# ỌRÛNMLA !

NIPA




**E. M. LIJADU,**

Alufã Ajihinrere-Iọfẹ, Ondo.


---

1908.

# ỌRÛNMLA !

NIPA




## E. M. LIJADU,

Alufã Ajihinrere-lọfẹ, Ondo.



1908.

— S. RICHARDS. ⁝ NOTTINGHAM —

*First Printed 1908.*
*Second Print 1972.*

*Printed by:-*

OMOLAYO STANDARD PRESS OF NIGERIA.
Akure Road, P. O. Box 3,
ADO-EKITI.



Alufā Lijadu ninu Igbó-Ifá.

# IFIJUBA.



ALUFA TOM HARDING.—Ȍyinbó onísẹ Olọrun tí o se Ọgá-Ìwé fun awọn Akẹ̀kó Isé Olọrun ni Ile-Ẹkọ Giga ti C.M.S. li Èkó lati ọdun 1884 dé 1887,—Alabojuto Isẹ Olọrun l'Abẹokuta lati ọdun 1888 de 1895,—Ìríju ati Akọwe fun C.M.S. lati ọdun 1896 de 1902,—Alabojuto Isẹ Olọrun l' Ibadan lati ọdun 1892 titi di ọ̀ní;—ati nipa ānu Olọrun, Iwọ tí o kù li àbọbá lārin awọn Ȍyinbó onisẹ Olọrun ni gbogbo Ìwọ-òrun Afrika,—Iwọ ni mo fi Ìwe kekere mi yi jūba loni.

Nigbati isẹ da awa mejeeji pọ ninu Ile–Ekọ Giga ti C.M.S. li Eko lati ọdun 1885 de 1890, Iwọ bi ọga-isẹ naa ati emi bi alagbaṣe, Ọlorun gbin igi-ore kan saarin wa; O fi i fun awa mejeeji lati maa roko-sí, On paapaa si nrojo ibukún rẹ le e lori. Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun pe igi-orẹ naa ti On gbin saarin wa ti hù, o gbilẹ, o si bẹrẹsi íso eso nisisiyi.

MO FI IWE YI JUBA RE ni iranti àniyàn rẹ ìgbanaa pe a bá le ri ọwọ awọn Iwe Kíkà li ede Yoruba lati maa ṣe bi íranwọ fun awọn Akẹkọ Iṣẹ Ọlọrun ni Ilẹ Yoruba sí ati-mọ ìwa ati iṣe awọn enia ilẹ wa daju, fun ìlo wọn bi Oniwasu lẹhin ọla. Ati nigbati o di mímọ fun ọ pe mo ngbìdánwò ati-ṣe akojọ iru awọn iwe bawọnyi, ọ̀pọ ìranwọ li o ti ṣe fun mi nipa ọrọ ìyanjú ati inawo rẹ fun mi si ọna naa. Ipasẹ tirẹ kannaa ni awọn Oyinbo miran bi awọn Oloogbe Alufaa J.W. Dickenson ati J. Brayne ati Yẹba Marion Goodall tẹlẹ nipa inurere wọn si ọna yi, —awọn ẹniti o ti goke odo Jordani si ibi isimi wọn. Ki Ọlọrun maṣai fi wọn si ipò rere lọwọ ọtún Rẹ lọhun.

Ninu awọn ọrẹ tootọ ti mbẹ laaye sibẹ ti kò si yẹ ki ng gbàgbe nihin ni Ọlọ́la obirin ti Arkidiakoni Melville Jones fun ìyanju rẹ igbagbogbo ti ó dabi tirẹ si mi ati si ohun rere gbogbo ti o jẹ ti ọmọ ìbílẹ Yoruba.

MO TUN JUBA NYIN O,— nitori ẹnyin kò korira 'Ṣekooní' nínu ẹnikẹni laarin Ilẹ enia dudu; kàka bẹẹ ẹnyin nfi tọkantọkan nyin kọ-ni pe 'Abá-ẹnu-lasan' kò le ṣọ ohun rere ti a nfẹ di t'ẹni.

MO TUN JUBA NYIN O, — nitori ẹnyin kò wipe ki ẹniti ó rí-jẹ maṣe jẹ, ẹnyin kò wipe ki alairí-jẹ f'ebi sùn, ẹnyin kò wipe ki ẹniti otutu npa maṣe yáná, ẹnyin kò wipe ki ẹniti ooru nmú maṣe sùn òyi, bẹẹni ẹ kò si wipe ki ol'igi eeji maṣe nọ'ṣẹ sina! Ki Ọlọrun bùkún iṣẹ nyin laarin wa, ki O si fi ọpọlọpọ eso ìtunú kẹ nyin latinu rẹ wá. Amin.

Iwe mi kekere yi jẹ kíkiní ninu eso naa; ṣugbọn adura ọkàn mi ni pe ki ó le jẹ agbara nla lọwọ awọn iranṣẹ Jesu Kristi ni ilẹ Yoruba, ati ki ó si le fi bẹẹ di iwe - àyọlẹ kan fun gbogbo enia

Emi ni Ọrẹ rẹ nitootọ
E. M. LIJADU

Gbàngan Ajihinrere-lọfẹ
Ode Ondo, July 7, 1907.

# SI AWỌN OLUFẸ IFẸ ILẸ IBI WỌN

Ẹnyin Olufẹ,

Bi ọjọ ṣe ng gori ọjọ, ti ọsẹ ng yi lu ọsẹ, ti igba si ng tẹle ra wọn: bẹ ẹ l'ọdun ori iwe yi ng di pupọ to bẹ ẹ ti a ko ba ri ẹni-bi-ẹni enia-bi-enia fọwọsowọpọ ṣe atunṣe ati atuntẹ iwe na ki nwọn si ran a s'ode fun ifihan ati kika gbogbo enia yio di igbagbe larin wa, iranti ki yio si si fun un mọ l'orilẹ ede wa yi i.

Pe Ọlọrun gbe awọn 'olufẹ ilẹ ibi wọn' dide ni sa a yi, ti nwọn si nfi t'ọkan t'ara ng fẹ ki aṣa ati itan ilẹ ibi wọn wa ni pipe ṣanṣan jẹ ohun ayọ ati iwuri fun mi. Awọn sa a li o rọ mi lati yọda atuntẹ awọn iwe mẹfa ti baba mi agba Ologbe Alufa E. M. Lijadu ṣe: a.n.:– (1) Aribiloṣo (2) Ifa (3) Ode Gaga Ara Ilujugbe (4). Gramma Yoruba (5). Ọrunmla ati (6). Sobo-Aro-bi Odu Apa I & II ati awọn iwe miran ti koi ti fi oju kan ẹrọ itẹwe.

Nigbati ohun wa si ti ṣọkan lori eto yi, a da ẹgbẹ kan silẹ ti a pe ni 'Ẹgbẹ Oludabobo Aṣa Yoruba.' Iṣẹ ẹgbẹ yi ni lati ma a ran ẹnikẹni ti o ba ni ifẹ aṣa ilẹ Yoruba lọwọ. Ẹgbẹ na a yio ma ṣe iranlọwọ fun titẹ iwe ti o ba niye lori ti yio si ṣe ilẹ wa yi ni rere, bakanna a ni yio ma sa gbogbo agbara rẹ lọnakọna lati ri pe awọn ohun abọba ilẹ wa ti o ṣọwọn ko po o ra mọ wa loju bikosepe a lo wọn fun ire, ogo ati igbẹkẹle orilẹ-ede wa. Nitori idi eyi..............................

Mo juba Ọlọrun Ẹlẹda, Ẹniti o fi apakan ọgbọn rẹ ta wa lọrẹ. Mo si dupẹ gidigidi lọwọ awọn enia wọnyi – ti wọn ba mi pilẹ ẹgbẹ yi ti wọn si ṣe akojọ owo fun atunse ati atuntẹ awọn iwe na a. e.n.:– Oloye S. A. Fawẹhinmi. (2). Iyaafin Fọla Faṣida. (3). Ọgbẹni Dọtun Odunuga. Ibẹrẹ li eyi, a ni igbagbọ wipe ẹ o tẹwọ gba awọn iwe na bi wọn ba ṣe njade li ọkọọkan gẹgẹ bi awọn baba wa ṣe gba wọn tayọtayọ niṣa-aju. Mo si ni ireti pe lẹhin eyi, ẹ o gbiyanju lati darapọ mọ wa ninu Ẹgbẹ Oludabobo Aṣa Yoruba. Mo ki yin o ẹniyin ara: Mo juba yin o ẹnyin agba, ki Ọlọrun ma fi eyi ṣe aṣemọ fun wa o. Aṣẹ.

Emi ni Tiyin Nitotọ,
Ẹniọwọ E. A. LIJADU,
Oniporisan Kẹta
Alufa Ajihinrerelọfe,
Ondo.
10 : 12 : 71.

Ajihinrerelọfẹ House,
64, Lokun Street,
P. O. Box 76,
Telephone 85,
Ode-Ondo.

# ORUNMLA

Bí a o sọrọ Ọrùnmlà li asọjàlẹ̀, a kò le ṣaisọrọ ohun mẹta wọnyi sí i — Ekíni, ohun Iwa-Ọlọrun tí awọn babanla wa pín fun u: ekeji, ohun Iwa-enia ti nwọn fifun u pẹlu: ẹkẹta, awọn èkọyẹkọ ti o ti ẹnu rẹ̀ jade.

Ekini ni nikan li a o dáwọle nisisiyi ninu iwe yi; a o fi meji iyoku silẹ dígbọṣe.

Nwọnyi li ookì Ọrunmla tí a fi ṣe ipilẹ àṣaro wa ninu iwe yi—

"ỌRUUNMLA, Elẹerí-ipìn; Ibikeji Olodumare:
"A-jẹ-ju-oogùn, Obírítii,-A-p'ijọ-ikú-dà.
"Oluwa mi àmòimọtán, —a ko m ọ o tán kò ṣẹ,
"A bá mọ̀ ó tán ìbá ṣẹ kẹ̀.
"Oluwa mi Ọlọwà àiyẹrẹ; Ọmọ Elẹ́sín Ile-Ọyín,
"Ọmọ ọl'ọpẹ̀ kan t'o s'aran dọgi-dọgi.
"Oluwa mi òpòkí a-mú-idẹ-s'oju,
"Eekàn kò jẹ̀ k'ẹkùn họra, aṣákà-ṣaaka àkún;
"Ọmọ Ọsọ́-gínni Tàpà ti nw'ẹwu ninii;
"Ọmọ Ọsò pa'dẹ mọ́wọ pa'dẹ mesẹ̀ o mbeere àtẹ̀paa òjé.
"Oluwa mi Igbo, ọmọ iyan bírikiti inu odó;
"Ọmọ igbà ti nṣ'ọ̀pẹ jiajia.
"Ikú dúdú àtẹwọ, Ọrọ aj'epo má pọn;
"Agìrí Ile-Ilọgbọn, a-b'oloowú díwẹ̀rẹ̀ má ran.
"Oluwa mi A-tó-íba -jaiye, Ọrọ a-b'íku-j'igbò;
"Oluwa mi Àjíki, Ọgẹ̀gẹ̀ a-gb'aiye –gún:
"Odùdù tì ídù orí emère; ó tún ori ti kò suàn ṣe.
"Omọ el'ejò tí nrìn mìrìn-mìrìn lori ewé,
"Ọmọ àrin ti írìn Ode-Òwọ ṣàka-ṣàka."

NINU ookì wọnyi a rí iṣi kan ti o tọka sí ohun Iwa Ọlọrun, a si rí iṣi miran ti o tọka si ohun Iwa-enia: a o kọ mu awọn ookì ti o bọ̀ sabẹ iṣi ekini lọroorí.

# ORI I

## "ỌRUNMLÀ."

Itumọ orukọ yi bi a ti gbọ ọ lẹnu awọn babalawo ni pe "Ọrun li o mọ oola ìja," tabi "Ọrun li o mọ ìlaja." Nipa orukọ yi awọn keferi ilẹ wa jẹwọ pe ìja kan pàtaki mbẹ laarin aiye ati ọrun, ati pe awọn kò mọ ẹniti yio làja naa, bẹẹni awọn ko mọ ọna ìlaja naa. Ninu awọn ẹsẹ-ifá ti o tẹle nihinyi a o ka ti ija yi.—

**1.** "Ọrunmlà ní 'ó di paaramiilà;' mo ní 'ó di paaramiilà;' ó ni * 'ọdẹ aiye t'on t'ọdẹ ọrun mà pade loni ná o!' "—Irosu-Egután.

---

* Nijọ kan, Ọdẹ ọrun ran aya rẹ wa sọja aiye, awọn araiye ko mọ ọ, nwọn ba a ja nwọn lu u: sugbọn Ọdẹ aiye ri bi a ti njẹ ẹ ni iya, o saanu rẹ laimọ ọ ri, o gba a silẹ lọwọ wọn. Nigbati obirin naa pada de ode ọrun, o rohin fun ọkọ rẹ iru iya ti araiye fi jẹ on, ati bi Ọdẹ aiye ti saanu fun on. Njẹ ọdẹ ọrun ranṣẹ dupẹ lọwọ ọdẹ aiye, o si bẹ ẹ ki o masai wa pade on ni ipinna aiye on ọrun titi ọjọ mẹta. Ọjọ pé, awọn ọdẹ mejeeji gbé agbé ẹmu kọọkan wa sibi adé; nigbati nwọn ri 'ra–wọn, nwọn yọ, ẹnikini si fi agbé ẹmu ti o gbe wa tọrẹ fun ẹnikeji rẹ bi ohun adé. Bi nwọn ti jumọ nmu ẹmu yi nwọn nsọ asiri iwa aiye on ọrun fun ara-wọn, nwọn si nta gẹdẹgẹdẹ inu ago wọn sori ilẹ nibikannaa. Nikẹhin nwọn pinnu ati-ba ara wọn da majẹmu, ki oju ilẹ it'-ọsẹ-si yi le di ibi oritẹ fun ati enia ati ẹranko. Lati se e daju, nwọn gbé ọfin jijin kan sibẹ gangan, nwọn si fi irawé bo o loju pe ẹnikẹni tabi ohunkohun ti o ba dasẹle oju ibẹ ki o maa lu ọfin.

2. "Èkiti pętę, adafa fun Ọdę aiye a bú fun Ọdę ọrun; "aní ki nwọn rú ęiyęle mẹrin on ęgbẹrin, ki igbó tí nwọn nlọ "dę lè ṣàn wọn. Ọdę ọrun nikan l'ó rú, *Ọdę aiye kò rú."– Ìrosu-Ègútan.

---

pęlupęlu nwọn se ibura pe ęni ti o ba tète de ibę ki o maa la ohunkohun ti a ba ri ninu ọfin naa lọgbọọgba lati mu idaji ki o si ku idaji silę fun ęnikeji. Etu jin 'fin yi a la a, ękiri jin i a la a; nkan ko tè nkan ko wọ. Aja ọdę ọrun lu ọfin yi; nigbati ọdę aiye ba a nibę o la a meji gęgę bi adehun, o fi idaji silę fun ọdę ọrun. Inu bi ọdę ọrun lati ri iwa ọdaju yi, nitorina li o ṣe lọ ifi ọdọ eku kan bę esu lọwè ki o le ba on gbęsan lara ọdę aiye. Esu gba, eṣu gbọ. Bi iya ọdę aiye ti nja ewe ęlu kiri ni agbegbe ibę, èṣu bi i lọ jin s'ọfin yi, o si yara lọ iwi fun ọdę ọrun. Ọdę ọrun ko benibęji o la arugbo naa: bi o ti ngbe idaji tirę lọ ni ọdę aiye de, o ke; inu bi i o ni, "biotiwu ki o ri, iwọ le wipe o ko mọ iya mi?" Oni-tọhun dahun o ni "biotiwu ki o ri, iwọ na le wipe o ko mọ aja mi?" Awọn mejeeji bęręsi ija, o si pọ tobęę gbogbo araiye pejọ lọtun, gbogbo ara ọrun pejọ losi; ko si ęniti o to isunmọ ibi ija yi, tọtuntosi nkigbe si ara-wọn wipe "ę la wọn, ę la wọn!" Awọn miran si nwipe "tani yio la wọn, tani yio la wọn?" Nigbayi ni Olodumare to ijade wa si aala ija naa. O si beere idi rę O gbọ tan, o ni ki awọn mejeeji lọ mu ogoogoji wa, nwọn se bęę. Olodumare wa tun awę meji oku arugbo naa le-pọ o si sọ ọ di odidi; ṣugbọn o fi ogoji kan sami si ibiti a ti la a; o si fa iya ọdę aiye fun u pada; inu ara aiye ati ara ọrun dun tobęę ti gbogbo wọn da ohun pọ nkigbe wipe "Ọrun mọ wọn ila! Ọrun mọ wọn ila!" Ayaani a mgbọ orukọ ORUNMILA. Awọn ọdę mejeeji si mu imọ kansoṣo nwọn di i mu nibi èji rę, nwọn fa a ya mọ 'ra wọn lọwọ lọgbọọgba nwipe "Paramila, paramila, ọdę aiye on ọdę ọrun ko ni iri 'ra mọ lai. Ayaani a nya imò kò 'ra ęni li ębi laini atunṣe mọ.

* Lati ọjọ ajayamọ ni, Ọdę aiye ati ọdę ọrun ko tun nfoju kan 'ra wọn mọ kiki pe nwọn a maa kèsi ara-wọn bi ọkan ba sọdę ja ipinna. Bi Ọdę ọrun ti ndęgbę tirę lọ nijọkan, o ba ęyin nla marun kududkudu pade labę pantiri o si ko o. O de ipinna o kèsi ęnikeji rę wipe "Odę aiye pèlé o, wa ko nkan ti mo fi silę dè ọ nibi yi o; " o wi tan o pada 's' ileba tirè. Ọdę aiye ti ko ri ęran pa nijọ yi wa wo ipinna, o ba ęyin nla meji wọnyi, o ko wọn lọ tayọtayọ; wara ti o si ti de ileba rè, o sè wọn ję. Ojumọ Ọdę ọrun lọ ibę awọn ęyin męta tirę wo nibiti o ko wọn lọ ipamọ si, ęnu ya a lati ba ęgbawa owo-okun niwaju ęyin kọọkan: o si yara gbe owo naa kuro, o tun ilę ibę ṣe daradara. Ojumọ ọjọ kęta mọ, o tun ba owo bęę nidi ęyin kọọkan. Nigbana ni o wa ilọ si ipinna o si kè - si ęnikeji rè, nwọn si nję 'ra wọn bayi:— "Ọdę aiye, pęlę o!"

"O-o-o-o-o-o-o."
"O ti ṣe ęyin rę ijęta o?"
"Sisè ni mo sè e ję o"
"B'o l'o ti ri lęnu rę o?"
"O ma dun ladunju o!"

Nigbana ni Ọdę ọrun dahun wipe "Haa! o tan o ku o, iwọ ọdę aiye ko ni ila mọ o." Ṣugbọn ọdę aiye yara dahun wipe "Eyi o wu ki a gbe inu ile aiye sè, Ọrun li o ma ni Ila o!" Ayaani a nwipe "Orun-nila. Ọrunmla.

3. "Àjó awo Ile-aiye, Àbemọ awo ode Isàlu-ọrun, awọn "mejeeji ni mpade kòmọn'ìpínnà aiye on ọrun: a ni ki nwọn "rubọ ki obirin kanṣọṣo t'o wà laarin wọn má le ba èto jẹ mọ "wọn lọwọ. Awọn mejeeji ş'eti gbọnran s'ẹbọ nwọn kò tu 'Fa "nwọn ní kini obirin kanṣọṣo ìbà ti ṣe le ba èto aiye on ọrun "jẹ mọ́ ẹni bi awọn lọwọ?" — Ọbara-meji.

4. "A-r' ọọtẹ-sá kò ṣ' ojo. Oyin ṣí tan f'afá de'lé, eerún "ṣi tán f'àgan de'le; a dífa fun *araiye a bù f'ara ọrun nigba "nwọn ngbogun ti 'ra wọn; a ni ki kaluku wọn rú akoto kan "oyin on akoto kan ẹkọ fifọ́. Ara ọrun nikan l'ó rubọ: araiye "gbọ́ nwọn kò rú." — Iretẹ-'Sá.

---

*Obirin naa a maa jẹ Obi, aya Àbemọ awo ode isalu ọrun ni ise. Àbemọ ti lọ idebọ si ọran ara obirin rè yi , a ni ki o ru ewurẹ dudu kan on ẹgbaafa ki o le bimọ, eiyẹle mẹrin on ẹgberindilogun ki owo le ya wa ba wọn. Àbemọ ru ti owo ko ru ti ọmọ. Ojọ mpe Obi ko bimọ, inu rẹ̀ bajẹ; o si sa wa ifẹ Ajo awo ile-aiye. Àjo da awo, ebọ ijọ́si ti a yan fun Àbemọ fun Àjo. Àjo gbọ o rubọ ọmọ, Obi si bi ọkanṣoṣo fun u. Nigbati ọdun yipo, ti ọjọ ati -lọ si ikomọ pe, Obi tẹle Àjo lọ ipade Àbemọ: inu bi Àbemọ pipọ lati ri pe Àjo tè obirin on mọ́wọ kadun li aitifi ranṣẹ si on: bẹẹni Àbemọ bẹrẹ si ọrọ buburu isọ si Àjo. Àjo si mbinu ẹwe pe Àbemọ ko tilẹ mu suuru gbohun kan lẹnu on ti on diyeinu mu Obi latinu ile-aiye wa ipade rè. Bẹeni ija di nla laarin wọn. Obi takete s'okeere on nworan wọn, ko si ẹniti yio laja o di ajakụ. Nigbati o rẹ awọn mejeeji ti wọn si nsimi lọwọ ni Àbemọ wa ikesi Àjo wipe "Ija iwère ni a ma ngbe ipinna aiye on ọrun ja yi o: ko si omuuja, ko si ọlaja; nitori ki aiye le bajẹ ki ọrun le bajẹ ma ni Obi se ti ọdọ emi Abemọ lọ sọdọ rẹ. Njẹ , Iwọ Àjo awo ile-aiye o ma wa ki a m'eti ko eti, ki a mu ohun s'apo o!" Bẹẹni inu awọn mejeeji si tutu, nwọn si lọ iwọ̀ ikomọ: nibẹ ni nwọn si ti peropọ lati wa pa Obi tan ija aarin wọn. Nwọn ṣe bẹẹ nitootọ, nwọn di oku Obi sinu apo kan, nwọn si fi ha s'ẹgbẹ igi kan li ẹba ọna, nwọn ba tiwọn lọ. Nijọ kẹta ni Orisa nkọja lọna ibẹ o ri oku Obi li ẹgbẹ igi, o ji i dide o si bi i leere bi o ti se de ibe. Nigbati Obi rohin fun u tan, orisa dahun pe "o dara o, ng ko le ja wọn niyan; eyiti nwọn se naa ko buru o." Bẹẹli o si tun di Obi sinu apo naa, o si fi ha sibiti o gbe ba a li ẹgbẹ igi, o ba tirẹ kọja lọ, Ayaani oo ri i, a mpa obi tan ija gbogbo ni ilẹ wa.

*Ni saa kan, awọn araiye sigun nlọ ba ara ọrun ja; ṣugbọn bi nwọn ti de ẹhin-odi ọrun nwọn ba ọpọlọpọ akoto ẹkọ-fifọ ti a po oyin igan mọ, nwọn ko mọ pe ewọ mbe nisalẹ gbogbo akoto wọnni, nwọn fi iwọra bẹrẹsi ẹkọ naa imu. Loru ọjọ naa ni gbogbo wọn ku patapata si ẹhin-odi ọrun. Ojumọ mọ ni jọ keji, awọn ara ọrun jade si ẹhin odi, nwọn ba kiki oku araiye bẹẹrẹbẹ: nwọn wa ina oku meje ni pasan dide ni igun mẹrẹẹrin ibudo araiye,

5. "Òke-yì-gbiri-wọ 'dò l'o difa fun araiye o bù fun ara "ọrun nlọ jùmọ wotẹ, nijọ ti nwọn yio jija ègbọn lori ẹran edú "kanṣọṣọ tí nwọn rí-pa; a ní ki araiye mà ṣe mẹlọ-mẹlọ fun ara ọrun ò: araiye kọ nwọn kò gbọ, ìja dé." —Ẹjiogbe.

6. "Hoo-hoo-mòdè l'o difa fun Àṣá, a bú fun Àwodi, a bú "fun Igún s'ẹkẹta gbogbo wọn; nijọ ti nwọn nleri pe awọn yio "gbé * ẹbọ ọmọ araiye lọ de ọrun. Àṣa lọ titi o rẹ ẹ o já wá'lẹ.

---

nwọn ni ki awọn mejeje nwọnyi maa ru oku ẹgbẹ wọn kuro li ẹhin odi awọn. Bayi ni awọn araiye diẹ ti a ji-dide nwọnyi nwahala putu ni riru oku awọn ẹgbẹ wọn pade ara yi ibudo wọn ka: awọn ara ọrun si wa nkọrin iya le wọn lori bayi pe:–

" 'Oyin l'a mu'
"Ko ma le b'ara ọrun ja o,
'Oyin l'a mu.'
O gb'ogbo ọlẹ b'ọlẹ ja o,
'Oyin l'a mu'
Ko ma le b'ara ọrun ja o
'Oyin l'a mu."

Àyaani oo ri i bi araiye ti nru oku ara wọn kaakiri ninu aiye; oku li o nru oku.

*Ẹkiri kanṣoṣo naa ti araiye ati ara ọrun wotẹ pa l' o da ija silẹ laarin wọn; nwọn ko fẹ ila a meji, ara ọrun ni awọn ni igbe e l'odidi, araiye ni awọn ni igbe e l'odidi, ija de. Ara ọrun binu kọ ẹran naa silẹ fun araiye nwọn si pada lọ sọrun lọ imu ojo. "Kirikiri m'aiye, dugbẹdugbẹ m'ọrun, ojo kakaka ko ta silẹ, ọmọ ẹiyẹ ko ri 'un sa-jẹ." Nigbati o pọn mọ araiye tan ni nwọn gbe ẹran ẹkiri naa silẹ, nwọn nwa ẹniti yio gbe e lọ sode ọrun fun wọn: olukuluku ẹniti nwọn filọ nsa nwọn ko fẹ ilọ. Nikẹhin ni nwọn wa ilọ gba aboyun kan mu, nwọn di ẹru ẹran naa ru u, nwọn ti i jade sọna ọrun. Aboyun gbe ẹru rẹ de ọrun aanu se Olodumare o ni "Nitori ki iwọ aboyun le ku sọna ọrun kọ li awọn araiye ṣe ti ọ jade yi? Njẹ, iku ko ni ipa ọ, arun ko ni igbe ọ de; mura ki o wa pada lọ inu aiye o." Olodumare paṣẹ a gb' agbè omi kan le aboyun lori, a ni bi o ba ti de inu aiye ki o fọ ọ mọlẹ. Obi mu aboyun bi o ti wọ inu aiye, irora si mu ki o wa 'gbe omi mọri, o gbagbe ati-fọ ọ mọlẹ. O wọnu ile tirẹ tan ki o to iranti fọ ọ, o si bimọ lojukannaa sinu agbara omi naa. Àyaani oo ri i, aboyun mbi sinu agbara omi-'ra. Gbogbo aiye gbọ pe aboyun de nwọn nwọ wa 'ki i wipe, — 'O ku at' ọrun bọ!' Àyaani oo gbọ bi a ti nki aboyun ti o bi titun. Aboyun bi tan a nwa omi ifiwẹ ọmọ bẹẹni ojo giiri kan o si rọ ka gbogbo aiye.

*Nigbati ojo yi rọ titi, o pa gbogbo ina aiye run ṣuṣu, ọmọ araiye ko tun ri ina se onjẹ mọ; nigbanaa ni nwọn lọ wa ẹbọ ti nwọn yio lọ fi gba ina pada ti ọrun wa. Ẹbọ yi li a ru silẹ tan ti a ko ri ẹniti yio gbe e lọ, ti aṣa awodi ati igun nleri ati-gbe e de ode ọrun fun wọn. Àsa li o kọ gbe e, gbogbo ọmọ araiye si pejọ nisalẹ nkọrin bayi fun u bi o ti ngbẹbọ naa lọ wipe:—

"gbírihan, Awodi lọ titi o rè ẹ, o já wá 'lẹ̀ gbìrihan, Igún nikan "I'o mà gb'ẹbọ ru de ode ọrun ninu wọn ò!"—Ọsá-'Wòri.

Akiyesi.— Awọn ẹsẹ-ifá nwọnyi ati ìtan wọn ti a kà nihin fihan dajudaju pe ọkan awọn baba-nla wa njẹ́ wọn lẹri pe ìja kan mbẹ laarin aiye ati ọrun; ati pe ìja naa bẹ̀rẹ laarin ẹnikan ti o duro fun gbogbo aiye ati ẹnikan ti o duro fun gbogbo ọrun; ati pe ìja naa ṣẹ̀ lori ohun kanṣoṣo ti t'ọtun-t'òsi wọn ní oju sí ati pe araiye kò ro ati-túmba fun ará - ọrun bikoṣe lẹhin ọpọlọpọ igbè; ati pe lati ọrun ni onilaja ti wá ati pe araiye kò rí ojurere ará-ọrun laisí ẹbọ on ètutu. Awọn otitọ nwọnyi ni iye lori jọjọ ninu ipilẹ ìsin awọn baba-nla wa; nitorinaa a o mú awọn ohun akiyesi wọnni wá si ẹ̀gbẹ́ ọrọ Iwe mimọ Ọlọrun fun ifiwé ki a ba le ri itoye wọn.—

(a). Ija kan mbẹ laarin aiye ati ọrun.

(b). Ija naa bẹ̀rẹ larin ẹnikan ti o duro fun gbogbo aiye ati ẹnikan ti o duro fun gbogbo ọrun.

Gene. iii, 17–19, 24 "O si wi fun Adamu pe, Nitoriti iwọ gba ohun aya rẹ gbọ, ti iwọ si jẹ ninu eso igi naa, eyiti mo ti paṣẹ fun ọ pe, iwọ ko gbọdọ jẹ ninu rè; a fi ilẹ bú nitori rẹ; ni ipọnju ni iwọ o maa jẹ ninu rè li ọjọ aiye rẹ gbogbo; Ẹgun on òṣuṣú ni yio maa hù jade fun ọ, iwọ yio si maa jẹ eweko igbẹ: Li oogùn oju rẹ ni iwọ o maa jẹun titi iwọ o fi pada si ilẹ; nitori inu rẹ li a ti mu ọ wá, erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si pada di

---

"Hohomode, Homode: (2)
Àṣa mgbẹbọ r'ọrun, Homode:
O jo-jo ee mu 'jo, Homode:
O ra-ra ee mu ra, Homode:
O f'ẹhin gb'ọrun tè o-mode, Homode. (2)

Nigbati asa ṣe e titi awodi gbe e, a nkọrin naa fun awodi, bẹẹ gẹgẹ nigbati igun gbe e. Igun gbe ẹbọ de ọrun tan, a de ina mọnu igba ademu kan fun u wa, a si kilọ fun u ki o maṣe fi igba naa kan ilẹ titi yio fi de inu aiye.

Igun de ori apata gbaramsa kan lọna o ni on yio simi diẹ, o si gbe igba naa ka ori apata; ṣugbọn bi idi igba naa ti kan-lẹ, bẹeni ina fo-yọ latinu rẹ o si la igun lori borokoto. Àyaani oo ri i "Igun ṣe rere o pari."

erupẹ. Bẹli o le ọkunrin naa jade; o si fi awọn kerubu ati idà ina dè iha ila-òrun ti njù kaakiri, lati maa ṣọ ọna igi iye naa."

Rom. V. , 17–19. "Njẹ bi nipa ẹṣẹ ọkunrin kan iku jọba nipa ẹnikan; melomelo li awọn ti ngba ọpọlọpọ ore-ọfẹ, ati ti ẹbun ododo, ti nwọn yio si jọba ninu iye nipa ẹnikan, Jesu Kristi.

Njẹ bi nipa ẹṣẹ ẹnikan idajọ ba bá gbogbo enia si ẹbi; gẹgẹ bẹẹni nipa ododo ẹnikan, ẹbun ọfẹ de fun gbogbo enia ni idalare si iye. Nitori gẹgẹ biotiṣe pe nipa aigbagbọ ẹnikan, enia pipọ di ẹlẹṣẹ bẹẹni nipa igbagbọ ẹnikan, a o sọ enia pipọ di olododo."

I Kor. xv., 21–22. "Nitori igbati o ti ṣe pe lati ipa ọdọ enia ni iku ti wá, nipa ọdọ enia li ajinde ninu oku si ti wa pẹlu. Nitori bi gbogbo enia ti ku nipa Adamu, bẹẹni gbogbo enia yio si di aaye nipa Kristi."

Ninu awọn ẹsẹ-fa ti a fi òrọ mimọ wọnyi gbèlohùn, a ri pe orukọ nwọnyi—" Ọdẹ aiye, Ajọ; "Ọdẹ ọrun, Abemọ;"— li a fi tọka si awọn ẹni naa ti o duro l'ọtun ati l'osì bi orí fun araiye ati ara-ọrun.

Ipò ọdẹ ni ilẹ wa ki iṣe kekere; fun ati-là ọna titun, fun ati-tẹ ilu titun, fun ati-dá ija silẹ on ati-pari ija, gbogbo wa li a mọ ipa tí ọdẹ kó ni ilẹ wa.

Ajọ ati Abemọ.— Ki iṣe orukọ bikoṣe iṣẹ ti a pín fun wọn ni mo fẹ ki a kiyesi nihin: *e.n. pe awọn mejeji a maa pade ṣe ikomọ ni ìpinna aiye on ọrun lẹẹkan lọdun. Awọn babalawo wipe Ajọ ni Olodumare fi ṣe ojú ara-rẹ sinu aiye nigba ìwa ṣè, O si fi gbogbo atunṣe aiye lé e lọwọ; ati pe Abemọ duro ni ipo kannaa li ọrun bi oju Ọlọrun ati alatunṣe ọrun. Nigbati Ajọ

---

*e.n. jasi akọmọna "eyini ni."

ati Abemọ ba pade ìkomọ, Àjọ́ ni isọ gbogbo ohun ti ọrun fi ṣe aiye lati èṣí wa; Àbemọ a si sọ gbogbo ohun ti aiye fi ṣe ọrun: awọn mejeeji a si sọ idi abajọ fun ara-wọn, nwọn a si jùmọ gbé ọ̀ran aiye on ọrun si ètọ. Èro yi jẹ́ pataki kan ninu ipilẹ ìsin ti nmú awọn baba-nla wa pejọ lọdọọdun bi agbajọ ilu fun ati-bọ awọn eniti o tẹ ẹya tabi orilẹ dó ti nwọn imaa pè ni 'egúngun—ìṣẹ̀lẹ̀.'

(d) Ija na ṣè lori ohun kanṣoṣo ti t'ọtun-t'osin wọn ni ojú si.

Odẹ aiye ati odẹ ọrun ndẹ ọ̀fin kanṣoṣo lati pín ohun gbogbo ti o bọ̀ si i dọgbadọgba; araiye ati ara ọrun jùmọ wotẹ pa edú kanṣoṣo ti ara ọrun kọ̀ ati-pín fun araiye ninu rè rára. Kili ohun ti iwọnyi ndù lati fihan bikoṣe (1) írẹrasilẹ tí Ọlọrun tí O ni ohun gbogbo si fi mbá awa enia pín ohun gbogbo tobẹẹ ti ọfẹ́ ati òfò fi jẹ́ òdì mejeeji aṣọ kanṣoṣo. Eyiini ni pe ohun ti o jẹ́ ọfẹ́ fun wa jasi òfo fun Ọlọrun, ohun ti o si jẹ òfo fun wa jasi ọfẹ́ fun Ọlọrun. Èro yi jẹ́ pataki kan ninu ipilẹ ìsin tí nmú awọn keferi ilẹ wa ma tọsẹ̀ kili o dá òfo ti Ifa ba wipe on rí si wọn. Bi nwọn ba si ti gbọ̀ pe ará-ọrun li o dá òfo ti mbọwa ná, nwọn kì tun beere pe "kíli awọn fi ṣe ara-ọrun o?" Ṣugbọn lẹsẹkanna ni nwọn a maa túmba nipa jijẹwọ gbogbo ọna ti o ba hàn si wọn pe awọn ti njẹ ọfẹ́ laijuba ibiti ọfẹ́ naa ti wá. Èro kannaa yi ti o li ẹru fun wọn jọjọ li o wà nisalẹ gbogbo suuru ati ipamọra ti nwọn imaa fi gba òfo ti o ba ṣe wọn pe "Ọlọrun li O fẹ́ beẹ."

A si rí pẹlu niti 'edú kanṣoṣo' (2) irira ti Ọlọrun Olodumare ní si àbuku ìsin ati aabọ ọkan. O yá fun U lati kọ̀ gbogbo ìsin ati ọkan naa ti ó mú u wá ju lati gbà wọn li abuku ati aabọ. Ẹsẹ ekini ti o bẹ̀rẹ orí ekini ninu Ifa jẹri si ọlanla yi ninu Ọlọrun. Ẹsẹ naa wi bayi pe.—

7. "Ọ̀tọ̀tọọtọ̀, Ọ̀rọ̀rọọrọ̀; ọ̀tọtọ * l'a ijẹ̀pà, Ọ̀tọtọ l'a

---

*Olukuluku ọrọ nwọnyi 'Ọtọ̀tọọtọ̀' 'Ọrọ̀rọọrọ́' 'Ọtọ̀tọ̀' 'Tori-tori 'jẹ́ ede

ije ímuumuu; "torí-tòrì l'a ifun Ọbamaakin n'Ile Iranjé ki ó le baa f'ohun torí-tori funni."—Èjiogbe.

(e) Araiye kò rò ati-tùmba fun ara-ọrun bikoṣe lẹhin ọpọlọpọ igbè. —

Ọpọ "ipọnju ati iloyun," Ọpọ "ẹgún on òṣuṣú," ọpọ ìle-ni "kuro laarin enia" ati onjẹ enia si "ibugbe awọn ẹranko igbẹ" ati si "jijẹ koriko bi maalu," ọpọ "kíkun-omi," ọpọ "ìdarú-ède," ọpọ "òjo sulfuri ati iná," ọpọ "idá ati iyan, ati ẹranko buburu, ati àjakalẹ arun, " ọpọ ikú;—kò ha ṣe pe nwọnyi li o kámbà ọmọ araiye, li o tẹ agídi ọkàn wọn, ti o si nmú wọn túmba fun Ọlọrun!

Èro yi jẹ pataki kan ninu ipilẹ ìsin ti nmú awọn keferi ilẹ wa maa tọsẹ kíli o dá ikú tabi àrun, tabi ẹjọ́, tabi òfo ti Ifa ba wipe on rí si wọn. Nitorinaa bi Ifa rí iku si wọn, nwọn a bi i

---

ti a nlo lati tọka si ohunkohun ti o wa ni kikun, pipé, ati ailabuku. Ọbaiala li a pe ni Ọbamakin ninu ẹsẹ-ifa yi. Mu ẹsẹ-ifa naa wa si ẹgbẹ́ ọrọ mimọ tinu Bibeli.—

Lef. xxii. 20–21. "Ṣugbọn ohunkohun ti o ni abuku, li ẹnyin ko gbọdọ muwa: nitoripe ki yio da fun nyin. Ati ẹnikẹni ti o ba ru ẹbọ alafia si Oluwa lati san ẹ̀jẹ́, tabi ẹbọ ifẹ-atinuwa ni maalu tabi agutan, ki o pe ki o baa le da; ki o maṣe si abuku kan ninu rẹ." 1 Kron. xxviii. 9. "Ati iwọ, Solomoni ọmọ mi, mọ Ọlọrun baba rẹ, ki o si fi aiya pipe ati fifẹ ọkan sin i: nitori Oluwa a maa wa gbogbo aiya, o si mọ gbogbo ete ironu, bi iwọ ba ṣafẹri rẹ, iwọ yio ri i; ṣugbọn bi iwọ ba kọ ọ silẹ, on yio ta ọ nu titi lai." Wo xxix. 17–19. "Emi mọ pẹlu, Ọlọrun mi, pe iwọ ndan ọkan wo, iwọ si ni inudidun si ododo. Bioṣe ti emi, ninu ododo ọkan mi li emi ti fi tinutinu ṣe iranlọwọ gbogbo nkan wọnyi; ati nisisiyi pẹlu ayọ ni mo ti ri awọn enia rẹ ti o wa nihin lati fi tinutinu ṣe iranlọwọ fun ọ Oluwa Ọlọrun Abrahamu, Isaaki ati Israeli awọn baba wa, pa eyi mọ lailai sinu ete ironu ọkan awọn enia rẹ, si fi idi ọkan wọn mulẹ si ọdọ rẹ: Si fi ọkan pipe fun Solomoni ọmọ mi lati pa ofin rẹ, ẹri rẹ ati ilana rẹ mọ."

Isa. xLii. 8 "Emi li Oluwa: eyi ni orukọ mi; ogo mi li emi ki yio fifun ẹlomiran, bẹ̀ẹni emi ki yio fi iyin mi fun ere gbigbé."

Joh. iv. 23–24 "Ṣugbọn wakati naa mbọ̀, o si de tan nisisiyi, nigbati awọn ti nsin li otitọ yio maa sin Baba li ẹmi ati li otitọ: nitoripe iru awọn ẹni bẹ̀ẹ ni Baba nwa ki o maa sin on. Ẹmi li Ọlọrun: awọn ẹniti nsin i ko le ṣe alaisin i li ẹmi ati li otitọ.

lere pe "ikú araiye tabi ti ara-orun?" bi o rí ẹjọ si wọn, nwọn a bi i pe "ẹjọ ara-ọrun tabi ti araiye a-b'ojú perekete?" Bi ìbo ba si mu ara-ọrun ninu ọ̀na ibi wọnyi, nwọn ki ítun beere pe "kíli awọn fi ṣe ara-ọrun o?" Iesẹkannaa ni nwọn imaa ítumba nipa jijẹwọ gbogbo ọna ti o ba hàn si wọn pe awọn ko sin tó: nwọn a si mura ati-ṣe gbogbo ètutu ati atunṣe ti mba mbẹ ni ipa wọn.

(e) Araiye kò le pada rí ojurere Ọlọrun lai-si ẹbọ on ètutu.

(f) Lati ọrun ni onilaja ti wá.

Gene. viii., 20–21. "Noa si tẹ pẹpẹ fun Oluwa; o si mu ninu ẹranko mimọ gbogbo, ati ninu ẹiyẹ mimọ gbogbo, o si ru ẹbọ-ọrẹ sisun lori pẹpẹ naa. Oluwa si gbọ oorun didun; Oluwa si wi li ọkàn rẹ pe Emi ki yio si tun fi ilẹ rè nitori enia mọ.

II Sám. xxiv., 25. "Dafidi si tẹ pẹpẹ kan nibẹ si Oluwa, o si rú ẹbọ sisun ati ti ìlaja. Oluwa si gbọ èbẹ fun ilẹ naa, àrun naa si dá kuro ni Israeli."

Heb. ix. 22. "O si fere ise ohun gbogbo nipa ofin li a fi ẹjẹ wẹnumọ: ati li aịta ẹjẹ silẹ imukuro ẹṣẹ ko si."

Ninu awọn ẹsẹ-ifa ti a fi ọrọ mimọ wọnyi gbè-lohun, a ri pe nigbati araiye nfẹ tumba tọkantọkan, nwọn fi eyi han nipa fifi ẹran-edú kanṣoṣo naa ti nwọn kò ti fẹ ífisilẹ rí ṣọwọ si ọrun: èwẹ, nwọn si fi ohun miran ti a yàn li ẹbọ fun wọn ṣọwọ si ọrun pẹlu li aijiyàn. Eyi naa gaan ni aiya ẹbọ.

Bẹẹ gẹgẹ li a si gbọ pe Olodumare tikalarẹ li ó wá ídùbú ija Ọdẹ aiye ati Ọdẹ ọrun; tabi bayi pe nigbati ko sí òmuúja tabi ọ̀laja laarin Ajọ̀ ati Àbẹmọ, Àbẹmọ tikalarẹ ti o ti ọrun wá li o si diyeinu nawọ̀ ilaja si Ajọ̀ awo inu aiye. Gbogbo nwọn yi ndù ati-fi otitọ naa han araiye pe lati ọdọ Ọlọrun ni ilaja ati onilaja ti wá íba araiye.

Isa. I: 18, "Oluwa wipe, wa nisisiyi ki ẹ si jẹki a sọ asọyé pọ̀: bi ẹ̀ṣẹ nyin ba ri bi òdodó, nwọn o si fún bi snoo; bi nwọn pọn bi àlaari, nwọn o dabí irun agutan." Isa. xiii. 15, "Tani eleyi ti o ti Edomu wa, ti on ti aṣọ arẹpọ̀n lati Bosra wá? eyiti o li ogo ninu aṣọ rẹ̀ ti o nyan ninu titobi agbara rẹ? Emi ni ẹniti nsọrọ li ododo, ti o ni ipa lati gbala. Nitori kini aṣọ rẹ fi pọ̀n, ti aṣọ rẹ wọnni fi dabi ẹniti ntẹ̀ ohun èlo ifúnti waini? Emi tikarami ti tẹ̀ ohun elo ifunti waini; ati ninu awọn enia, ẹnikan ko pẹlu mi; nitori emi tẹ wọn ninu ibinu mi, mo si tẹ̀ wọn mọlẹ ninu irunu mi; ẹ̀jẹ wọn si ta si aṣọ mi, mo si ṣe gbogbo ẹ̀wu mi li abaawọn. Nitori ọjọ ẹsan mbẹ li aiya mi, ọdun awọn ẹni irapada mi ti. Mo si wo, ko si oluranlọwọ; ẹnu si ya mi pe ko si olugbéro; nitorina apa ti emitikalami mu igbala wá sọdọ mi; ati irunu mi, on li o gbé mi ró. On si wipe: Lootọ enia mi ni nwọn, awọn ọmọ ti kì iṣeke; on si di olugbala wọn."

Eyi naa gaan li awọn keferi ilẹ wa npe ní "Ọ̀RUNMLA."

# ORI II

"Ẹlẹri-ìpín, Ibikeji Olodumare."

Ninu iwe wa iṣaaju a ti ṣe akiyesi yi pe awọn baba-nla wa gbagbọ pe ninu ọlanla Ọlọrun ti enia ko le mọ titobi rẹ yi, Olodumare ti fi Enikan ṣe ibikeji ara–Rẹ, On a si maa pe Oluwarẹ si ìmọ ninu ohun gbogbo, On a si maa fi ohun gbogbo hàn a, On si fi i ṣe ẹlẹri ara-Rẹ ninu ohun gbogbo, tobẹẹ ti ko si ohun ti Olodumare mọ tí Oluwarẹ na kò mọ, ko si sí ohun ti Olodumare rí ti On kò ri. Eni naa ni awọn npè ni "Ọruunmlà, Ẹlẹri ipín, Ibikeji Olodumare."

Njẹ, ọna wo ni Ọrunmla fi jẹ Ẹlẹri ìpín?

Awọn babalawo fi idahun si ibeere yi latinu odùifa wá gẹgẹ bi eyiti a kọ si isalẹ nihin.

(1) Ọrunmla jẹ Ẹlẹri-ìpín nitori On ati Olodumare li o jumọ nṣe ìkomọ lode ọrun.

3 "Olodumare pẹlu Ọrunmla lọ iti ara-wọn mọ ile-"ìkomọ lọrun, gbogbo ọrun nkẹ idarò wipe 'Tani yio lọ isílẹkun naa?'

Ẹtu gbọ o síwaju lọ íf'owọ le ilẹkun; bẹẹli Ọrunmla dahun lati inu ile nwipe, 'Lesí nkàn 'kùn Ọsìn kàkàkà, lesí nkàn' kùn Ọsìn lelele?' O dahun o ni 'emi Ẹtu ni, òbeje.'

"Ṣugbọn Ọrunmla dahun si i pe 'Ẹtu òbejẹ, Olodumare ní ki o dehin o; o tii mọ ìgbanaa rí? tabi o tii bá wọn lọ s'ikọmọ ri?" Bẹẹni Ẹtu òbejẹ pada sẹhin.

"Edú gbọ o ní on yio ba won ṣilekun; bẹeli Ọrunmla "beere wipe 'Lèsí nkàn 'kun Ọṣìn kàkàkà, lèsí nkan — "'kún Ọsin lelele?" O dahun o ní 'emi Edú ni, ìbaaraa "af'ìja gb' ọkọ;

"Ṣugbọn Ọrunmla dahun si i pe 'Edú ìbaaraa, Olodumare "ni ki o dẹhin o; o ti i mọ ìgbanà rí? tabi o ti i ba wọn lọ "s'ikomọ rí?' bẹeni Edu ìbaaraa pada sẹhin.

"Àgbọnrin gbọ o ni on yio ba wọn ṣilẹkun; bẹli Ọrunmla "dahun wipe 'Lèsì nkàn 'kùn Ọṣin kàkàkà 'lèsí nkàn 'kùn "Ọṣìn lelele?' O dahun o ni 'emi Àgbọnrin òdogija onílà "afifẹn.'

"Ṣugbọn Ọrunmla dahun si i pe 'Agbọnrín òdogija, "Olodumare ní ki o dẹhin o; o ti i mọ igbanaa rí? tabi o ti i "ba wọn lọ s'ikomọ rí?' bẹeni Àgbọnrin òdogija pada sẹhin.

"Irá gbọ, o ní on nlọ ba wọn ṣilèkun; bẹeli Ọrunmla "beere wipe 'lèsí nkàn 'kún Ọṣìn kàkàkà, lèsí nkan 'kùn Ọṣìn "lelele?' O dahùn o ni 'emi Irá oniiwo kanṣoṣo ni.'

"Ṣugbọn Ọrunmla dahun si i pe 'Irá oniiwo kanṣoṣo, "Olodumare ní ki o dẹhin o; o ti i mọ igbanaa rí? tabi o ti i bá wọn lọ si ikomọ ri? bẹeni Irá oniwo kanṣoṣo pada sẹhin.

"Ariwo ta lode ọrun pe 'tani yio ha bá-ni sílèkun Ọṣìn?'

"Nigbanaa ni Ẹdun gbọ, o jade wá o ni on yio bá wọn de "ibẹ wò; o lọ if'ọwọ le ilẹkun, o si gbọ Ọrunmla mbeere wipe " 'lèsí nkàn 'kun Ọṣìn kàkàkà, lèsí nkàn 'kùn Ọṣìn lelele?" O "dahun o ní "Emi Ẹdun mà ni ò!"

"Ṣugbọn Ọrunmla dahun si i pe 'Iwọ Ẹdun ol'oju "fòkífokí, Iwọ Ẹdun ọl'ọwọ pọjọpọjọ, dẹhin o; mọ igbanaa, "tabi o bá wọn yún 'bẹ rí?'

"Ẹdun dahun o ní

" 'Oju mi meji fòkífòkí yi
" Mo fi kà ìbò f'Ọlọfin jẹ;
" Ọwọ mi meji pọjọpọjọ yi
" Mo fi kà ìbò f' Ọlọfin jẹ'.

"Orunmla dahun o ni

" 'Haa! O tó, Edun ol'owo pojo, Edun elesè pojo;
" Edun ol'oju fòki, maa tún rora:
" Itan ti o pa sile mà to ò!'

"Nigbanaa ni Edun silekun wole ikomo, ó m'ekún
" s'ekún igbe, ó m'ohún s'ohùn iyèrè, o nse.
" 'Ogiján, Edun mà mbá won to rè;
" Ogiján, Edun mba won lo.' "*

(2). Orunmlà je Eleri-ìpín nitori on ni Olodumare fi
" je Orí fun gbogbo awon irúnmalè ati oba, li aiye ati
" li orun.—

**9** "Bi a bá dupe oore àná à gba omiràn: a dá a f'Ori*
"nlo si awujo gbogbo irúnmale lo ip'obì ooré."—Ejiogbe.

**10.** "Sèsé-ooloogoo–sèsé adifa f' Orunmla nlo ba
"gbogbo oloja inu aiye jìjakaadì.* O mú Al'Ara o dá a,
"o kó gbogbo erù rè; o d'Ajerò o kó gbogbo erù rè: o

---

*Ifa ti a ki nihin je apa ikehin ese kan ninu Ejiogbe, o si se okan ninu awon ese ti o li eru julo fun babalawo lati ki. Agbara ni mo fi mu babalawo mi ki i fun mi: sibe, eru ba a tobee ti o fi mu mi lo si ikoko kan, ti o si mu enu sunmo eti mi nki i kélékelé!

*Itan yi wi siwaju pe Olodumare ji, O mu obi ooré (e.n. obi olori tabi alase) sile: o ni on nfe eniti yio ba on pa a ninu gbogbo awon Irunmalè. Ogun dè o pa a ti, o joko sibe; gbogbo irunmale dè lokookan nwon pa obi ooré ti, nwon si joko sibe nleri dè eniti yio wa ipa obi ti awon pa ti. Nikehin ni nwon ri ti Ori yo si won o nyi bowa gbirigbiri, o dè o mu obi naa kan, o pa a, ariwo ta: Olodumare ni 'Ori, iwo naa li o to obi ooré ipa looto.' Beeni gbogbo irunmalè beresi iba Ori jowu ipo ola yi. Nwon si su-mo o lati ba a ja, sugbon ko si eniti o da Ori ninu gbogbo irunmale, Ori l'o da gbogbo won l'okookan. O da Olota si'le Ado, o da Erinmi s'ode Owo, o da Peepee s'ode Àsin; o da Orisa s'Itapa, o da Ogun s'Ile-Ire, o da Obalufon si Iyinde: o da Orunmla s'Ile-Ifè.

*Nigbati Ewi ti gburo isegun Oruunmla, o sa to awon awo lo igbo ohun ti on le se ki Oruunmla ma le da on; a ni ki o ru owuuru eku, owuuru eja, pelu igo oti kan. Ewi gbo o o ru gbogbo nkan naa. Bi Oruunmla ti gbè ija de aafin, Ewi jade si i, o yara ko gbogbo eku ati eja wonni ti i li aiya, o si gbè igo oti naa fun u mu. Orunmla je o mu yo tan, oti gbe e sanlè: beeli Ewi se da Orunmla, ti o si ko gbogbo eru awon oloja-loja ti Orunmla ti da. Àyaani a nwipe 'Ko si oba bi Ewi'. Àyaani Orunmla ni bi a ba da on, ki a si maa ko on!

"dá gbogbo ọloja-'lọja inu aiye o kó gbogbo ẹru wọn tán o "wá mu orí le ile Ẹwí". —Osé meji.

(3). Ọrunmla jẹ Ẹlẹri-ìpín nitori on li ó gbé ẹrù kìkì orí nijọ ti awọn irunmalẹ̀ ndù ẹrù ọrọ gbé li ọrun.

**11.** "Ẹwọn-ba'lẹ̀-ró-wọrọjọ adifa f'Ọrunmla a bù fun "gbogbo irunmalẹ̀, Olodumare d'ẹrù ka'lẹ̀ O ranṣẹ *pe gbogbo "wọn ki nwọn wá ígbe e lọ sinu aiye."— Ọkanran-ègútan.

Akiyesi.—Awọn ẹsẹ-ifá nwọnyi ati ìtan wọn ti a kà nihin fihan dajudaju pe ọkan awọn baba-nla wa njẹ wọn lẹri pe Ẹnikanṣoṣo ni mbẹ lẹhin Ọlọrun Olodumare ti ó le mọ ìpín ohun gbogbo li ayie ati li ọrun; ati pe nipa imọ yi, Ẹnikanṣoṣo naa ni iṣe Ori fun ohun gbogbo.

---

*Ikọ Olodumare de ọdọ gbogbo irunmalẹ̀, ko si ẹnikan ninu wọn ti o ni i lohun; o de ọdọ Ọrunmla, Ọrunmla fun u ni itan adiẹ kan ati ọpọ onjẹ. Nitori oore yi, ikọ naa ṣofofo fun Ọrunmla pe ki o mase kanju gbe ẹru nitori "isẹ gbogbo mbẹ ninu karahun li akata Olodumare." Esẹ gbogbo irunmalẹ pe, nwọn ndu eru gbé niwaju Olodumare, eyi ngbe ẹru owo, eyi ngbé ẹru asọ; sugbọn ikọ Olodumare nfi fere wi tantan fun Ọrunmla bayi pe:— "Ọruunmla, ma sẹdọ joko o! ori mbẹ ninu aaihun." Bayi ni Ọrunmla sẹdọ joko nwo gbogbo irunmalẹ̀ titi nwọn fi ko gbogbo ọrọ kọja lọ sinu aiye. Ọrunmla dide nigbati awọn irunmalẹ lọ tan, o rin lọ gaara si akata Olodumare, o si mu aaihun (karahun) naa jade ti ibẹ wa, o mu ọna Ile Aiye pọn. Ọrunmla ba gbogbo irunmalẹ nwọn tidi si ati-jade si aiye, o bi wọn eetiri, a ni omi bo gbogbo oju aiye, ko si ilẹ nibikibi lati ti ọrun bọ si.

Nigbana ni Ọruunmla tọwọbọ inu karahun rẹ yi, o mu awọn kan ti inu rẹ jade, o si sọ ọ le oju omi; o tun tọwọbọ ibẹ naa, o bu ikunwọ kan erupẹ da sori awọn naa; o tọwọbọ ọ nigba kẹta o mu adiẹ kan oniigan marun jade, o si sọ ọ le ori awọn naa pẹlu. Adiẹ yi bẹrẹsi erupẹ die naa itan, bi o si ti ntan a, bẹni omi nsa sẹhin ti ilẹ si mgbaye.

Ọruunmla ti o da ilẹ li o kọ bọ sori ilẹ; on ko si jẹ ki awọn irunmalẹ wọnni bọ sori ilẹ titi nwọn fi ko gbogbo ẹru ọrọ ti nwọn ru ti ọrun wa le e lọwọ. Iyekiye ti o si to loju Ọrunmla ni on nfifun wọn pada; gbogbo irunmalẹ si tumba fun u patapata. Ọrunmla si nkọrin bayi wipe

"Aiye ma nwa
Iwa l' iwa o, Iwa l'ehin, Iwa!"

Awọn otitọ naa niye lori jọjọ ninu ìpilẹ ìsin ti a ba lọwọ awọn baba-nla wa (ka iwe 'kini, ewe 16–17); nitori nwọn nfihan pe awọn keferi ilẹ wa ti ni imọ wíwa Jesu Kristi. A o mú awọn ohun akiyesi meji naa wá s'ẹgbẹ ọrọ Iwe Mimọ Ọlọrun fun ifiwé ki a ba le ri ọna ti a lè maa lò wọn lati bá awọn keferi ilẹ wa sọ asọyé nipa ti Kristi.

(*a*). Ẹnikanṣoṣo ni mbẹ lẹhin Ọlọrun Olodumare ti o le mọ ìpín ohun gbogbo li aiye ati li ọrun.

(*b*). Ẹnikanṣoṣo naa yi ni Ori fun ohun gbogbo.

Job. *xxxviii*. 4–11. "Nibo ni iwọ wà nigbati mo fi ipilẹ aiye sọlẹ? Wi bi iwọ ba moye! Tali o fi iwọn rẹ lelẹ, bi iwọ ba mọ, tabi tali o ta okùn wiwọn sori rẹ? Lori ibo ni a gbe kan ipilẹ rẹ mọ, tabi tali o fi okuta igun rẹ lé ilẹ? Nigbati awọn irawọ owurọ jùmọ kọrin pọ ti gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun nho ihò ayọ? Tabi tali o fi ilẹkun sé omi okun mọ, nigbati o ya jade bi ẹnipe o ti inu tú jade wá? Nigbati mo fi awọ-sanmà ṣe asọ rẹ, ati òkunkun ṣiṣu ṣe ọja igbanú rẹ? Ti mo ti paṣẹ ipinnu mi fun u, ti mo si ṣe bèbe ati ilẹkun. Ti mo si wipe: nihinyi ni iwọ yio dé, ki o ma si rekọja, nihinyi si ni igberaga riru omi rẹ yio gbe duro mọ".

Jobu kò le dahun gbogbo ọrọ-ìmọ wọnyi ti Ọlọrun bi i leere ninu orí 38 dé 41. Mo si le sọ pe kò si ninu araiye ti o ti i fọwọsọiya pe on le dahun wọn bikoṣe Ẹnikanṣoṣo naa ti iṣe Ọgbọn Ọlọrun. Ka ẹsẹ wọnyi:—

Owe v*iii*. 22–30. "Oluwa pese mi ni ipilẹṣẹ iwa rẹ, ṣaju iṣẹ rẹ atijọ. A ti yàn mi lati aiyeraiye, lati ipilẹṣẹ tabi ki ilẹ aiye ki o to wà. Nigbati ọgbun kò si, a ti bi mi; nigbati ko si orisun ti o kún omi pipọ. Ki a to fi idi awọn oke nla sọlẹ, ṣaaju awọn oke li a ti bi mi: Nigbati ko ti ida ilẹ aiye, tabi pẹtẹlẹ, tabi ori erupẹ aiye. Nigbati o nṣe ipilẹ awọn ọrun,

emi wa nibẹ: nigbati o fi ọsuwọn ayika le oju ọgbun. Nigbati o sọ awọsanmà lọjọ soke: nigbati o fi agbara fun orisun ibú. Nigbati o fi aṣẹ rẹ fun okun, ki omi rè ki o maṣe kọja ẹnu rẹ: ati ofin rẹ fun ipilẹ aiye. Nigbana emi wa lọdọ rẹ bi oniṣẹ: emi si jẹ didùn inu rẹ lojoojumọ, emi nyọ nigbagbogbo niwaju rẹ."

Tani ha li ẹni naa ti o fọwọsọiya bayi bikoṣe "Kristi" Ẹniti a pè ni "agbara Ọlọrun ati ọgbọn Ọlọrun" i Kor. i,24.

Eyi naa gaan li awọn keferi ilẹ wa mpè ni Ọrunmla. Ṣugbọn Kristi naa ti iṣe ọgbọn Ọlọrun ni Ori fun ohun gbogbo.

Efes. i. 22. "O si ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ, o si ti fifun u lati jẹ ori lori ohun gbogbo fun ijọ enia Ọlọrun.– iv. 15. Ki a le maa dagba soke ninu rẹ li ohun gbogbo, ẹniti iṣe Ori, ani Kristi."

Ati Kristi naa yi ti iṣe Ori fun ohun gbogbo li Ọlọrun fi ṣe Ẹni àpésìn aiye ati ọrun:—

1 Kor. xi, 3. "Ṣugbọn mo fẹ ki ẹnyin ki o mọ pe, Kristi li ori olukuluku ọkọnrin; ori obirin si li ọkọ rẹ; ati ori Kristi si li Ọlọrun." Filip. *ii.* 10–11. "Pe li orukọ Jesu ni ki gbogbo eekun ki o maa kúnlẹ̀, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ̀, ati awọn ẹniti mbẹ nisalẹ ilẹ; ati pe ki gbogbo ahọn ki o maa jẹwọ pe Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba." Heb. *i.* 6. "Ati pẹlu nigbati o mu akọbi ni wa si aiye, o ní, Ki gbogbo angeli Ọlọrun ki o si maa foribalẹ̀ fun u" Or. Daf. *xcvii.* 7. "Oju yio ti gbogbo awọn ti nsin ere fifin ẹniti nfi ere ṣe ileri ara wọn: ẹ maa sin i, gbogbo ẹnyin ọlọrun."

Ọna wo ni Ọrunmla fi jẹ Ibikeji Olodumare? Awọn babalawo fi idahun si ibeere yi latinu odu–ifá gẹgẹ bi eyiti a kọ si isalẹ nihin:

(1). Ọrunmla jẹ̀ Ibikeji Olodumare nitori On ati Olodumare li o jùmọ bẹrẹ iwa nigbati nwọn ko tilẹ ti i ni ohunkohun miran ju ohun – Iwa – Ọlọrun.

**12.** "Ojú mpọn Olodumare, ojú mpọn Ọrunmla: "Olodumare ni ki Ọrunmla rubọ; Ọrunmla ni ki Olodumare "naa rubọ kẹ̀. Nwọn jumọ yan aṣobiliki ẹranla kọọkan "ati ọgbọọgbọkanla li ẹbọ fun ara-wọn. Awọn mejeeji gbọ ẹbọ nwọn rubọ."—Ejiogbe.**

(2). Ọrunmla jẹ̀ Ibikeji Olodumare nitori lẹhin Olodumare, On nikanṣoṣo li o kù ti o tún kàpa Eṣu.—

**13.** "Ẹni burukú nsalọ kuro loju Olodumare, Olodumare "kẹ́-lẹ́ e wipe 'Ẹ mú u!' Ẹni buruku tẹsẹ̀ mọ 'rìn nlọ, "bẹẹli a ko ri ẹnit' o le mú u silẹ ninu gbogbo irúnmalẹ̀ t'o "pejọ s'iwà ọrun.

" Ẹni buruku là wọn kọja patapata tan ó wa kàn Ọrunmla, Ọrunmla mú u ṣikun o fa a pada lọ fun Olodumare, Olodu-"mare gbe e s'ẹẹwọn.

" Ayaani oo ri i Olodumare wipe kí Ọrunmla joko ti On: "O ní 'Iwọ Ọrunmlà nikanṣoṣo ni ki o maa rí mi fín ninu "gbogbo irúnmalẹ̀.' "—Ejiogbe.

Akiyesi.—Awọn ẹsẹ-ifa nwọnyi ati ìtan wọn ti a kà nihin fihan pe wíwà-ṣiwaju-ohun-gbogbo jẹ̀ èro pataki kan ti nwọn ní si Ọlọrun: ati pe wíwa ohunkohun miran lẹhin

---

*Eyi ni apa ẹsẹ-ifa ti a ki ni ẹsẹ'kẹjọ iwe yi: o si jẹ ọkan ninu awọn ẹsẹ ti o li ẹru julọ fun babalawo lati ki.

Itan abami yi wi siwaju pe nigbati Olodumare ati Ọrunmla rubọ yi tan, bi nwọn ti jumọ nrin lọ, nwọn jin sinu ọfin nla kan; nwọn si wa ninu ọpọlọpọ ebi nibẹ fun ọjọ pipẹ tobẹẹ ti nwọn ko fi le jade mọ. Ni alabapade ni Ẹdun wa iba wọn ninu ipọnju nla yi, o ni "Haa!" o yara nlọ iwa eso igi gbogbo ka wa ifun wọn je nibe titi oju wọn fi walẹ, ti imi fi ko wọn diẹ lati goke. Nigbati nwọn goke tan, sibẹsibẹ nitoriti ara wọn koi tii padabọ sipo tan, nwọn lọ iti ara-wọn mọ odi ti a mpe ni Odi Ikomọ li ode ọrun.

Iyoku itan yi li a ti sọ saaju ninu ẹsẹ 'kẹjọ ti iwe yi.

Àsiri nla yi ti Ẹdun nikan mọ li o fi ni igboiya lati ṣilẹkun wọle ikomọ Ọrunmla ati Olodumare lọtọ (wo ẹsẹ 'kẹjọ).

Ọlọrun nà Ọlọrun li ẹbọ kan; ati pe ní riru ẹbọ nla yi, ọgbọgba ni ìnàwo rẹ̀ fun Olodumare ati Ọrunmla: ati pe kò sí ẹnikan tí o kapa Èṣu bikoṣe Ẹniti o bà Ọlọrun dọgba.

Awọn otitọ nwọnyi níye lori jọjọ ninu ipilẹ̀ ìsin ti a bà lọwọ awọn baba–nla wa: e.n. pe nwọn ya Ọlọrun Olodumare tikalarẹ̀ ati ohun–ìwa Rẹ̀ kuro lara ohunkohun ti iṣe ohun–èlo–ìpilẹ–ẹ̀dá, nwọn si ya Ọrunmla ati ohun -iwa rẹ̀ bakanna kuro lara ohunkohun ti iṣe ohun–elo–ipilẹ–ẹ̀dá.

Bi a bà mu awọn ohun akiyesi wọnyi wà si ẹgbẹ̀ ọrọ Iwe Mimọ Ọlọrun fun ifiwe, a oo ri ọna ti a le maa lò wọn lati bà awọn keferi ilẹ wa sọ asọye nipa ti Kristi.

(a). Wíwà Ọlọrun ṣiwaju ohun gbogbo jẹ èro pataki kan ti o yẹ ki a ni si Ẹniti a pe ni Olodumare.

Or. Daf. 90. 2. "Ki a to bi awọn òke nla, ati ki iwọ ki o to dà ilẹ on aiye, ani lati aiyeraiye, iwọ li Ọlọrun.

Job. *xxxvi.* 26. "Kiyesi i, Ọlọrun tobi, awa kò si mọ bi o ti tobi to! bẹẹni a ko le iwadi iye ọdun rẹ̀ ri."

Rom. *xi.* 36. "Nitori lati ọdọ rẹ̀, nipa rẹ̀, ati fun u li ohun gbogbo."

Heb. *iii.* 4. "Lati ọwọ enia kan li a sa ti kọ olukuluku ile; ṣugbọn ẹniti o kọ ohun gbogbo ni Ọlọrun."

Ifi. *i.* 8. "Emi ni Alfa ati Omega, ipilẹṣẹ ati opin, ẹniti o mbẹ, ti o ti wà, ti o si mbọwa, Olodumare. *iv.* 11 Oluwa, iwọ li o yẹ lati gba ogo ati ọla ati agbara: nitoripe iwọ li o dà ohun gbogbo, ati nitori wiwù rẹ ni nwọn fi wà ti a si ṣe dà wọn.

Ero wíwà Ọlọrun ṣiwaju ohun gbogbo li o mu awọn baba–nla wa kàn akoko kan ti oju mpọn Olodumare ti o si mpọn Ibikeji Rẹ̀ pelu; e.n. pe akoko kan tí Olodumare ati Ibikeji Rẹ̀ ti wà li aitii dà ẹdakẹda kan, ani nigbati a kòi tii dà nkan naa tikalarẹ̀ ti iṣe ohun–èlo-ìpilẹ-ẹ̀dá.

Niti Ọlọrun, gbogbo ẹ̀dá li o ti hàn fun Ọlọrun lati gbogbo aiyeraiye biẹnipe a ti dá wọn; ṣugbọn niti awa enia, a ko le ri tabi ki a ní ohun ti kòi tii si. Ohun ijinlẹ nlanla si ni ero yi li ọkan awọn babalawo ti o ba gbọ 'fá de ibẹ ni ilẹ wa; nitori nigbati a tún fi ibeere yi fun wọn pe "Tali ẹniti o kọ wà pàto ninu Olodumare ati Ọrunmla?" nwọn dahun pe "Kò si ẹniti o mọ ẹniti o kọ wà ninu wọn nitori 'Li ọjọ ti a ti mú oko li a ti mú àgbè.' "*

Ẹniti o ba rò idahun kekere yi wò yio rí ìjinlẹ ẹ̀ro ti awọn baba-nla wa fifun ohun-iwa Olodumare ati Ibikeji Rẹ̀.

(b). Wíwà ohun-kohun miran lẹhin Ọlọrun ná Olodumare li ẹbọ kan.

(d). Ní ríru ẹbọ nla yi, ọgbọọgba ni inàwo rẹ̀ fun Olodumare ati Ibikeji Rẹ̀.

Isin otitọ, e.n. ojú ìbọ ati ọna mgbà-bọ ti o ṣe itẹwọgba lọdọ Ọlọrun Olodumare jẹ ilana a-t'ọwọ Ontikalarẹ wá: ati bi kò ti si isin kan ti o pé-ye lainí ẹbọ ati irubọ, o daju pe araiye kò le tikarawọn ronu kan ẹbọ ati irubọ laisi ifihàn at'ọwọ Ọlọrun wá. Nigbati a ba si rò o pé bikoṣe Ọlọrun Olodumare ba tẹwọgba ẹbọ ti mbẹ ninu isin kan, isin naa ko le igbè olùsin, yio wa idaniloju pe ẹbọ ni kókó ati ẹmi isin.

Kí ha li ebọ? Ebọ ni nínà ara-ẹni tabi ohun ti o dípò ara-ẹni fun ati-mú anfaani bá ara-ẹni tabi ẹlomiran; eyi ni owurọ ẹbọ.

Ero yi gaan ni awọn keferi ilẹ wa ní sípa ẹbọ nigbati nwọn nwipe 'Olodumare rubọ' tabi 'Ọrunmla rubọ' e.n. pe nwọn ná ara wọn jade ki nwọn ba le ní ohun gbogbo wọnyi ti a rí ati ti a ko ri. Pataki kan li o si jẹ ninu igbagbọ wọn pe ohun

---

*Ki akawẹ yi ro o jinlẹ:— "Ewo li o kọ wa? ilẹ oko ti a ṣan, tabi ẹba oko naa?" Iwọ yio si ri pe lẹṣẹkannaa ti a ti bẹrẹsi ṣisan oko, lesẹkannaa ni agbẹ rẹ iti ihan pẹlu rẹ̀.

gbogbo ti a rí ati ti a kò ri (e.n. gbogbo ẹdá), ní ati ìbẹrẹ ati aarin ati opin wíwà wọn latinú ati nipasẹ ẹbọ ti Olodumare ati Ọrunmlà rú li owurọ ìwa. Njẹ eyi mu ki a rí ipò nlanla ti nwọn fifun Ọrunmla niti pe ki o jẹ ẹnikanṣoṣo naa ti t'on t'Olodumare jumọ rubọ gbogbo ẹdá.

(e) Ko si ẹnikan ti o kápa Eṣu bikoṣe Ẹniti ọ bá Olodumare dọgba ninu ohun gbogbo.

Lotitọ ni awọn enia ilẹ wa npe Eṣu ni Ẹlẹgbara, sibẹ nwọn njẹwọ ninu isin wọn pe Olodumare ati Ibikeji Rẹ lagbara ju Eṣu lọ fiiri. Nigbati a si bi wọn leerè pe "Eetiṣe ti ẹ fi mbọ Eṣu to bayi nigbati ẹ mọ ọ lí ẹni buruku?" idahun tí awọn babalawo fifun ìbeere yi ni wọnyi pe,—

"Ọlọrun li o dá Eṣu, ti O si fi i jẹ oye alagbara sọdọ ara-Rẹ lọhun. Nigbati Ọlọrun si mọ pe Eṣu kò tún sàn mọ, On kannaa li o lé e wá sinu aiye. Agbara Ọlọrun tobi ju ti Eṣu lọ fiiri, ṣugbọn bẹẹ gẹgẹ ni agbara Eṣu si tobi jù ti awa ọmọ araiye lọ. Idá ti Ọlọrun ti dá Eṣu lati ọhún wá ni kò ṣe ípa-dà lọwọ awa ọmọ araiye li o jẹ ki a kúkú maa bẹ ẹ kí o ma baa fi buburu rẹ ṣe wa. Ẹnyin kò gbọ bi owe wa kan ti wí pe 'Bí kò rọọ-nii l' apa baba, a rọọ-nii l'apa iya'? Ọrun lọọhún kò san Eṣu, sísàn li aiye wá ísàn jù ọrun lọ nì."

Ero yi níye lori jọjọ niwọnbi o ti tọka si ọna pàtaki ti a bá maa lo ìyanju wa sí laarin awọn keferi ilẹ wa lati mú wọn mọ daju pe Ọlọrun kò le Eṣu bọ si aiye lati maa pá araiye li aiya nikan, ṣugbọn O si ti ran Ẹnikan tí o le kápá Eṣu wá sinu aiye pẹlu lati jẹ Ọgagun igbala araiye: ani Ẹni naa Jesu Kristi Olugbala.

Luk. xi 21–22. "Nigbati ọkọnrin alagbara ti o hamọra ba nṣọ aafin rẹ, ẹrù rẹ a wà li alaafia: Ṣugbọn nigbati ọkọnrin alagbara jù u ba kọlu u, ti o si ṣẹgun rẹ, o gba gbogbo ihamọra rẹ ti o gbẹkẹle lọwọ rẹ, a si pin ikogun rẹ."

i Tessa, v. 8–10. "Ṣugbọn ẹ jẹki awa ti iṣe ti ọsán, ki a ma wa li airekọja, ki a maa gbe awo-aiya igbagbọ ati ti ifẹ wọ; ati fun aṣibori irin, ireti igbala. Nitoripe Ọlọrun kò yàn wa fun ibinu, bikoṣe lati ní igbala nipa Jesu Kristi Oluwa wa. Ẹniti o kú fun wa, pe bi awa jí tabi bi awa sùn, ki a le jumọ wà laaye pẹlu rẹ̀."

Heb. II. 14–15. "Njẹ niwọn bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara on ẹjẹ, on tikararẹ̀ pẹlu si mu ipa ninu rẹ naa; pe nipa iku ki o le pa ẹniti o ni agbara iku run, eyini ni Eṣu; O si yọ awọn, nipa ibẹru iku, ti mbẹ labẹ ide li ọjọ aiye wọn gbogbo."

i John. ii. 8. "Ẹnikẹni ti o ba dẹṣẹ ti Eṣu ni; nitoriti Eṣu ti ṣẹ̀ lati igba àtetekọṣe. Nitori idi eyi li Ọmọ Ọlọrun farahàn ki o le pa iṣẹ ti Eṣu run."

# ORI III

"Oluwa mi Àmọimọtán!
A kò mọ Ọ tán kò ṣe,
À bá mọ Ọ tán ìbá ṣe kè."

Edè yi 'Oluwa mi' ninu ìsin jẹ eyiti awọn keferi a maa lò ní ìbọla fun òriṣa wọn. Ninu ìsọrọ lasan, a mọ bi lilò ède naa yi ti wọọpọ to ni ilẹ wa. Aya a maa lo o ni ìbọla fun ọkọ rè, ẹrú a maa lò o ni ìbọla fun olówo rè, awọn enia ilu a maa lo o ni ibọla fun ọba wọn: ṣugbọn gbogbo enia ninu isin ni ímaa lò o ni ìbọla fun oriṣa wọn. Ṣugbọn ìlo rè nihin li ẹnu babalawo ninu adura ati ìsin rẹ miran si Ọrunmlà ati Olodumare jẹ ìbọla ati ìbọwọ fun awọn mejeeji na ni iru òṣuwọn ti o rekọja eyikeyi ti aya lò fun ọkọ rẹ, tabi ẹru fun olowo rẹ, tabi ọlọtọ ilu fun ọba rè. Oṣuwon naa tilẹ rekọja eyiti awọn ẹlomiran fi ímaa bu ọlá ati ọwọ fun awọn oriṣa ti nwọn mbọ lẹhin Ọrunmlà. Enikẹni ti o ba si fọkànbalẹ ro ipo ti awọn babalawo to Ọrunmla si li ẹgbẹ Olodumare yio mọ iru ífọkansin ti nwọn fi ímaa pè e li 'Oluwa'. O mú-ni ranti ọrọ wọnyi ti mbẹ ninu I Kor. viii. 5–6 "Nitoripe bi nwọn tilẹ wà ti a mpè li Ọlọrun, iba ṣe li ọrun tabi li aiye, (gẹgẹ bi ọpọ ọlọrun ti wà, ati ọpọ oluwa), ṣugbọn fun wa Ọlọrun kan li o wà, Baba, lọwọ ẹniti ohun gbogbo ti wá, ati ti ẹniti gbogbo wa iṣe; ati Oluwa kanṣoṣo Jesu Kristi, nipasẹ ẹniti ohun gbogbo ti wa, ati awa nipasẹ rè."

"Amọimọtan!"

Awọn babalawo nlo ede yi si ọna meji pataki:

(1). Lati sọ bi ẹnikan ko ti le riidí Ọrunmla biotiwù ki o wá a tó ninu ohun ìwa–Ọlọrun rè ati ohun iwa-enia rè. Gẹgẹ bi mo ti wi ṣiwaju, o ba babalawo leru jọjọ lati maa sọ itan tabi ki ifá kan ibi ijinle idi Ọrunmla. Fun ọpọ ọsù ti mo mbé babalawo mi lati sọ ijinle wọnyi fun mi, kiki èsi ti o nfun mi ni pe "Tani le riidi agbado lorun?" Ẹru nla mba a pe ko si ohun ti ko le ba on fun siso ti on ba sọ idi Ọrunmla fun mi. O le pa on, o si le sọ on di iánnaaiánnaa. Bi iru ẹru nla bayi ti ṣe mba wọn yio farahan ninu awọn ẹse–ifa átẹlé wọnyi.

**14.** "Afẹẹfẹ ṣori igi hẹrẹhẹrẹ, ẹfufulẹlẹ ni it' ewe agbọn "nìkọọrọọ, adifa f'Ọrunmla* gbogbo irunmalẹ nk'osiiri mọ "ọ, nwọn nwalẹ lati ode wa iyọ si idi iporún rẹ ninu yaara "Ọrunmla." — Irosu'Sá.

**15.** "Kàkàkà l'awo kàmiikà, kàkàkà l'awo kàmiikà; adifa f'Ọrunmla *nijọ t'Oriṣa yio ṣ'oro silẹ de e nidi iṣin."– Ogbè 'Kà.

**16.** "Oyígí l'awo Oyígí, Oyígí l'awo Oyígí, ati–dide l'à "ímọ agba Ilẹṣì';*–adifa f'Ọsanyin * nlọ b'Ọrunmla lèri pe ko

---

*Ọrunmla ko tete mọ ọtẹ ti a ndi mọ ọ yi, bikose bi ojumọ ti mọ ti o fi obukọ kan rubọ, o ni ki on wa ilẹ lati ri ori obukọ naa sidi iporun on; o jiin ewuru. Ọrunmla yara gbé igba iporun rè kuro nibẹ laimọpe gbogbo awọn irunmalẹ li o ti wọ kun inu iho naa ti nwọn ngbé. Ọrunmla rubọ tan gẹẹ ni ojo nla kan rọ arọṣulẹ, o si wọ agbara nlanla lọ ipa gbogbo irunmalẹ mọnu ọfin ti awọn tikalawọn ngbẹ lati lọ fi ridi Ọrunmla.

*Awọn ọmọ ile Ọrunmla ati Oriṣa a maa jumọ du eso iṣin ka. Nijọ kan Orisa nfẹ ise Ọrunmla ni ika o lọ ifi oro si idi igi na, o sọ fun awọn ọmọ tirẹ pe ki nwọn mase lọ sibẹ loni o. Ọrunmla ko gbọ ' kan, ojumọ mọ o da iporun rẹ wo a ri Ogbe-' Ka, o ni ki awọn ọmọ on jọwọ mase lọ ka iṣin loni o. Awọn ọmọ Ọrunmla gbọ, awọn t'Orisa ko gbọ oro mu wọn. Nigbati Orisa lọ ba oku wọn nidi iṣin, o ni "E! mo s'oro silẹ de'ra mi!"

*e.n. Ṣiṣi ti awọn Ọyọmisi imaa ṣi wii lẹẹkannaa kuro li apejọ aafin Ọbalọyọ.

"s'ẹnit' o le yan on m'ẹbọ."—Okanran–Túrúpọn.

17. "Ọrunmla ní "Ajambète,' mo ni 'Ajambète'; o ni 'mèsewà l'apá eku íké, mèsewà l'apá ẹiyẹ íké:– a dá a fun gbogbo igi oko * nijọ nwọn nkó èse lọ ọrun ti Ọrunmla yio maa sánrí tọ wọn lẹhin." – Irosu-'Sá.

18. "Bi t'ẹni yo ba siàn, araiye ki ílè bà a jé:– a dá a "f'Ọrunmla *nijọ ti yio b'Ẹsu sòwo po ti Ẹsu ni on yio maa ba "tirẹ jẹ." – Ọwọnrin meji.

19. "Nigba aiye Ifè fọ bi igbá, a ranṣẹ si Ọlọta n'Ile "Ado ki o wá tún aiye Ifè sọ bi igbá, o dé o ṣe e o ṣe e tì. A "ranṣẹ s'Erinmi lode Ọwọ, ó dé o ṣe e ṣe e o ti. A ranṣẹ si "Pẹẹpẹẹ lode Asiin, o dé o ṣe e o ṣe e tí. A ranṣẹ si Ogun lode

---

16 *Ọsanyin mpegan Ọrunmla nijọ kan ni Ọrunmla sọ fun u pe bi o ti gbọn ti o mọ esan-mesan to ni, sibè on Ọrunmla le yan a mọ ẹbọ. Ọsanyin jiyan pe ko si ọkunrin bẹẹ laiye. Awọn mejeeji si tile pe ẹniti tire ba sẹ ni ki o maa je agba fun ẹnikeji rẹ. Ojumọ mọ nijọ keji a pè Ọrunmla wa iwo 'fa f'Ọlọfin, a ko ri ohun meji a ri Okanran-' Turupọn: Ọrunmla ni a o ru ẹru iṣẹpẹ igi kan wọle Ọlọfin loni, on dandan l'ẹbọ. Ọlọfin rẹrin ẹlẹya, o ni 'eewọ ni, a koi tii ru isẹpẹ igi wọle Ọlọfin ri'. Ọrunmla ni njẹ ki a yan olusọ si gbogbo ọna abawọle Ọlọfin. A se bẹẹ. Ṣamọ-samọ ọkan ninu awọn olori Ọlọfin ti a se li ẹlẹeha lati wundia, ti ọba ko de ọdọ rẹ ri titi o fi di arugbo. Ii o yọ jade kuro li aafin nlọ p'okun sọ ninu igbẹ. O ri Ọsanyin ntu isẹpẹ igi o si sọ isẹ ara-rẹ fun Ọsanyin. Ọsanyin ni bi ọkan rẹ gba a on le ba a se: olori fi ayọ nla gba. Nwọn setan ni Ọsanyin dupe o pẹhinda nlọ, bẹeni olori yi gba a mu o ni nibo ni o nlọ? Afi bi yio ba on kalọ si aafin ki on lọ fi i pamọ sinu yaara on. Ọsanyin ke wipe on gbe, a iti irin de yaara olori ọba? Olori ni ki o saa wa bọ saarin awọn isẹpẹ igi wọnyi ki on di i mọ ọ. Ọsanyin se bẹẹ. Bi a ti ngbe ẹru isẹpẹ igi yi wọle ni awọn olusọna gba a, nwọn si gbe e lọ gbọọnran sọdọ Ọlọfin. Enu ya Ọlọfin tobẹẹ ti ko fi le duro wadi ọna ti isẹpè iti gba wọle on, o yara bọ si yaara lọ mu ẹbun ati ẹjẹ wa fun Ọrunmla. Ki Ọlọfin to ipada de ijoko ni Ọsanyin ti nwi kẹlẹkẹlẹ fun Ọrunmla lati aarin ẹru isẹpẹ igi wipe

"Ọrunmla! jọwọ pa mi sile, ma pa mi sode:
jọwọ fi mi s'ẹru je, mo d'ẹru rẹ."

Nigbati Ọlọfin pada de, o ko ohun ẹbọ silẹ patapata, Ọrunmla sẹ ẹẹrun die ninu igi naa lati fi tubọ, o si pasẹ ki a ru iyoku ba on kalọ ile. Nwọn de ile tan ni Ọsanyin wa bọ sile, o nforibale niwaju Ọrunmla o ndọbale, o nwipe titi lailai on ki yio ye iiuba Ọrunmla.

"Ire, ó dé o ṣe e o ṣe e tì. A ranṣẹ si Dàwodéri awo Imọjùbí, ó "dé o ṣe e o ṣe e tí. A wa íranṣẹ si A-ti-kekere-ṣ'ọgbọn ki ó wá "tun aiye Ifẹ ṣọ bi igbá; ó dé, o ni ki nwọn o lọ wá ewe-"olúṣùwàlù wá, nwọn wá a nwọn kò rí i, nwọn ní "awa kò mà "rí ewe oluṣùwàlù o!" O ni "bi ẹnyin kò bá rí ewe olúṣùwàlù "ẹ jẹwọ obùn ki a dáṣọ bo nyin." Nwọn ní "awa jẹwọ ọbun "dáṣọ bò wa." O si ṣí fila rẹ o m'ewe olúṣùwàlù jade, o si fi ṣu "ìwa Ifẹ lù. Igbanaa l'awọn ẹiyẹ kékèké lọ si àlé wọn, awọn "eku kékèké lọ si itẹ wọn, awọn àrọ gídigbà lọ si isalẹ odo omi.' Irosu meji*

20. "Ẹgẹ́ n'igi Ifẹ, arúgbó-rùgbò ní ígùn u: gbogbo "irunmalẹ l'o gùn u tì. Ajà idi ẹgẹ kì ijẹ k'ẹni g'ẹgẹ; àgbo "mọmọ idi ẹgẹ ki ijẹ k'ẹni g'ẹgẹ, ejò wèrèrè idi ẹgẹ ki íjẹ k'ẹni "g'ẹgẹ. Ẹgẹ́ m'ori s'owó, o m'ẹhin s'okùn; o m'agbedemeji

---

*"Gbogbo igi oko," e.n. Ọkọọkan igi ti o jẹ aayo fun ọkọọkan irunmalẹ gẹgẹ bi ọpẹ ti jẹ aayo igi fun Ọrunmla.

Nigbati gbogbo igi oko de ọdọ Olodumare, nwọn sọ eru wọn kalẹ, nwọn si fi Ọrunmla sun pe "Ọrunmla ko ma ru ẹse wa o Olodumare!" Sugbọn Olodumare dahun o ni "À! O ti se tirẹ tan!" Beẹli oju ti gbogbo igi oko, Ọrunmla si njọ pada bọ nwipe:— "Igi wọ'we, okun wọ 'we, Ọpẹ nikan l'o ma ma ku o." Ayaani oo ri "Ọpẹ ki iba igi oko wọ' 'we ọdun."

*Itan naa wipe Esu wa gba ọkẹ mẹfa ti Ọrunmla tujọ o ni on yio maa fi sowo fun u; sugbọn nitori o nfẹ ki ti Ọrunmla le bajẹ, o lọ ifi owo naa ra arugbo obirin kan wa ififun Ọrunmla. Arugbo ko gba ju ọjọ mẹta lọ, o yiku. Ọrunmla fi suuru fun ara-rẹ o dakẹ: sugbọn o lọ tọju ibiti o sinku arugbo naa si rere. Saamọsamọ arugbo naa li o bi ọba ol'Ibini ati Ọba-looyọ; awọn mejeeji si ti nwa iya wọn lati ra is'oku-isaaye rẹ ni iyekiye; awọn ọba mejeeji na li o si wa ra oku arugbo naa lọwọ Ọrunmla lowo iyebiye. Ayaani oo ri i "Bi t'ẹni yio ba suan, araiye ki ile ba a jẹ."

*Babalawo kan ti o gbọ iwaasu lenu Ọgbẹni J. A. Savage ni ilu Oke-Igbo li o ki odu-ifa yi bi esi si i ibeere pe "tani le ba nyin tun aiye nyin se?" O dahun pe "A-ti-kekere-s'ọgbọn" e.n. Ọrunmla, "ni yio tun iwa aiye gbogbo se." Nigbati oniwaasu si fun u li aiye lati sọ bi yio ti ri, babalawo naa fi tayọtayọ ki ese-ifa naa bi a ti kọ ọ yi. Eyi ni ireti ti awọn babalawo ilẹ wa nfi siwaju awọn egbeegbaawa enia ti nwọn nko-jẹ ninu isin wọn.

"so kìkì idẹ: Ọrunmla *nikan t'ó m'ẹbọ rírú t'o m'ẹru títù
"l'o mà g'ẹgẹ́ o! " – Irẹtẹ meji.

Akiyesi:– A rí pe awọn ẹsẹ-ifá mẹfẹẹfa ti o ṣiwaju nwọnyi nfihàn bi awọn irunmalẹ̀ ti mọ Ọrunmla tì tí nwọn kò si le íriidí rẹ̀ nitoriti on ju gbogbo wọn lọ ninu ohun gbogbo. Ẹsẹ-ifa 18 tilẹ wipe Eṣu tikalarẹ̀ mọ ọ tì. Bẹẹ gẹgẹ ninu awọn ẹsẹ-ifa àtẹlé wọnyi a oo ri pe awọn ohun-ìpilẹ-ẹ̀dá mọ ọ tì pẹlu.

**21**. "Iná awo òjógbó, oorùn awo ojógbò, oṣupa awo alá-
"tànṣẹerẹ, ójo giiri awo isalu ọrun, awọn mẹrẹẹrin, ni nṣ' ọta
"Ọrunmla * nijọ ti nwọn ní nwọn jumọ mbọwa íba Ọrunmla
jà" — Ogbe 'Sá.

**22**. "Igba Ẹmi * nwọn a maa p'ọlọja-lọjà, nwọn a maa
"p'eríkiin-'ríkiin, o d'ijọ ti nwọn wipe Ọrunmla ni iku kàn,
"Ọrunmla gbé iporún rẹ lé'lẹ̀ ohun ti on íṣe ki igba Ẹmi ti
"mbọ yi ma le pa on. Ó ri Ogbè- 'Sá a ní ahó ọti kan ni ẹbọ,
"ki a ṣe 'hun si i fun u ki o gbé e si ẹ̀hinkulé rẹ̀. Ọrunmla
"gbọ o rú; o ṣẹẹtẹ igba Ẹmì.–Ogbè-'Sá.

---

*Ọrunmla nmura ati-lọ igun ẹgẹ, o gbe iporun rẹ le'lẹ o beere ohun ti on iṣe ki on le gun ẹgẹ: a ni ki o ru akasu ẹkọ kan, igba kan eepo-iṣu, eku kan ati erinka kan. Ọrunmla gbọ o ru tan o ko ohun ẹbọ wọnyi o d'idi igi ẹgẹ. O de ibẹ, aja ku si i Ọrunmla sọ akaṣu ẹkọ si i; agbo ku - si i Ọrunmla gbe, gba eepo-iṣu ti i ; ejo ku-si i Ọrunmla sọ eku ọwọ rẹ̀ si i; akukọ ku-si i Ọrunmla sọ erinka ọwọ rẹ si i. Bi gbogbo awọn olusọ nwọnyi ti njẹbọ wọnni lọwọ, Ọrunmla gun 'gi ẹgẹ l' oke Akukọ galaja idi ẹgẹ l'o kọ taju kan t'o ri Ọrunmla loke ẹgẹ, o gbọn 'pa pipipi o kọ wipe "Ọrunmla g'ẹgẹ-ẹ-ẹ-ẹ!"" Ayaani o ko gbọ bi ogbo-akukọ ti nkọ?

Atijọnaa ni Ọrunmla ti ni ohun gbogbo li anidopin ti o si darugbo kẹgẹ (e.n. darugbo g'ẹgẹ).

*Nigbati Ọrunmla gburo ọtẹ ti awọn mẹrẹẹrin nwọn yi ndi si on, o gbe iporun rẹ le'lẹ o da a, a ni ki o lọ igbe igba iyan mẹrin ati awo ọbẹ mẹta si ọna ti nwọn yio ba wa si ile rẹ̀. Ọrunmla gbọ o ru. Ina ti o ṣiwaju mbọ dẹ ibi ẹbọ yi, o gbe igba iyan kan ati awo ọbẹ kan: Ọrun tẹle e de o gbe igba iyan kan ati awo ọbẹ kan: bẹẹ gẹgẹ si ni Oṣupa pẹlu. Ojo giiri ti o kẹhin de, o ba igba iyan kan ti o ku ṣugbọn ko ba awo ọbẹ̀, o binu nlepa awọn ẹgbẹ rẹ lọ, o ba Oorun o pa a sọna, o ba Oṣupa o pa a sọna, o ba Ina o si pa a sọna pẹlu: bẹẹni ọtẹ ti nwọn di-mọ Ọrunmla ṣe tu.

23. "Ki o ki mi rete ki ng je o rere:- a da a f' Orunmla nijo ti a nda ina Oro * de gbogbo irunmale l'ehinkule. "Ajaruuwa n'Ife-'l'-Agbo: adie meji, agbe omi meji pelu "egbaaji l'ebo: Orunmla tu 'Fa."–Irete-Egutan.

24. "Awon Akereṣohùn, awon Adàgbaṣohùn, awon l'o "dífa fun Orunmla, Ikú kan ile rè íwá níjo ti gbogbo oloja-"'loja ati gbogbo eríkiin-'ríkiin mo oruko odun ti Iku mpa "gbogbo won kiri. Orunmla gbé ìporùn rè lé'lè ohun tí on "íṣe ki Iku má lè pa on; a ni àmorú kan ti a fi egúsi-ìtoo kan ṣe "ehín rè ni ebo, ki a gbé e lo si oriita. Orunmla *gbo o "rú." – Idi - 'Gbè.

---

*"Emi," e.n. aigbo irè oko. "Igba èmi," e.n. oriṣiriṣi aigbo irè, bi iṣu, koko ati ohun bawonni.

Itan na wi lo siwaju bayi pe,— Beeni okokan ni Emi nrin nigba iwa sè. Nigbati Emi ekini de, o ki Orunmla, Orunmla ki i "Pele, o ku atijo! koja si ehinkule ki o bu ago kan mu ninu oti ibè ni." Ekini Emi koja si ehinkule nitooto, o bu ago kan mu ninu oti naa, o subu lulè o ku, a wo o lo sunje. Bee kanna ni Orunmla se si ekeji ati eketa emi titi de eyiti o kehin gbogbo won. Nigbati Orunmla ri ehin igba Emi tan, o bo sode njo wipe:-

"Igba Emi ti mb'Olofin sota,
 Ṣin Emi, Emi siin:
Mo ti m'owo emi di loni,
 Sin Emi, Emi siin:
Iku maa pa won berere niṣo
 Ṣin Emi, Emi siin."

Ni kutu aiye Ile-Ife, nwon a maa deeja awon imale ki nwon to ima bo won. Ina Oro je okan ninu awon idanwo ti a fi nmo eyiti o to iṣe adimula laarin gbogbo won. Idanwo naa ni pe ki imale ti nfe imaa gba iboo wa jo yi ina nla naa ka nigba meji ki o si sare lo ifo ileru naa da koja siha keji laifarapa. Gbogbo oworan n'Ife a si maa patewo korin fun imalè jo bayi pe:-

"O ma njo o,
 À ra jo gbageedee;
Ina Oro njo,
 À ra jo gbageedee:

Lokookan, gbogbo irunmale dan a wo, nwon mbo sinu ileru yi nwon si jona: a si nfi won sesin kiri Ode Ife. Ṣugbon nigbati Orunmla nlo dan a wo, o so agbe omi kan mo ejika otun, o si so okan iyoku mo ejika osi: o si ja won lu ina naa pa bi o ti nse ati-fo, tobee ti o fi le fo o koja sihakeji laifarapa. Gbogbo Ife wa nrawo-rase ki i pe "Orunmla, Iwo nikan li o to ina Ooro irun o!"

Akiyesi — Ninu ẹsẹ-ifá mẹrẹẹrin ti o síwaju, ẹsẹ 21 ati 23 fihan bi awọn ohun ipilẹ ẹdá-ina ati omi-ti mọ Ọrunmla tì: ẹsẹ 22 fihan pe ohunkohun ti ẹnu íjẹ kò ni ipá lori ẹmi Ọrunmla: bẹẹ gẹgẹ ni ẹsẹ 24 fihan pe awọn ayíka ọdun ko ni ibùyan ninu íwa-laayè Ọrunmla. Aropọ gbogbo akiyesi wọnyi ni pe ẹmi ati ìwa-laaye Ọrunmla kò duro le eyikeyi kan ninu ohun ipilẹ-ẹda, ibaaṣe lọkọọkan g-b. *ina, ofuurufu ati omi, oorun, oṣupa ati irawọ; tabi li apapọ wọn g.b. oniruuru eso ati ohun ọgbin ti itipasẹ idapọ awọn ohun ipilẹ ẹda jade; bẹẹ pẹlu ni iwalaayè rẹ naa kò duro le ìgba ati akoko g.b. wakati, ọjọ, oṣu ati ọdun.

Fi èro yi tí awọn baba-nla wa ní sipa Ọrunmla si ègbẹ otito ti a kà ninu iwe mimọ sipa Jesu Kristi.

Heb. *i* 10–12. "Iwọ, OLUWA, lati ipilẹṣẹ li o ti fi ipilẹ aiye sọlẹ; awọn ọrun si ni iṣẹ ọwọ rẹ: nwọn o parun; ṣugbọn iwọ duro, gbogbo wọn ni yio si di gbígbo bi aṣọ; ati bi agbáda ni iwọ o si ká wọn, a o si paarọ wọn: ṣugbọn bakannaa ni iwọ, ọdun rẹ kì yio si pin."

Ninu awọn ẹsẹ-ifa àtẹle wọnyi a o fi han pe awọn enia aiye mọ Ọrunmla tì pẹlu: nitori ọpọlọpọ ìdánwo ni Ọrunmla là kọja

---

24 *Awọn baba-nla wa gbagbọ pe ni ipari ayika Odun kokan, awọn Odun a maa tọọwọ ti isalu ọrun wa sinu aiye, nwọn a si maa sami sara olukuluku enia ti nwọn yio pajẹ, ọdun-nii a sami si awọn ẹran tirẹ, amọdun a sami si tirè, a.i. Ko si si ẹniti imọ ohunkohun titi iku fi ikan a li ojiji: bẹẹli o si ri ti iku fi mpa gbogbo ọlọja-'lọja ati gbogbo erikiin-'rikiin. Ṣugbọn nigbati awọn Odun nwọnyi ntọọwọ bọwa sile Orunmla, nwọn bạ amọru (sigidi) oriita ni bi o ti si ẹhin silẹ, nwọn si ki i pe "Ojobi ọna, o ba duro ki o gb obi je!" Àmọru naa dahun pe "Ehin mo nmu j'obi ng ko nmu jẹ-ni." O si beresi ipe awọn Odun l'orukọ lọkọọkan pe "Ṣebi iwọ Odun-ni niyi, iwọ tọhun si ni Amọdun, iwọ li Odun-taa, iwọ si li Odun-riin, a.b.l. Bẹeni awọn Odun ta giri pe ẹni yi ti se mọ orukọ awọn, nwọn si yara pada kuro lọna ile Orunmla, nwọn ko si le pa a, Ayaani oo ri i "Ọdun ti a ba mọ ki ipa-ni, ọdun ti a ko mọ ni ipa-ni."

*g.b. jasi akọmọna "gẹgẹ bi". a.i. jasi akọmọna "ati iyoku.' a.b. jasi kọmọna "ati bẹẹ lọ."

lọdọ awọn adẹẹjà ki aasiki rẹ̀ to igoke de ipò nla ti o wà nisisiyi, ati ki a si tó le gbà a gbọ bi ọlọrun laarin awọn imalẹ̀:–

**25.** "Ọwọkọ-wọkọ k'ẹni mà baa w'ọkọ ẹni buruku:–a "dá a f'Ọrunmla *nijọ ti Ọlọfin nmú iṣu gbẹ́n 'dó, nmú ewúra "gbẹ́n ọkọ, nmú ọmọdùn gbẹ́n ejija, nmu agbado ṣe àlufín "odídẹ: a ni kini Ọlọfin nfi wọnyi ṣe? O ní on yio fi wọn "dibo pa Ọrunmla ti nwá ifi igbakuugba kifá kó on l'ohun lọ." Iwori–Egután.

**26.** Irẹtẹ-Okanran li a dá nijọ ti gbogbo awo pejọ sile "Ọlọfin nṣoró silẹ̀ de Ọrunmla: a ní ki o rú ewurẹ kan ati ẹgba- "mẹrìndilogun li ẹbọ àrúnù ki o ma baa fi ẹnu ara-rẹ̀ gba iwọ jẹ

---

*Nigbati Ọlọfin mura tan lati ke Ọrunmla wo, o fi iṣu gbẹn odo kekere kan, o fi ewura gbẹn ọkọ, o fi igi ọmodun gbẹn ejija, o si mu agbado ti odidẹ ti fi ṣe alufin, o ko gbogbo ohun wọnyi pẹlu rẹ sinu igba ademu nla kan, o dé e pa: o gbé e kalẹ, o ranṣẹ pe Ọrunmla ki o yara wa ikifa fuubo ti on di do e yi, o si nleri fun awọn emewa pe bi Ọrunmla ba fuubo naa ti, on mu eke rè, pipa li a o si pa a dandan. Ṣugbọn awọn olori Ọlọfin gbọ ileri yi, ẹru si ba wọn pe ika ti Ọlọfin nfẹ ṣe si Ọrunmla ko dara, nitori Ọrunmla ni alaajẹla wọn nibi ati-bi on ati-tọ awọn ọmọ wọn; aanu ṣe wọn, nwọn si ranṣẹ abẹlẹ si i pe ẹhinkule wọn ni ki o gba kọja lọ ijẹ Ọlọfin; ki o si fetisilẹ maa gbọ orin ti awọn yio maa kọ ki o le mọ ohun ti on nlọ iba lọdọ Ọlọfin. Ọrunmla gbagbọ: nigbati o si mba ẹhinkule awọn olori kọja lọ o ngbọ nwọn nfi orin jo ilu bayi pe:–

"E - ee - é - e
A mu 'ṣu gbẹn 'do;
E - ee - é - e,
A mu 'wura gbẹn 'kọ;
E - ee - é - e,
A m'ọmọdun gbẹn 'jijaa;
E - ee - é - e,
A m' agbado s'alufin odidẹ;
E - ee - é - e

Ọrunmla gbọ o mọ sinu, o si kọja tọ Ọlọfin lọ, o ba gbogbo emewa pejọ lọdọ ọba, igba ibo yi si wa niwaju wọn, a tẹ ẹ ti ifa ọba. Ọba ki Ọrunmla tan o si wipe on nfẹ ki o wa ki ifa si igba-ibo ti a de sọọhun ni. Ọrunmla foribalẹ, o si beere pe "Ifa wo ni ọba da loni?" a da a lohun pe Iwori-egutan ni." Nigbanaa ni Ọrunmla kọ 'Haa!' o si bẹresi ifa naa iki gẹgẹ bi eyi ti a kọ soke iwe yi. Ẹru nla ba Ọlọfin lojukannaa, o si fi itara beere kili ẹbọ. Ọrunmla dahun pe "Bi a pe ki Ọlọfin ma ku, ewurẹ kan, ẹgbaa merindilogun ati aṣọ ainina meji li ẹbọ." Ọlọfin yara ko nkan wọnyi silẹ: ṣugbọn Ọrunmla dahun pe, "Bi a pe ki ajẹ aiye ma pa Ọlọfin jẹ, ewusa kan, ẹgbaawa, aṣọ ainina meji li ẹbọ." Ọlọfin yara ko iwọnyi silẹ pẹlu; ṣugbọn Ọrunmla tun dahun pe "Bi a si wipe ki Ọlọfin pẹ laiye, ki o ma d'aiye nu, jẹ ki o mu agutan kan, ẹgbaa merindilogun ati aṣọ ainina marun wa warawara." Bẹẹ ni Ọlọfin yara ko gbogbo nkan naa silẹ lati gba ara rẹ silẹ lọwọ Ọrunmla.

"l'awujọ awo. Ọrunmla gbọ, o rubọ tán , o f'ori lé ile Ọlọfin"*
Irẹtẹ-Ọkanran.

27. "Otúra-meji ni Ọrunmla dá nijọ ti yio fi aayo aya*
"rẹ sile lọ àjo, tí awọn iwarẹfa ilu yio maa fẹ ẹ wipe 'kini
"Ọrunmla ọkọ rẹ yio bọwa ífi awọn ṣe?" – Otura-meji.

---

26 *Bi Ọrunmla ti de ile Ọlọfin, a gbe ọti-ọka silẹ fun u, a si ti fi atẹnujẹ sinu rẹ ki o ba le pa a; ṣugbọn Ọrunmla dahun o ni.

Kini mbẹ ninu oru ti nho yaayaa?
Iwọ ni mbẹ ninu oru ti nho yaayaa:
Irẹtẹ-Ọkanran! Awo ko mu loni, Irẹtẹ-Ọkanran!"

Bẹẹ ni Ọrunmla kọ ti ko mu ọti-ọka yi si. O pẹ titi ere tubọ ndun nile Ọlọfin, ọba ni ki a gbe ọti-ọka kuro ki a si fi ẹmu-ọpẹ siwaju rẹ bakannaa: sugbọn Ọrunmla wo o, o ni

"Kini mbẹ ninu agbè ti nho yaayaa?
Iwọ ni mbẹ ninu agbè ti nho yaayaa:
Irẹtẹ-Ọkanran ! Awo ko mu loni, Irẹtẹ̀ Ọkanran!"

Bẹẹ ni Ọrunmla tun kọ jalẹ, ko si mu ninu ẹmu-ọpẹ yi pẹlu: o si fi wọn sibẹ lọ si ile rẹ̀.

Lẹhin eyi ni ọmọkansoso naa ti Ọlọfin bi ṣaisan, Ọlọfin pe gbogbo awọn awo lati wa ba on wo o san; nwọn de nwọn yan ẹbọ ohun gbe mẹrinmẹrin, Ọlọfin rubọ: gbogbo wọn fohunsọkan wi fun u pe ọmọ naa ki yio ku. Ọlọfin ni ki a pe Ọrunmla wa ki on gbọ imọran tirẹ: sugbọn awọn awo fi keeta papọ wipe ki a ma pe e, ọmọ Ọlọfin fẹrẹẹ san na. Ṣugbọn kaka ki ọmọ san, o ku nijọ 'kẹta. Nigbayi ni ibinu Ọlọfin wa iru si awọn awo wọnyi, o nfẹ ijẹ wọn niya, o si fi ti iku ọmọ rẹ naa dibo fun wọn bayi. O paṣẹ pe ẹnikẹni ko gbọdọ tu ọfọ naa sode, o se ase nlanla nijọ keji, o gun iyan lọpọlọpọ, o pe gbogbo ilu wa ijẹun. O ranṣẹ pe gbogbo awọn awo, o ni ki a gbé igba nla kan siwaju wọn: sinu igba nla naa ni Ọlọfin ge ori oku ọmọ rẹ kansoso ni, o fi isu-iyan kan bọ ọ patapata tobẹẹ ti ko si ibikan ti o han sode lara rẹ, o fi i tẹlẹ, o si wa ko isu iyan pipọ le e lori. Ọlọfin pasẹ ki babalawo kọọkan ma lọ igbe iṣu iyan kọọkan ninu igba yi: gbogbo awọn awo gbe iṣu iyan kọọkan yika, nwọn njẹ, nwọn nmu, nwọn si nṣire nibẹ. Ninu eyi ni Ọlọfin ranṣẹ pe Ọrunmla o ni ki o wa ijẹun. Nigbati Ọrunmla gbe iporun rẹ le 'lẹ̀, o da a wo, o ri Iretè-Ọkanran, a ni ki o sora ki o ma baa fi enu re jeun ti ko wo lode titi ale: nitorina nigbati o de ile Ọlọfin, ti a ni ki o lọ igbe iṣu-iyan tirè ninu igba, o duro lokẹere, o wo titi o kọ "Haa!" o ni:–

"Kini mbẹ ninu igba?
Ohun ti mbẹ ninu igba dabi ikoto araiye.
O si dabi ẹ̀bubu enia:
Irẹtẹ̀-Ọkanran!
Awo ko jẹ loni o, Irẹtẹ̀–Ọkanran!"

Ọrunmla wi bayi tan o pẹhinda lọ ijoko, ẹnu ya Ọlọfin ẹru nla si ba a, o ni ki Ọrunmla jọwọ yan ẹbọ fun on ki on ru; o si wa igbe ori ọmọ rẹ̀ sode fun awọn awo ti nti njẹ iyan nibẹ loni, o nwi fun wọn pe "ori ọmọ mi ti ẹnyin eke awo wi pe ko ni iku ma niyi o!" Lojukannaa ni Ọlọfin paṣẹ a si ko gbogbo awọn eke awo lọ sinu tubu, Ọrunmla si di aayo awo Ọlọfin.

"À ko mọ o tán kò ṣẹ.
A bá mọ o tán ìba ṣẹ kẹ."

Ọna meji ni awọn babalawo mọ oriiki yi si otitọ sipa Ọrunmla. Lọna 'kini,–Pé Ọrunmla kò ṣe, tabi kò dá-ni-lohun niwọn bi on tikararẹ ti jẹ ẹni àimọ fun-ni, e.n. pé ọna gbogbo ti Ọrunmla fi jẹ ẹni awamaridi fun-ni li o si fi jẹ ẹni ai-ṣẹ fun-ni pẹlu. Awọn keferi nro pe bioṣepe awọn le riidi ori-iwa Ọrunmla li ariyika, Ọrunmla iba maa ṣẹ, iba si maa jẹ wọn nigbagbogbo lai-ṣaaki nigbakan.

---

27 *Onipupa ni ns'aya Ọrunmla, ti Ọrunmla fi sile lọ si ajo ti gbogbo awọn iwarẹfa ilu ba ṣika dè e. Eru ba wọn tan nwọn mu onipupa nwọn gbe e ta, nwọn wa itọ bara titun sile de Ọrunmla wipe iboji Onipupa ni'un. Nigbati Ọrunmla bọ ajo, nwọn gba a mu nsipe fun u nwọn ntọọfọ Onipupa. Ọrunmla dupẹ lọwọ wọn. O di ọjọ keji ni Ọrunmla ji kutu wẹ 'wọ-wẹṣẹ o ko iporun rè le'lè, ohun ti on ise ki on tun le ko iru obirin rere bi Onipupa aya on. A ri Otura-meji: Ifa fọre wipe aya rè ni Onipupa ise sibẹ. Ọrunmla tun Ifa bi leere eetiri? Ifa nfọ bakannaa o ni ki Ọrunmla ru ewurẹ kan, ki o si fi ẹja nla kan bọ Iporun rè. Ọrunmla gbọ, o ru: o si wa ran Amoosu on Amoorè lọ sọdọ Otoosu rè lọ ira ẹja wa lodo: Nwon dè ọhun, a ngbe ẹja wẹwẹ han wọn, nwọn kọ nwọn ni awọn nfẹ eyi ti o tobi julọ. A diyele ẹja nla fun wọn, nwọn si sanwo re laidin i ati laibojuwehin. Eyi ya Otoosu lẹnu, o si ran aya rè jade lọ iwo awọn alejo ti nra ẹja nla bẹe. Bi obirin yi ti jade wa iwo, awọn iranṣe Ọrunmla ri i pe Onipupa aya Ọrunmla ni, on obirin naa si mọ wọn ni ọmọ-awo ọkọ on atijọ; tọtun-tosi wọn si dakẹ. Sugbọn awọn iranse pada lọ jihin fun Ọrunmla, on si fi owo iyebiye ran wọn pada wa ira Onipupa kuro lọdọ Otoosu rè ti ise ọmọ-awo Ọrunmla pelu li atijọ. Onipupa tun pada de sọwọ Ọrunmla o si sọ ohun gbogbo ti awọn iwarẹfa ilu ti ṣe si on fun u. Ọrunmla wa se ase nla nijọkeji, o pe gbogbo ilu, o si pe awọn iwarẹfa ika wọnni sibẹ pẹlu. Nigbati ẹse gbogbo ọtọkulu pe tan, Ọrunmla bọ si yaara o wẹ soposoopo jade, gbogbo enia nki i. Lẹhin naa ni o tun wa wọle lọ, o si wẹ jigbenne fun Onipupa, o si ran a ki o gbè ọti jade lọ fun awọn ti o joko lode wọnni. Onipupa gbe ọti de ọhun o kunlè, o gbè e sile o yipada lọ igbe ẹmu jade, o si tun yipada lọ igbe pakata obi jade bẹe gẹgẹ. Gbogbo awọn iwarẹfa naa daamu, nwọn si ba ọna ọtọọtọ salọ sile wọn. Nigbati nwọn tun mpada bọ, olukuluku wọn mu ewurẹ kan ati ẹgbaafa lọwọ pelu agbọn obi kan lati wa fi bẹ Ọrunmla. Nigbana ni Ọrunmla bi wọn ereedi rè ti nwọn fi salọ.

Nwọn dahun wipe:–

"Ọti ti a ri nilẹ li o jọ ọti ẹjọ,
Obi ti a ri nilè li o jọ obi iwa;
Ẹmu ti a ri nilẹ li o jọ emu ailajoorijoori!"

Gbogbo iwarẹfa ilu wa ikunlẹ mbẹ Ọrunmla pe ki o jọwọ mu oju kuro ninu ọran ẹṣe ti nwọn fi se e naa o. Lati ọjọ na ni apa Ọrunmla ti ka awọn agbaagba ilu.

What it takes to become an Ifa priest



Bẹẹ gẹgẹ si ni lọna keji,—Ifá ṣoro kíkọ tobẹẹ ti ko si ẹniti o le ko àkọjari gbogbo odù ifá ni gbogbo ọna ti a ńfi ídìbo tose ọran lẹnu Ọrunmla.

Nota

Lati la-ni-loye diẹ kiun nipa ti ìṣoro ti mbẹ fun babalawo ti nkọ ifá-kíkì, a o ṣiiro ohun ti ijẹ àkọjari odù-ifá.—

1 Gbogbo odu-ifa ti mbẹ jẹ ọtalúgba-din-mẹrin ti o le hù sójú ọpọn. (256 Odus)

2 Awọn orisirisi ọna ibo si jẹ mẹrindilogun t'ibi-t'ire laika awọn ẹka ti ibi ati ire naa ya si.

Fun ẹnikan lati jẹ babalawo ti o gbọ 'fa tó ki ó sa le sí ẹsẹ koọkan nínu olukuluku odu ifá sinu ọkọokan ọna-íbọ wonni, on yio kọ ẹsẹ mẹrindilọgorun-lé-l'egbaajì pelu ẹbọ ti a íyán fun iye ọna bẹẹ. Nitori àmọti ifá–kíkọ yi ni ẹnikẹni ti o tẹ 'fá ara rẹ sílẹ a maa pe ọpọ awọn awo ṣọkan lati wa íkì í fun on, ni ireti pe ẹsẹ ti o pamọ fun ẹnikan le han fun ẹnikeji niti orisi ọna ti a le kì odù kanṣoṣo naa ti ó hù fun u. Nitorinaa nigbati babalawo ba ṣi ifa li ẹsẹ kan, on a yan ẹbọ, on a si fi ìbo beere pe bẹẹni tabi bẹẹkọ: bi Ifá ba kọ ìbo, àmọbí koì tii kàn ẹsẹ ti Ifá nfẹ, ṣugbọn bi o ba gbà ìbo naa, àmọbi ẹbọ naa ni Ifa yàn. Bi babalawo pe ogọjì, ẹsẹ ti ẹniti Ifa gba ibo rè ni à iru li ẹbọ. Sìsẹ ati aisẹ isotele wa ikù sọwọ Ọrunmla. Eyi ni aiya afọsẹ laarin awọn babalawo.

Njẹ ki babalawo kan tó le ni àwíse ati àfọṣẹ Ifa lẹnu, on yio kọ:

(1) Akọjari gbogbo odu-ifa mẹrindilọtalugba fun iye ọna ire ati ibi ti iba ẹda laiye-lorun,

(2) Akọjari gbogbo ẹbọ ti a iyan gbe olukuluku odu ifa wọnni lẹsẹ. On yio si kọ pẹlu.

(3) Lati maa wa li oninukan sí Ọrunmla nigbagbogbo tobẹẹ ti Agbọnnìregún yio fi fẹ ímaa gba ìbọ lọwọ rè.

Awọn keferi gbagbọ pe bi a ba wadi aìṣẹ Ifa kanlẹ̀, ẹbi naa ki yio jẹ ti Ọrunmla bikoṣe ti babalawo tí o ṣe aìtó ninu awọn ọna mẹta ti a ti wi ṣiwaju wọnni. Ka awọn ẹsẹ-ifa àtẹlé wọnyi:–

**28.** "Orí-si-tasí Ọdẹ Ọlọfin,
"Orí-sì-ta-sì Ọdẹ Ọlọfin;
"Atamátàsé Ọdẹ Ọlọfin.
"Orí-sí-ta-sí lọ s'igbo o t'erin,
"Orí-sì-ta-sì lọ s'igbo o t'ẹfọn;
"Ata mátàse lọ s'igbo o t'àgbọnrín.

"Erin tí Orí-sí ta ṣiro ká'gbó tan o wọle wá iwo si m'ògún "Ọlọfin, a nkun u lọwọ a bá igbá àdéìṣí ninu rẹ̀.

"Ẹfọn ti Ori-sí ta ṣiiro ká'gbo tan o wọle wá iwo si m'ọruun "Ọlọfin, a nkun u lọwọ a bá ọmọ titun jojolo t'o diwọ-disẹ̀ "ninu rẹ̀.

"Agbọnrín ti Atamatasé ta sare wá iku si ṣàṣá okuta ẹnu-fò "Ọlọfin, a nkun u lọwọ a bá iikiin mẹrindílogun ninu rẹ̀. "Ọlọfin ní ki gbogbo awo meẹdogun jọ, nwọn jọ, o d'oko amọti "nwọn kùbò nwọn kẹregẹ́de, a kó gbogbo wọn dà s'aaja Ọlọfin.

"Ọlọfin tun beere, a ní o kù awo kan t'o kù: o ni 'tani?' a ní "Egútan-meji awo Ode Idere Mòfún ni. Ọlọfin ranṣẹ lọ "ipè e pe ki o yara wá."

"Ogúda-meji ni Egutan dá nijọ ti a mpè e nile Ọlọfin;–a ní ki "o pa adìẹ kan si iporun rẹ, ki o mu t'apa-t'ẹsẹ rẹ̀ sinu apo pẹlu "ẹkọ mẹta, ki o si fi tọrẹ lọna ki o tọ íde 'le Ọlọfin ki o le ṣe rere "bọ. Egutan gbọ, o rú. Bi o ti nlọ, o bá wundia mẹta loju "odo nfọṣọ lẹhinkule Ọlọfin,."

"Aború ni iṣ'ọmọ Ọlọfin, Aboyè ni iṣ'ọmọ Ọlọfin, Abọṣẹ ni iṣ' "ọmọ Ọlọfin; Awọn meteeta ni iṣ'ọmọ Ọlọfin nijọ ti Egutan- "meji *mbọwa kífa ṣ'ọkọ wọn."—Ogúda-meji.

29 "A-mọ 'fa-má-mọ'fa, A-mọ'fa-má-mọ'fa, adífa "f'Ọl'Ọfa mẹfa nr'àrun igbo, nrun opẹrẹ nilẹ, ẹkurẹ d'aşigbà, "Ọl'Ọfa ekini kú.

---

*Loju odo lẹhinkulẹ Ọlọfin ni Egutan-meji ri awọn wundia mẹta wọnyi – Abọru, Abọye ati Abọṣẹ–ti baba wọn ran sibẹ lati fọṣọ. Ọkan Egutan fa si wọn jọjọ, o si duro ti wọn lati ba wọn darọsọ diẹ. Ninu ọrọ wọn ni o gbọ pe Ọlọfin ti nkanra lati owurọ wa, ati pe ko ranti fun wọn ni onjẹ bẹẹni o ko aṣọ pipọ bayi fun wọn wa si odo lati fọ. Egutan yara tu apo rẹ, o si ko gbogbo onjẹ inu rẹ fun awọn wundia naa, nwọn si fi tayọ-tayọ gba a: nwọn jẹ, nwọn mu, inu wọn si dun pipọ si Egutan tobẹẹ ti nwọn fi pe e mọra, nwọn si sọ gbogbo asiri ti mbẹ ni ile Ọlọfin fun u–
(1) Nipa ti awọn agba ọdẹ Ọlọfin mẹtẹẹta ti o pa abami ẹran loni
(2) Nipa ti awọn agba awo mẹẹdogun ti Ọlọfin de si aja ilẹ ninu ile rẹ, ati
(3) Nipa ti aayo obirin Ọlọfin ti nti nrọbi lati ijẹta, ti ndaamu Ọlọfin.
Awọn wundia nwọnyi si tikarawọn kọ Egutan-meji pe ki o bẹere awọn lọwọ Ọlọfin ki o si gba wọn lọwọ rẹ lọ ifi ṣe aya. Egutan kọja lọ o de ile Ọlọfin, o ba a tẹ 'fa silẹ, a ni ki o wa wi ohun ti ifa ri fun Ọlọfin. Egutan ko ifa Ọlọfin o da a, a ri Oguda-meji, o ni "Ha! ọdẹ Ọlọfin mẹtẹẹta li o pẹran loni, ki a yara lọ ikun ẹran ti ekini a o ba igba adeiṣi ninu rẹ, ki a mu igba naa wa ikan aboyun ti nrọbi nile Ọlọfin lati ijẹta nikun ni gbamgba ode aafin yi ki o le bi tibi-tire. Ọlọfin gbọ, o wariri.

Egutan ni ki a si yara lọ ikun ẹran ti ekeji, ki a gbe ọmọ jojolo ti o diwọ-disẹ sinu rẹ wa iri si baluwẹ Ọlọfin ki o maa wẹ le e lori kije bi a ba fẹ ki Ọlọfin ma ku titi ọjọ meje. Ọlọfin gbọ, o ntọ o nsu sara. Egutan ni ki a si tun yara lọ ikun ẹran ti ẹkẹta, ki a ko ikin mẹrindilogun inu rẹ wa ide-mọgba ifa Ọlọfin ki o maa pẹran bọ ọ lọdọọdun: ki o si yara lọ ida onde titun mẹẹdogun ti a ṣẹṣẹ ko sinu tubu wa ififun on, bi ko ba fẹ iku titi alẹ loni. Ọlọfin gbọ, o nku lọ. A wa bẹresi Egutan meji ibẹ pe ki o yan ẹbọ ti Ọlọfin iru ti iye.

Egutan ni bi a wipe ki Ọlọfin ma ku warawara, ki a lọ imu wundia mẹta ti nfọṣọ lọwọlọwọ loju odo ẹhinkulẹ Ọlọfin fun on wa, ki Ọlọfin wẹ wọn, ki o si fi ewurẹ mẹta ati ẹgbaa mẹrindilogun sin wọn wa iba on. Gbogbo nkan naa li a si yara ṣe gẹgẹ bi Egutan ti yan a fun Ọlọfin. 1. A fi igba adeiṣi ti a ba nikun erin kan ikun aboyun ile Ọlọfin, o si bi lojukan-naa tibi-tire. 2. A si gbe ọmọ jojolo ti a ba ti o diwọdisẹ ninu ẹfọn lọ iri si baluwẹ Ọlọfin, o si nwẹ le e lori kije ko ku mọ. 3 A ko ikin ti a ba nikun agbọnrin lọ ide mọ igba-ifa Ọlọfin, o si mgbibọ ọdọọdun lọwọ Ọlọfin.

A si wa lọ da awọn awo mẹẹdogun ti a ti gbe-de lati owurọ wa ifun Egutan, a fi awọn ọmọbirin Ọlọfin mẹteẹta ti i: Egutan si nko wọn lọ sile. Nigbati nwọn de ile, Egutan da awọn awo silẹ ki nwọn le maa lọ si ile tiwọn: ṣugbọn nwọn dahun pe nwọn ko le lọ bẹẹ lai-pinnu iṣẹ ti awọn yio maa ṣe sin i titi lai nitori ti iku ti o gbe-fo lori wọn. Egutan ni on ko yan iṣẹ kan fun wọn, ṣugbọn on fẹ ki nwọn maa juba on nigbagbogbo lọna bayi:– ẹnikẹni ninu wọn ti yio ba pa ẹrankẹran kan, nigbati o ba fi ọbẹ le ọrun ẹran naa ki o wipe "Egutan-meji pa ọ".

Awọn ọmọbirin mẹtẹẹta Ọlọfin si fi bẹẹ di aya Egutan-meji: ṣugbọn ni 'jọ keji ti nwọn de ile rẹ, o ji lowurọ kutu o si juba wọn nitori oore ti wọn ṣe fun u li ana, o nki wọn bayi pe:– Mo yin Àbọru, mo yin Àbọye, mo yin Àbọṣẹ."
Ayaani oo rı ı, babalawo a maa ji kutu wuure bẹẹ.

'A-mọ'fa–má-mọ'fà, A-mọ'fà–má-mọ'fà, adífa f'OlỌọfà "marun nr'àrun ìgbo, nrun ọpẹẹrẹ nilẹ, ẹkurẹ d'àṣígbà, "Ọl'Ọọfà ekeji ku.

"A-mọ'fá-má-mọ'fà, A-mọ'fà-má-mọ'fá, adífa f'Ọl'Ọọfà "mẹrin nr'àrun ìgbo, nrun ọpẹẹrẹ nilẹ, ẹkurẹ d'àṣígbà, "Ọl'Ọọfa ẹkẹta de ẹkarun kú; o wa ku ọkanṣọṣọ nílẹ.

"A-mọ'fa-má-mọ'fà, A-mọ-fà-má-mọ'fá, adifa f'Ọl'Ọọfà "kanṣọṣọ iyókún nr'àrun ìgbo, nrún ọpẹẹrẹ nílẹ, ẹkurẹ "d'àṣígbà; a ní bi Ọl'Ọọfà kanṣọṣọ yi bá kú, iwọ A-mọ'fá–"má-mọ'fà, A-mọ'fà-má-mọ'fá li a oo mà pa ní i ò! A-"mọ'fá gbọ o sá s'ígbo.*—Idi-'Gbè.

**30.** "Awo-ju-awo-lọ l'ó difa fun Ajibowu ọmọ alagbẹdẹ "oke ọjà nijọ ara gbogbo ndún u, kò le gb'apa kò le gb'ẹsẹ, "a ní k'ó rú obukọ, o rú lẹrinkínín ón tikàlarẹ rú u, ó "ngbé e jẹ; o rú lẹrìnkeji, ón tìkálarẹ rú u, ó ngbe e jẹ: "àbori Ajibowu kọ kò ṣé pẹrẹ. Awo-ju-awo-lọ waìde nikẹhin, "ó dífa a rí Ogbè-'Sá, o ní obukọ kan ati ẹgbẹsan ni ẹbọ; "ki a mú u si kàragbá mẹsan, ki a mú ori ẹbọ naa ṣẹbọ orí, "ki a mu ọrún ẹbọ naa ṣẹbọ ọrun, ki a mu èjiká meji ẹbọ "naa ṣẹbọ èjiká meji, ki a mu ookan-aiya ẹbọ naa ṣẹbọ "ookan-aiya, ki a mu ogoji-ẹhin ẹbọ naa ṣẹbọ ogoji-èhin, ki "a mú orúnkun meji ẹbọ naa ṣẹbọ

---

*Bi Amọfa ti nlọ ninu igbo ti o sa-si, o ko ọdẹ kan ti o ti sọnu s'igbo, o si fi ọna ile han a. O tun rin siwaju die, o ri iya arugbo kan ti o di ẹru igi nla kalè ti ko le gbe e ru. Arugbo naa bẹ Amọfa ki o jare gbèru on, sugbọn Amọfa dahun pe:– Àni Ol'Ọofa nku lọ a si nfè ipa mi mọ oku rè bayi, ng ko ma roju gberu enia ninu eyi ti mo wa yi o!" Arugbo dahun o ni "saa duro gberu mi, nitori emi dandan ni iku ti o ti mpa gbogbo Ọl'Ọfa" Bẹeni Amọfa yara duro, o si wa iran arugbo naa li ẹru igi rè kori si ile. Bi nwọn ti njumọ lọ sile, arugbo sọ fun Amọfa pe "nigbati o ba pada de'le, sọ fun awọn ọmọ Olọfin ki nwọn lọ igbẹn ilè lori ibusun Ọlọfin niha ori ati aiya ati ẹsẹ rè, nwọn yio ba amu kọọkan nibẹ ti ẹjẹ mbẹ ninu wọn: jẹ ki nwọn hu amu wọnni soke, nitori nibẹ ni ẹjẹ ara awọn ọba ti nwọ-si ti nwọn fi nku: si mu ninu ẹjẹ ti olukuluku amu naa ki o si fi buwọn li ẹsẹ, aiya ati ori Ọlọfin, gbogbo ara rẹ yio si sọji, yio si bọ sipo." Amọfa dupẹ pupọ, o lọ sile, o si se bi arugbo ni ti sọ fun u; ara Ọl'Ọfa kansoso yio kun bọ sipo nitootọ ko ku mọ.

"orúnkun meji, ki a mú ìdí ẹbọ naa ṣebọ ìdí. Ajibowu gbọ, o "rú; o d'ijọ keji o dide kánbán: o wa mẹkun ṣ'ẹkún igbe, ó "m'ohún ṣo'hún yẹrẹ, o nkọrin wipe,—

"Orí ti nsán mi l'aaná kò mà sán mi mọ loni
"Asuuruuduu òlulu! E, awo j'awo òlulu.

"Ọrun ti ndun mi l'aaná ko mà dun mi mọ loni
"Asuuruuduu òlulu! E, awo j'awo òlulu.

"Apá ti ndun mi l'aaná ko mà dun mi mọ loni
"Asuuruuduu òlulu! E, awo j'awo òlulu."—Ogbe-'Sá.

Bẹẹ l'o si nñ gbogbo oriikẹ ara iyokun kọrin yika.

**31.** "Mímọọdá l'awo Ẹl'Ẹká, Aimọọdá l'awo On' Ikanranmu, Afẹẹfẹ ni iṣe ori igi yẹrẹyẹrẹ, ẹfuufu nla ni iṣ'ewe "agbọn nìkọrọnikọrọ, adifa fun Ọrumnla a ni ki o rubọ; "ó ní 'tani ẹ dá fun t'ó ṣẹ rí?' nwọn ni awọn l'awọn dá "fun òromọ adiẹ af'ìkó lòmlò a mú u rubọ sidi èṣu, o si p'ọmọ "sẹhin ṣọrọṣọrọ. Ọrunmla suka-wọn-'rí o ní eewọ! iyẹn "awo ẹiyẹ, ng kò ni íb'ẹiyẹ rubọ-pọ.' Mimọọdá l'awo "Ẹl'Ẹká, Aimọọda l'awo Ikanranmú, Afẹẹfẹ ni iṣe ori igi "yẹrẹyẹrẹ, ẹfuufu nla ni iṣ'ewe agbọn nìkọrọ-nìkọrọ, adifa "fun Ọrunmla a ní kí o rubọ; o ní 'tani ẹ dá fun t'o ṣẹ ri?' "nwọn ní awọn l'awọn dá fun igi èkiika ti a gé lori gé niidi, "ti a lu ihò-ìde si lẹṣẹ, o si tun ruwe o so iyeeyé sori ṣanran-"ṣanran. Ọrunmla suukawọn'rí o ni 'eewọ! iyẹn awo igi, "ng kò ni íba 'gi rubọ-pọ.'

"Mímọọda l'awo Ẹl'Ẹká, Aimọọdá l'awo Iknranmu, "Afẹẹfẹ ni iṣe ori igi yẹrẹyẹrẹ, ẹfuufu nla ni iṣ'ewe agbọn nikọrọ-nìkọrọ adifa fun Ọrunmla a ní ki o rubọ, o ní 'tani ẹ "da fun t'ó ṣẹ rí?' nwọn ni awọn l'awọn dá fun Ol'Ilá nigbati "o m'ojuju s'ẹṣẹ, t'ó nm'ẹeforẹ se ibantẹ, t'ó nṣẹ hárahára "igi ti kò ri oju pọnna ode tà a, t'ò mbẹbẹ k'ó ìtẹ oju-ode "ẹni gbọnre. Ol'Ilá rú ewurẹ mẹta o là o lu, o sì nmu irukẹrẹ "ṣe 'Gboo-si ọna Iráyé lọdọ Ọlọfin. Ọrunmla ní 'En-"ẹẹn-ẹẹn-ẹẹn, ngo rubọ ìyẹn wàyi o! '"—Oguda-'Sa.

32. "Awo Ajíkí l'awo Ajíkí, Awo Ajìkì l'awo Ajíkì, "Awo Ajíkì l'á ipe awo Aja-alẹ̀-gbuun;-a dá a, awọn mẹtẹẹta "nlọ ibọ Orí-Ẹlú, Orí-Ẹlú kò gb'ẹbọ lọwọ wọn.

"Awo Ajíkí l'awo Ajíkí, Awo Ajìkì l'awo Ajíkì, Awo "Ajíkì l'á ipe awo Aja-alẹ̀-gbuun; a dá a fun Okètè f'ọwọ "winni-winní t'ó ni on yio bọ Ori-Ẹlú, Okètè kì Ori-Ẹlú titi "Orí-Ẹlú kò gbà 'bọ lọwọ rẹ̀. Njẹ lésí kan maa bọ Orí-Ẹlú ti "Orí-Ẹlú yio gbà lọwọ rẹ̀?

"Awo Ajíkí l'awo Ajíkí, Awo Ajìkì l'awo Ajíkì, Awo "Ajíkì l'á ipe awo Aja-alẹ̀-gbuun;–a dá a fun Ikì t'ó ni on yio "bọ Orí-Ẹlú, yio gbà ìbọ lọwọ on. Ikì jí o wẹwọ fini o wẹsẹ "fini, ó wa ímu obì ó ná a si Orí-Ẹlú, Orí-Ẹlú gbà lọwọ rẹ̀, ó ní "Iwọ Iki ẹlẹyinjú ẹgẹ́ l'o tó mi íbọ.' Igbanaa ni Iki m'ẹ̀kun "ṣ'ẹkún igbe, o m'ohun ṣo'hun yẹrẹ nkọrin wipe—

" 'Gb' obì pa o, Awo Ayẹ̀!
"Gb'obì pa o, Awo Ayẹ̀!' "—Irẹtẹ-'Sá.

33. "Ọrunmla ni 'Alugbohun!' mo ní Alugbóhun!—' "O ní 'ìgbatí a lu ọmọ Ogún a kò gb'óhun Ogun i?' mo nì 'a "mà gbóhun Ogun ò. Ọrunmla ní 'Alugbóhun!' mo ni "Alugbóhun!; O ni 'igbatí a lu ọmọ Orịṣa a kò gb'óhun Orịṣa "i ?' mo ní 'a mà gbóhun Orịṣa ò.'

"Ọrunmla ní 'Alugbóhun!' mo ni 'Alugbóhun!' O ní " 'ìgbati a lu ọmọ Ọbàlufọn a kò gbohun Ọbalufọn i?' mo ní " 'a mà gbohun Ọbàlufọn ò.'

"Ọrunmla ní 'Alugbóhun!' mo ní 'Alugbohun!' O ni "ìgbatí a ba lu ọmọ on Ọrunmla a kì yio hagbohun on i?' mo "ni 'a oo mà gbohun rẹ ò!' O ní.

'Njẹ, Agbe, maa gbé ohun mi r'ókun,
Alukò, maa gb'ohun mi r'ọsa;
 Itiyanrinyanrın maa gb'ohun mi r'ọrun adé:
Ki ohun mo ba wı lonı se, rere!
Ohun mo wi loni a ṣe, rẹrẹ!' "

# ORI IV

"Oluwa mi Ol'ọwa aì-yèrè:
Opokí, A-mu-idẹ-ṣ'oju."

A maa pe ọdẹdẹ gígun tí awọn ọba ati awọn ìwarẹfa ati awọn ọlọla ilu ima kọ si gbangba ita àbáwọle wọn ni 'ẹnu-ọwá': iru ọdẹdẹ bẹẹ ti o kere ti a si kọ-pọ mọ ile kekere ti awọn talaka ati awọn alainóyè-lọrun li a mpe ni 'ẹnu-ifo' e.n. ẹnu ihò. (Ondo ati Ekiti). Sugbọn kili a mpe ni 'Owá' paapaa? A le tumọ rẹ si ọna wọnyi—

(1). Ọwá ni pèpé ti a mọ fun ọba ati awọn ijoye rẹ lati maa joko lé ninu apejọ ilu.

☞ * Latihin ni orukọ naa si ti ran gbogbo iru pèpéle bẹẹ ti a mọ yika ile awọn enia miran. A maa ran ọmọde ki o fi ida tabi ohun miran le ori-ọwa funni. Ẹse-ifá kan wi bayi pè "Or'ọwa (ori–owa—ori pèpéle) ṣebi ẹniti yio difa, ko si difa."—Ọgbè-Atè. Ewe, "Or'ọwa ki iṣe ile awun, Ọgbagba (itẹbọ ile) ki iṣe ile igbín."—Iká-Turúpọn.

(2). Ọwa ni aṣẹ ati ọlá ti a fifun ẹniti o joko lé ori pèpé ti a mọ fun ẹni ọtọ ati ẹni ọwọ.

☞ * Latihin ni gbogbo ẹni ekini ninu ẹgbẹ-igbimọ, tabi ẹni ọtọ ati ẹni ọwọ ti njẹ Olọwá e.n. Oniijoko ekini laarin awọn àgbà ori-ọwa. A si maa pe awọn ọba Ilẹ Ekiti ni 'Ọwa,' bẹẹni a maa gbọ lẹnu awọn ara Ilẹ Ekiti pe awọn "nlọ ijiṣe 'Ọwá' nwọn a si maa pe ara-wọn ni "Ẹru Ọwá" tabi 'Ọmọ Ọwa'

Nję, Ol'ọwa ni ẹniti ó ni ipò asẹ ati ọla giga julọ laarin awọn ijoye ilu! gẹgẹ bi ọba ti ini ìtẹ giga laarin awọn Iwarẹfa.

Ni pipe Ọrunmla ní 'Ọl'ọwa,' ọkan ìsin awọn baba-nla wa fi ipò giga julọ laiye-lọrun fun u; a ti sọrọ pupọ sipa eyi ninu Iwe I. 16-20, ati ninu Iwe II Ori 2.

Ṣugbọn ní pipe Ọrunmla ní 'Ọl'ọwa aìyẹrẹ,' ọkàn isin awọn baba-nla wa pe e ni ọba tabi alaaṣẹ ti (a) a kò gbọdọ yẹ-nipò: bẹni (b) kì yio yẹ'pò titi lailai.

A o mú ẹsẹ-ifá diẹ gbe akiyesi wọnyi lẹsẹ.—

(*a*). A kò gbọdọ yẹ Ọrunmla nipò, aiye yio bajẹ.

**34.** "Ọdun t'ọwọ gbó, ọdun t'ẹsẹ gbó, ọdun ti gbogbo "ara gbó jáweejáwee, a dá a fun Ọrunmla nijọ ti gbogbo aiye "koosiirì mọ ọ ti o ku Ẹdun nikanṣoṣo li ọrẹ Ọrunmla ninu "gbogbo ọmọ ẹranko.

"Ọdun t'ọwọ gbó, ọdun t'ẹsẹ gbó, ọdun ti gbogbo ara "gbo jáweejáwee, a da a fun Ẹdun nijọ ti gbogbo ọmọ araiye "k'oosiiri m' Ọrunmla,*ti nwọn gbé ìporun rẹ lo sọ sibu omi, "ti Ọrunmla nran Ẹdun lọ igbe igbá omiràn t'ode ọrun wa "ífun u."—Ogúda-'Sá.

---

* A gbọ siwaju niti osiiri yi pe o gbilẹ tobẹẹ laarin t'enia-t'ẹranko si Ọrunmla ti awọn ọmọ araiye fohunṣọkan nigbati nwọn gbọ pe Ẹdun lọ si ọrun lọ igbe igba-ifa miran wa ifun Ọrunmla, nwọn lọ ibẹ gbogbo igi ti o wa li agbegbe ilu wọn ki Ẹdun mase ribi balẹ si nigbati o ba nti ọrun bọ: ni sise eyi nwọn nreti pe ọwọ wọn yio tẹ Ẹdun ki o to le sare nilẹ wọle Ọrunmla. Nwọn bẹ gbogbo igi sugbọn o ku ọpẹ kansoso ti mbẹ niwaju ile Ọrunmla. Bi Ẹdun ti bojuwo ile aiye lati isalu ọrun, ẹnu ya a lati ri gbogbo rẹ mọ lọ sanlalu, ko ri igikigi kan lati fo le bikose ọpẹ kansoso ti o duro loju-ode Ọrunmla. Nigbati Ẹdun fojusun ọpẹ yi titi, o fọwọ mejeji wa igba-iporun naa mọ aiya , o si gbera pa, o fo firi wa balẹ sori ọpẹ naa, sugbọn emimi naa pọ tobẹẹ ti igba-iporun naa fọ mọ ọ li aiya, ti gbogbo ikin inu rẹ si fun kakiri. Ẹdun fi ibanujẹ ke kara pe "Haa! Iwa nu, iwa nu, iwa nu." Ọrunmla gbọ igbe Ẹdun o yara bọ sode nsa awọn ikin naa jọ nwipe 'Yee! Eyi ti san, mo ri dede ko, mo ri dede ko." Bẹeni ọwọ Ọrunmla tẹ iporun miran o si tẹfa gagara silẹ nijọ karun eru si ba gbogbo awọn ọmọ enia nwọn yara wa tumba fun u; sugbọn awọn ọmọ ẹranko ko kasi sibẹsibẹ. Nigbanaa ni Ọrunmla pinnu lati da awọn ẹranko niji diẹ loru ọjọ kan, o wi fun Ẹdun tẹlẹ pe k'o maṣe bẹru, – ko si nkan,

see p. 44

**35.** "Láyimiká l'awo Oré, Erè l'awo àbata, Gbọdunro "gbọdunfọ l'awo òtuuruu:–a dá a fun wọn ni'Ifè OO yè "lagbò nijọ ti nwọn dawọjọ nle Ọrunmla ** s'ígbo"

**36.** "Irẹẹtẹ-Ọkanran li a dá f'Ọrunmla nijọ ti gbogbo "awo pejọ sile Ọlọfin nṣ'oró silẹ dè e, a ní ki o gbaawẹ ṣulẹ "loni kí àṣubi orólẹ * le tan fun u loni."—Irẹẹtẹ-Ọkanran.

---

ohun ọkọnrin ni ki o fọ bi o ba gburo aburadi kan loru oni. O di ọganjọ dundun, Ọrunmla na ọpa ọrẹrẹ rè si oke gẹgẹre eti okun, okuta nla kan si ya tibè lu omi gbirigidi, iṣẹlẹ sè: tobẹẹ ti erin saresare o fi ipe da, efọn saresare o fi ajaipa kọ'gi; a ko le ka oku wẹwẹwẹ eran. Ṣugbọn ẹdun nikan ti Ọrunmla ti sọ fun tẹlẹ li o dahun li ọganjọ naa wipe
"Lèsi nda Orisa niji? Lèsi nda Orisa niji?
Agada ni ngo fi ṣe e lori ramu-ramu-ramu!
Ayaani o ko ngbọ bi alukẹdun ti nkigbe l'ọganjọ?"

35 **Ṣugbọn awọn ọmọ enia ko tumba tinutinu fun Ọrunmla, nitori lehin eyi ni gbogbo wọn tun gbaraịọ lẹ e kuro ni ilu, nwọn wipe on kannaa ni mbaiye jẹ tan ti o wipe on ntun u ṣe; bi ko si laiye kini mbaiye jẹ? Njẹ Ọrunmla ji kutu nijọ kan o binu wọnu igbo lọ ṣọna jijin rere, o dè ohun tan o kòle imu, o yòdede erinn, o ngbe inu rẹ fọjoojumọ wipe "Bi o ba jẹ iru ile ti mo kọ sihin l'Ọlọfin ngbe inu rè n'Ifè ni aiye wọn le roju." Ko n'iye ọjọ, bẹẹni kirikiri m'aiye, dugbẹdugbẹ m'ọrun; ọda da-mọ wọn, owo wo, ojo ko rọ, akẹremọdo k'oorungbẹ; ojo gbọrọ gbọrọ ko rọ mó, ẹsin ọba ko j'oko, opo ko tirinmọlè mọ, agan ko tọwọ ala b'osun. Isu p'oloota, agbado tipé ko gbo, adiẹ fu ko n'iyé.

G. Adeol p. 14 no 42

A ni "eetiri?" Nwọn ni "Ọrunmla l'o pa'di osu da soke ti popojaja m'aiye n'Ile Ifè; bikoṣe a ri Ọrunmla ki aiye to le igun." Bẹẹni gbogbo enia bọ sigbo nfi omije wa Ọrunmla kiri titi nwọn fi lọ ide ibi ile ti o kọ sigbo, nwọn kankun imu naa, Ọrunmla dahun ninu ile o ni "Awọn tani nkan ile imu mi?" Nwọn ni "Awa Ifè Oyelagbo ni". O ni "kili ẹ nwa ti ẹ nki mi ni 'Okun, Oké'?" Nwọn ni "Ọlọfin l'o ni ki a maa lọ wa ọ ri ki a maa bè ọ ki o bowa iba on tun Ile Ifè ṣe." Ọrunmla dahun pe "E lọ wi f'Ọlọfin bi ẹ ba pe ki ng wa'le ki o ni eku meji oniiwere, ẹja meji afirulagba; akukọ meji afiru gagaga, obi adiẹ meji af'aiya gbẹnkẹn, obukọ meji olusibebe, ewurẹ meji af'amu-rẹndẹnrẹndẹn; agbo meji af'owo ṣuṣuka, agutan meji afimu bọrọgi; ki ẹ si wa fi ẹgbaa mejilelogun le e." Nwọn yara ko gbogbo nkan wọnyi wa fun Ọrunmla ki o to ba wọn pada wọ ilu lọ. Ṣugbọn sibẹsibẹ nigbati Ọrunmla pada de ile, ode ilu tun ngbona girigiri, nigbanaa ni gbogbo ilu tun kigbe wa iba Ọrunmla pe ki o gba wọn mase jẹ ki ilu bajẹ: Ọrunmla si tun gba ohun mejimeji lọwọ wọn bi ti isiwaju, o pero si ilu fun wọn, ilu wa idero patapata.

36 *Nigbayi ni gbogbo awọn adahunṣe ilu pejọ sile Ọlọfin, nwọn ba a gbimọ ki nwọn le fi maajele pa Ọrunmla, nitorinaa nwọn fi i sinu ẹmu ati ogurọ nwọn si fi ataaragba sinu aṣọ ibora ati eni dè e, nwọn ransẹ si Ọrunmla, pe ki o wa ba wọn se ajọ-asc kan nile Ọlọfin o. Nigbati Ọrunm-

**37.** "Irẹtẹ-Ọkanran li a dá f' Ọrunmla nijọ ti a mpe
"gbogbo awo lọ ijẹ'yán alaìmọra nile Ọlọfin; a ní ki Ọrunmla
"tun gbaawẹ ṣulẹ loni ki oju ma baa tì i bọ ile Ọlọfin loni.*
"A ni eeti tún ri loni ẹwẹ? O ni ẹnyin ko mọ pe alailojuuti
"ni íjẹ 'yán Ọbara-Ofú?"—Irẹtẹ-Ọkanran.

---

la de ile Olọfin, nwọn gbe emu yi silẹ fun u pe ki o mu, sugbọn o wo o titi o ni

"Kini mbẹ ninu oru ti nho yaayaa?
Iwọ ni mbẹ ninu oru ti nho yaayaa!
Ireetẹ-Ọkanran! Awo ko mu loni, Ireete-Ọkanran!"

O pé diẹ nwọn gbe oguro sile fun u ki o mu, sugbọn Orunmla wo o titi o tun wi bi ti isaaju. Njẹ Olọfin té ifa rẹ silẹ o ni ki nwọn wo o fun arẹmọ on ti mbe ni ibulẹ aisan. Gbogbo awọn adahunse ti wipe ọmọ yi ki yio ku, Olọfin beere lọwọ Ọrunmla, Ọrunmla ni yio ku afi bi Ọlọfin ru aṣọ igunwa ati ẹni ori ité rẹ ki a fi seun fun u. Ọlọfin ti o ti nwa ọna ati-pa Orunmla yọ pe ọwọ tẹ e wayi o, nitorina o mu ataragba sinu aṣọ ati ẹni naa ki o to igbe e jade fun Ọrunmla. Sugbọn bi a ti mu nkan wọnyi jade, beẹni eiyẹ Ago ti nse oniranti Orunmla ke-si i tantan wipe

"Ọrunmla! Ma ma joko l'ẹni loni o!
Ma ma joko l'aṣọ loni o!
Joko lori ifin, joko lori ifin!"

Bẹẹni Orunmla yara wipe ki nwọn tikarawọn fi asọ naa bora ki nwọn si joko le ẹni naa funrawọn. Oro si mu gbogbo awọn ti o se bẹẹ. Orunmla si lọ lalafia sile rẹ.

37 *Lọjọ diẹ si i, arẹmọ Ọlọfin ti awọn awo wipe ki yio ku ku dandan; inu bi Olọfin gidigidi, sugbọn o ni on ko fẹ ki ẹnikẹni gbọ lode ilu, o ni ki a pa a mọra, on yio mu gbogbo wọn t'Orunmla t'Orunmla : o ge ori ọmọ yi pamọ o gbe iyoku rẹ sin, o makẹda. Nijọ ti ase ile Ọlọfin tun ko, Olọfin fi ori ọmọ yi tele igba iyan, o patẹbọ iyan bo o, o ransẹ ki a ko gbogbo awo ilu wa ijase nile on loni. Gbogbo orisirisi ẹgbẹ-awo ti o siwaju Orunmla de ibi ase li o ti bu ninu iyan Ọlọfin nwọn si jẹ ẹ. Ọlọfin dakẹ nwo wọn, o ni ki awọn tẹtu maa mura ati-ko gbogbo awo lọ ide sinu tubu. Nikẹhin gbogbo wọn ni Orunmla de, a gbe igba iyan yi ati awo ọbẹ kalẹ fun u lati bu tirẹ. Nigbati Orunmla wo o titi on ni

"Kini mbẹ ninu igba?
Ohun ti mbẹ ninu igba dabi ikoto araiye,
O si dabi ẹbubu enia!
Irẹtẹ-Ọkanran! Awo ko jẹ loni o, Irẹtẹ-Ọkanran!"

Eru ba Olọfin o ni ki Orunmla yan ẹbọ fun on. Orunmla dahun o ni
"Kini ẹbọ arunu?
Ekeregbe kan, ẹgbaa'mẹrindinlogun on l'ẹbọ arunu;
Ki a si ko gbogbo awo ailojuti wa itumba f'Orunmla."

A ko gbogb ohun ẹbọ silẹ warawara, a si ko gbogbo awọn awo wọnni ti i; bẹẹni Orunmla se gba wọn silẹ lọwọ Ọlọfin ti ngbiro lati pa wọn. Nigbati Orunmla ko gbogbo wọn de ile, nwọn foribalẹ fun u wipe on ni nwọn yio ma sin titi lailai; Orunmla da gbogbo wọn silẹ, oni ki nwọn maa lọ.

**38.** "Ọrọ-f'orí-ṣ'agogo adifa f' Ọrunmlà gbogbo Irun-"malẹ̀ gbà òsìri mọ ọ, nwọn ni fẹẹrẹ̀ ọla ni nwọn íjí-kutu bolé "rẹ̀: a ní ki Ọrunmla ru igba ẹyin adiẹ ki ó tò wọn yí ile rẹ̀ ká "ki apa awọn Irunmalẹ má lè ká a. **Ọrunmla gbọ o rú, apa "gbogbo Irunmalẹ kò ká a."—Ika-'Gbè.

(*b*) Ọrunmla kì yio yẹ-pò titi lailai.—

**39.** "Ẹniti kò ti-ni ífá laiye kì iti-ni ifa lọrun:— a dá a "f'Ọrunmla*gbogbo aiye kó ẹjọ rẹ lọ íwí lọrun pé ibágbe rẹ̀ nni "nwọn lara, kí Ọlọrun jare yan ẹlomiran tì wọn, aiye bajẹ tan "Ẹru àtori kan l'ẹbọ. Ọrunmla gbọ, o ru, o mura o lọ jé "ẹjọ araiye lode ọrun."

---

38 **Ṣugbọn awọn awo nwọnyi peropọ̀ nwọn lọ bẹ awọn Irunmalè lọwẹ lati gbe wọn niija si Ọrunmla. Nigbati gbogbo ogun wọn pe tan, nwọn lọ do-ti Ọrunmla, nwọn ko fiyesi awọn ẹyin adiẹ ti o to yi ile rẹ ka; ṣugbọn loru ọjọ naa ki ilẹ to imọ̀, gbogbo ẹyin adiẹ nwọnnni ta wọlẹ̀ lọ, nwọn si yọri soke-soke pẹlu bi oke giga, nwọn diina mọ ogun awọn Irunmalẹ; ẹru si ba wọn gidigidi. Nisisiyi ni Ọrunmla hamọra patapata o jade si wọn; gbogbo Irunmalẹ si tumba fun u, nwọn ni "nitootọ iwọ Ọrunmla li o to orukọ oke ijẹ." Atijọnaa ni Ọrunmla ti njẹ "Titi la iti oke."

39 *Nigbati Ọrunmla nlọ jẹ ẹjọ yi, o gbé ẹru atori yi ru o nkaanu bi o ti nlọ pe njẹ ọmọ araiye l'o sa se aimoore to bayi! Bi o ti nkaanu lọ, o ko Esu lọna; Esu bi i pe "nibo ni o nlọ t'iwọ t'eru atori lori?" Ọrunmla dahun pe "awọn ọmọ araiye li o ma lọ fi mi sun lọrun pe iwa mi le ju fun wọn ki Ọlọrun paarọ mi o!" Esu ni "Haa! iwọ ti o tutu bi omi amu ni araiye wi eyi si, njẹ kini nwọn yio ti wi si mi o! Ngo ba ọ lọ ide ọrun naa ki ng tilẹ lọ ifi tirẹ yi kọgbọn de wọn." Bẹẹni Esu pojuda biri, o gbe ẹru atori kuro lori Ọrunmla, o ni ki o maa nso on mba a lọ de ọrun naa: awọn mejeeji si jumọ nlọ. Bi nwọn ti yọ sode ọrun, ti Esu fojukan awọn agbalagba ọmọ araiye tọsè si ẹnu-ọwa Ọlọrun nreti Ọrunmla, inu bi i, o gbe ẹru atori naa lọ titi de iwaju Olodumare, o sọ ọ kalẹ nibẹ, o fa diẹ yọ ninu rẹ, o si bẹresi wọn ifa lokun-lokun. Ariwo ta lode Ọrun, gbogbo ọmọ araiye nke wipe "Olodumare, jare gba wa o! eni naa ma tun tele-ni wa ode Ọrun wa ipa o!" Olodumare wa iran awọn emese rẹ jade lọ ila Esu niija: nwọn bẹ ẹ ki o dawọduro diẹ ki nwọn le gbọ ẹjọ. Olodumare ni "Họwu Ọrunmla; mo fi awọn ọmọ ti ọ ki o maa ba mi tọju wọn bayi li o si nlo wọn buruku?" Ọrunmla dahun o ni "Emi kọ, Esu ni; bi o ti nse wọn laiye gaan naa ni Ẹ kuku nri i yi o!" Esu fo sode kerekete o kọju si awọn ọmọ ariaye, o ni "Eese? Ọrunmla ti o nfa nyin laiye yio ti nyin ifa lọrun bi?" Ayaani oo ri i.– "Ẹniti o ba fa-ni laiye ti o si fa-ni lọrun ki a maa pe e ni Ifa" Atijọnaa ni Olodumare ti sọfin pe ki Ọrunmla mase tun mu Esu lẹhin wa sọrun mọ, ati pe titi aiye ni ki Ọrunmla maa fi oju ara rẹ tun aiye se o. Bẹẹli Ọlọrun si tun ko gbogbo araiye bẹ Ọrunmla ki o maa lọ ba On tọju wọn nile aiye.

**40.** "Layimiká l'awo Oré, Erè l'awo àbata, Gbọdunro-"gbọdunfọ l'awo òtuuru:–awọn l'o dífa fun Ọrunmla nijọ ti o "gbó gbó gbó ti a nlọ ròhin lọrun * pe arán li o ku tí o nṣe, "kò sí ire kan ti Ọrunmla tun le ṣe nile aiye mọ. A ní ki o rú "igba màriwo ọpẹ ton t'igba orubu ẹfun ki bẹẹ-bẹẹ le kà aiye. "Ọrunmla gbọ, o rú; bẹẹ-bẹẹ ka aiye."—

Ninu awọn ẹsẹ-ifá ti a kà wọnyi, o daju pe ipilẹ-èro ti mbẹ li ọkan awọn baba wa ni pe a kò gbọdọ yẹ Ọrunmla ni ipo aiye yio bajẹ; bẹẹni on tikalarè kì yio sípò pada lai. Nitorina ní nwọn ṣe nkì i ní "Ọl'ọwa aiyèré."

"Opókí, A-mú-idẹ-ṣ'oju."

Itumọ rè ti o fi njẹ "Opóki" faramọ apẹẹrẹ bi awọn babalawo ti imaa kó iikin lọwọ òsì, tí wọn si ímaa fi ọwọ ọtún lu u nigbati nwọn ba ndá Ifá wọn. Nitori eyi ni a ṣe nsọ ọ li ọrọ pe "O kó Ifá naa o dà a 'pókí;' e.n. pe ẹniti ndá a kò fura odu ti Ifá yio hu, o ndà a bi ẹniti nfi i ṣire, ṣugbọn nigbati a dá a 'póki' bẹe, ti odu lile ba hu soju ọpọn, a di èru jẹnjẹn sara ati ẹniti o dá a ati ẹniti a nda a fun: eyi ni njẹ "a-mu-idẹ-ṣ'oju."

Oju idẹ yi ni Ọrunmla ikàn mọri nigbati yio ba bá awọn ọta rè jà. Awọn babalawo rò pe Ọrunmla ní oju tí ibanilẹru bayi nitoripe (1) on paapaa jẹ Ekun; tabi nitoripe (2) on nikan ni íba ẹkun fọjúrinjú, tí ísi ímu u ní ìjakaadì.

---

40 *Nigbati Olodumare gburo yi, O yan ikọ to Ọrunmla wa wipe bi o ba gbo to bi nwon ti rohin fun On ni, o ma to ibọwa sọrun o! Ọrunmla ti rubọ ki ikọ Olodumare to ide, a fọ awọn orubu ẹfun wọnni kunna, a ya awọn mariwo wọnni wẹwẹ a si tẹ wọn bọ inu ẹfun patapata, a gbe wọn kọ kaakiri si ẹnu ọna ati iloro abawọle Ọrunmla, tobeẹ ti ẹfun nti ibẹ ku-bo gbogbo ẹniti nwọle ati ẹniti njade lara. Nigbati awọn ikọ Olodumare de nwọn jisẹ, Ọrunmla ni ki nwọn joko na ki on ransẹ si tọmọdetagba ilu ki nwọn wa ba on gbọ isẹ Olodumare. Nigbati gbogbo ode aafin Ọrunmla kun tan, Ọrunmla ni ki awọn ikọ naa jade wa ijisẹ. Nwọn jisẹ tan ni ọkan ninu ọmọ Ọrunmla bọ sode, oni "Kili ẹ ti wi nla? Enyin naa ko ri ara nyin ndaan?" Bẹẹni ẹnu ya awọn ikọ naa lati ri ati ara wọn tikalawọn ati ti gbogbo enia nfun ruru. Bẹẹni nwọn si foribalẹ fun Ọrunmla, nwọn ki i titi titi, nwọn ni "Njẹ a o pada lọ jisẹ fun Olodumare pe, bẹẹ-bẹẹ ni gbogbo aiye ma ri o!"

(1). On paapaa jẹ Ẹkun.—

**41.** "Ọkanran-meji li a dá f'Ọrunmla ti a si bu fun gbo-"gbo Irunmalẹ nijọ ti gbogbo wọn mbọwa sinu ile aiye ti nwọn "njija "tani yio ṣ'agba nigbati a ba de ọhun," ti a ní ki gbogbo "wọn tilẹ ṣì duro* rubọ ná ki nwọn le de ile aiye rára. Ekére-"gbe kan, àjiiwọn kan ati ẹgbaa owo funfun li ẹbọ. Ọrunmla "nikan li o gbọ ti o duro rubọ ninu gbogbo wọn."—Ọkanran-meji.

(2). On nikan ni íbá ẹkun fojúrinjú, ti ísì imú u ni ìjakadì.

**42.** "A-bẹrẹ-t'ile-lọ-s'oko, A-d'oko-má-bẹrẹ,, A-rooguro "t'oko-wale, awọn meteẹta ni nṣọmọ-awo Ọrunmla*nijọ ti yio "fi wọn sile lọ s'ajo, ti o kìlọ ki nwọn má má ṣe ọpọn poro lẹhin "on ki Ọlọfin ma baa pe wọn l'ífa o!"—Ikaa-'Fu.

---

*Kaka ti awọn Irunmalẹ iba duro rubọ, nwọn ni bi awọn ba de inu aiye awọn yio rubọ nibẹ: olukuluku wọn si nsare ki on le kọtẹte de aiye, ki a le maa pe on li agba. Sugbọn ẹkun nlanla kan ti lọ iba sọna de wọn, bi nwọn si ti nyọ si i lọwọ lọkọọkan bẹẹli o nfo-mọ wọn ti o si mpa wọn jẹ titi o fi pa gbogbo wọn jẹ tan. Ọrunmla duro pẹ li ọrun o fọkanbalẹ rubọ rẹ tan rere ki o to idide. Bi o ti kusaata ibiti ẹkun naa ba si, ojo giiri de o le ẹkun kuro lọna, Ọrunmla kọja. Nigbati ojo da, ẹkun pada wa soju ọna o gboorun Ọrunmla o si yara nlepa rẹ bọwa wọ inu ile aiye, o si ba Ọrunmla ni igboro ki o to ide ibuwọ rẹ. Ṣugbọn bi o ti fo fẹrẹ lati bo Ọrunmla mọlẹ; Ọrunmla so ajiiwọn si i o si fi yi i kitikiti; o gbe e de o si ru u wọle: nje riri ti a oo kọ ri Ọrunmla lode aiye t'on t'aaye ẹkun li a ri, t'on ti aaye ẹkun li a si fi wọ soju ile kannaa tobẹe ti ile Ọrunmla di ile ẹkun ti o li ẹru nigbanaa fun gbogbo ọmọ araiye: awọn ọmọ araiye a si maa fi da ajuuwe pe "Nibo ni o nlọ? "Mo nlọ si ile Ẹkun " e.n. ile Ọrunmla. Bẹẹ bẹẹ ni "ẹkun di orukọ Ọrunmla tobẹẹ ti a fi nki i ni ""A–mu-ide-s'oju, Ekan ko jẹk'Ẹkun hora;" nitori nigbati o nru ẹkun naa bọ, eyini nfi eekan ha a lori titi o fi sọ ọ kalẹ, apa awọn eekan ẹkun naa ni mbẹ lori Ikin titi di oni ni. Ẹkun naa yi ni Ọrunmla kọ pa bọ ori rẹ ninu ile aiye.

*Awọn ọmọ-awo Ọrunmla mọ pe o lọ s'ajo tan, nwọn ni ọgbọn kini Ọrunmla gbọn si wọn yi? – kini ki awọn o ha maa se jẹun titi yio fi bọ nigbati awọn ko gbọdọ sẹ ọpọn poro; nje ko ma tilẹ fẹ ki Ọlofin mọ pe awọn ti kọ Ifa ja? Bẹeni nwọn bẹrẹsi isẹ ọpọn, awọn enia ntọ wọn wa, nwọn nwo ifa fun wọn, nwọn nyanbọ nwọn si njeru. Nijọ kan nwọn sẹ ọpọn, Ọlofin gbọ o ni "tani nse'fa to bayi nile Ọrunmla nigbati ko si nile?" A ni "awọn ọmọ - awo Ọrunmla ti o fi de'le ni." Ọlọfin ransẹ si wọn pe ki nwọn ma ṣai ji kutu wa iwo ifa fun on li ọla o. Awọn ọmọ-awo yọ, nwọn ni ori awọn jaja san wayi o! Bi nwọn ti de ile Ọlọfin nijọ keji,

Ka Iwe Ifihàn ori I, ẹsẹ 13–15, ki o si ṣe àṣaro rè, iwọ yio si mọ iru ipò ọlá ti awọn baba nla wa gbé Ọrunmla si li ọkan wọn.—"Ati larin ọpa fitila meje yi ẹnikan ti o dabi Ọmọ enia, a wọ ọ li aṣọ ti o kanlè de ẹsẹ rè, a si fi àmure wura dì i li ẹgbẹ. Ori rè ati irun rè dabi ègbọn òwú, o funfun bi òjo-dídì; oju rè si dabi ọwọ iná; Ẹsẹ rè si dabi idẹ darara, bi ẹnipe a sun u ninu ileru: " Fi eyi wé ẹsẹ-ifá 40 ti o sọ bi Ọrunmla ti gbó gbó gbó ti kò kú: ati oriikì rè pelu ti o wipe: "Ọmọ Ọṣọ pa'-lẹ-mọwọ-pa'dẹ-mẹsẹ o mbeere àtẹpaa oje."

---

nwọn ko Ifa Ọlọfin nwọn da a poki a ri Ikaa-Fu o fọbi iku warawara. Ẹru ba wọn nwọn ni "Haa! bi a ba wipe ki Ọlọfin maa ku, afi bi a mu ekun kan laaye wa ipa si Ifa Ọlọfin." Ọlọfin gbọ aajo mu u, o tilẹkun mọ awọn ọmọ-awo Ọrunmla s'idi Ifa rè, o bọ sode lọ iran gbogbo ọkọnrin ilu rè da sẹhin odi ki nwọn maa lọ imu aaye ẹkun kan fun on wa ki on fi yẹ iku kuro lori on. Gbogbo ilu ni "Haa! tabi Ọlọfin nfẹ ipa gbogbo wa ni?" Nwọn bẹrẹsi iseepè sọ ẹniti o yan iru ẹbọ buruku bẹẹ fun u. Ṣugbọn Ọlọfin le gbogbo wọn s'oko, beni nwọn nwa ekun kiri, nwọn si ka ọkan mọ'ko, o mpa wọn sọhun; ko ṣe imu laaye, beeni nwọn ko gbọdọ pa a. Bi ohun nwọnyi ti nse lọwọ, Ọrunmla bọ ajo o gbọ idi rè lẹnu Ọlọfin. Orunmla yara ko iporun rè o da a, ohun ti on le se? a ni ki o ru aja kan, obukọ kan, ajiiwọn kan pelu ọtalegbẹta: Ọrunmla gbọ o ru, o f'ori le oko ekun. Bi o ti de ibẹ, ẹkun yọ gọlọ si i; sugbọn Orunmla sọ ajiiwọn si i o fi yi i kitikiti o di i ru wale laaye. Beeni Ọlọfin yọ, o rawọ si Ọrunmla pe ko si ọkọnrin bii rè laiye; o si paṣẹ ki a gbé ẹgbaa mọkanlaa ati ewurẹ kan fun u. Nigbati Ọrunmla pada de ile, awọn Pètẹbi bẹrẹsi ilu, nwọn njo, nwọn si nkọrin ki i bayi pe:–

Oluwa mi d'ẹkun, Eran l'ẹkun ijẹ;
Ọrunmla d'ẹkun, Ẹran l'ẹkun ije:
Iji l'ẹkun, Eran l'ẹkun ijẹ:
'Fa da-ṣe, Eran l'ẹkun ijẹ:
'Fa la-ṣe, Eran l'ẹkun ijẹ.

Ba t'ọtun jẹ, Eran l'ẹkun ijẹ:
Ba t'osi je, Eran l'ẹkun ijẹ:
E maa k'ẹran bo o, Ẹran l'ẹkun ijẹ;
Apa tan ẹsẹ tan o, Ẹran l'ẹkun ijẹ:
Apètèbi sè e jẹ, Eran l'ẹkun ijẹ:
Gbe'le-gbe'na, gb'Eriwo; Eran l'ẹkun ijẹ

# ORI V

"Oluwa mi igbo, Iku dudu atẹwọ;
Ọrọ, aj'epo ma pọn: Oluwa mi atoobajaiye!
Ọrọ, ab'iku-j'igbo."

Ọrọ yi "igbo" ninu ede, jẹ ọrọ ti a imaa fi ṣe apẹẹrẹ iwọjọpọ ipa ati agbara ninu ẹnikẹni tabi ohunkohun. Ninu ọrọ naa a nṣe iranti ipá, agbara, ẹ̀ru ati titobi lẹsẹkannaa laiya wọn sọtọọtọ. Njẹ ohunkohun ti igbo-ni delẹdelẹ tabi tí ímì-ni li àmikanlẹ, tabi ti íbà-ni lẹru li àbatàn li a mpè ni "Igbo."

"Ogun Igbo" li ogun ti o le, ti o si banilẹru gidigidi. "Arun Igbo" li arun ti o le ti o si banilẹru gidigidi. Iroko "Igbo" li ìròkò ti o tobi jọjọ.

Njẹ nigbati awọn baba-nla wa nki Ọrunmla ni "Igbo tabi Ọṣìn-ìgbo, itumọ rẹ̀ ni pe nwọn jẹwọ rẹ̀ li Ọba ti o tobi jọjọ ni ipa, agbara ati ẹ̀ru.

Eyi ni itumọ rẹ̀ pẹlu ti nwọn fi ki i li "Iku dudu atẹwọ";– nitoripe nwọn gbagbọ pe ẹniti o ko ikin wọnni sọwọ ti o si ndà a ndàn ẹniti o ni iku wò nigbagbogbo: ati pe latinu iikiin wọnni ni iku ti nfò-lu ẹnikẹni ti Ọrunmla nfẹ ípa.

**43.** "Akàheregbedifa ọmọ–awo Ọrunmla; Akànrigidifa "ọmọ–awo Ọrunmla, Adùbùlẹ̀difa ọmọ–awo Ọrunmla: awọn "mẹtẹẹta ni nṣ' ọmọ–awo Ọrunmla *nijọ ti o rán wọn lọ sinu "aiye ti nwọn d'ọhun tán ti nwọn kò beere rẹ̀ mọ."–Otúraoríkọ.

---

*Nijọ ti Ọrunmla nlọ bẹ awọn ọmọ-awo rẹ wọnyi wo, o ji kutu, o ni ki a de on mọ apere ki a ru on lọ iba eyi ekini; a ṣe bẹ, a si ba Akaheregbe-difa nibiti o té Ifa si, a sọ apere kalẹ a ki i, a ni baba rè ni ki a gbé apere yi fun u o. Akaheregbedifa posé sarara o ni nibo ni on tun ni baba

Ninu itan ti mbẹ labẹ ẹsẹ 43, a ri pe Akaheregbedifa ati Akaanrigidifa tikalawọn pe Ifa ti yio lọ wọn lọrun pa. Eyi li o jẹ ki awọn baba-nla wa maa pe Ọrunmla ni "Ikú dudu àtẹwọ." Nitorinaa bi Otúraoríko bá fù soju ọpọn, babalawo a yara fi ọwọ mejeeji gbé ọpọn naa soke ni ìjẹwọ ọpẹ ara-rè fun Ọrunmla ki o ma ba a kú warawara. Agbara yíya-lù enia pa ti a gbagbọ mọ Ọrunmla on li awọn baba-nla wa ṣe nkì i ní "Ọrọ."

### "Ọrọ."

Itumọ ède yi—"Ọrọ," ni ilẹ wa jinlẹ jọjọ. Awọn baba-nla wa gbagbọ pe olukuluku ohun ti a le fi oju rí ti a si le dìmú laiye yi, li o jẹ ibùgbé tabi ile fun awọn ohun miran ti a ko le fi oju rí, ti a kò si le dìmú; ṣugbọn tí wíwà wọn daniloju gbamgba laísì ani-ani: Igi, okuta, ilẹ̀, omi, òke, ọgbun, odò, ẹranko, enia ati ohun ainiye miran ti a kò le kà, gbogbo wọn li ó ní olùgbé kọọkan ti a kò le fojuri, ti a kò si le dìmú.

---

kan si? Bi o ti fọ̀ bayi tan, bẹẹni Ọrunmla fo jade si i latinu apere o si bi i leere pe "Ifa kini o da sọpọn?" O dahun wipe "Oturaoriko ni." Bi o si ti wi bayi tan, ọrun rẹ̀ yi sẹhin o si ku. Ọrunmla tun bọ́ sinu apere a de e mọ́ ọ o di ilu ibiti Akaanrigidifa wa, a gbe e de ọdọ rẹ̀ o tun ṣe si eleyiini bi ti isaaju. Ṣugbọn nigbati o de ọdọ Adubulẹdifa ti o bi i pe "Ifa kini o da sọpọn?" O dahun o ni "Baba mi, ng ko ma mọ Ifa naa o! titè ni mo kan tẹ̀ ẹ soju ọpọn sa o." O yara gbe ọpọn soke si Ọrunmla ki o ba on wo o. Nigbanaa ni Ọrunmla wipe "Iwọ ti o jẹwọ ope tirẹ fun mi yi ni iṣe ọmọ mi nitootọ; wa nisisiyi ki ng ran ọ s'Ifẹ̀ Oyẹlagbo; sọ fun wọn lọhun pe iku de si gbogbo ọmọ wẹẹrẹ ibẹ, oromọ adiẹ kọọkan pẹlu ookanlerugba l'ẹbọ. Adubulẹdifa se bi a ti ran a, a gba a gbọ́ n'Ile Ifẹ, o si ko gbogbo oromọ adiẹ ati owo wa jiṣe fun Ọrunmla. O tun di amọ̀dun, Ọrunmla tun ran Adubulẹdifa s'Ifẹ ki o lọ wi fun wọn pe "Iku de si gbogbo igiripa Ifẹ o, obukọ kọọkan, ọ̀talẹlẹgbẹta l'ẹbọ." Adubulẹdifa se bi a ti ran a, a gba a gbọ ni'Ile Ifẹ; o si ko gbogbo obukọ ati owo wa jiṣẹ fun Ọrunmla. O tun di ọdun 'kẹta, Ọrunmla tun ran Adubulẹdifa s'Ife ki o lọ sọ fun wọn pe "Iku de si gbogbo arugbo Ifẹ o, agutan kọọkan, ọgbọkanla l'ẹbọ." Adubulẹdifa ṣe bi a ti ran a, a gba a gbọ n'Ile Ifẹ, o si ko gbogbo agutan ati owo naa wa jisẹ fun Ọrunmla. Nigbayi ni Ọrunmla wa fi aṣẹ fun Adubulẹdifa pe "Lati oni lọ, bi mo ba mu ọwọ rin ẹnikẹni lara ti otutu ba dabo o, ti nwọn ba sare wa sọdọ rẹ, wi fun oluwarẹ, ki o lọ mu ohun gbogbo mejimeji wa ki o wa igba ọ. Lati oni lọ, emi paapaa ko ni ohun ifọ mọ̀, iwọ ni ki o maa fọhun fun mi." Ayaani oo ri i, babalawo mpaṣẹ ki alaisan wa igba Ifa.

Iwa aiṣe-írí ati aiṣe-idìmú yi ni Afẹ̀ìrí ati Amúbọ tọka si. Awọn ẹda airí ati aigbámú nwọnyi li awọn baba wa imaa pè ni "Oníle" ninu isọrọ wọn ti nwọn imaa wipe ẹnikan "bá Oníle nile." Awọn onile nwọnyi li a si mpè ni "Ọrọ" ninu ede ìsin. Ẹru ati ọwọ nlanla ni nwọn si imaa fi pe "Ọrọ" ninu ìsin ìbọriṣa.

Ni pipè Orúnmla ni "Oro," o yẹ ki a pada lọ íwò ohun ti a ti wi niti ipò ti awọn baba-nla wa tò o mọ li ẹ̀gbẹ́ Olodumare:– **Iwe I.**, ewe 16–20.

**44.** "Bi igi ti tó bẹẹ kọ li ọrọ inu rè ito:– a dá a fun "Gbẹnàgbẹẹrẹ́ ti iṣe ọmọ Ọlọfin nlọ bẹ́ gbogbo igi oko, ti a ni ki "o mà rubọ gbogbo igi yika o; o kọ o ni bi on ti rú ti akọ-igi "o tó. Ojúmọ mọ, Gbẹnàgbẹẹrẹ́ di ibà mọ ìrókò o bẹ́ ẹ, o "di ìbà mọ egungun o bẹ́ ẹ; o wa di ibà mọ Oro* ṣìkẹta gbogbo "wọn ilẹ ṣú o ní bi ojúmọ ti nmọ li ọla li on íbọ Oro."– Owọnrin-meji.

**45.** "Ọrọ fiifii aya On'Ibagbọn, ó p'Al'Ara, ó p"Ajerò, ó "p'ọlọjalọja, o p'eríkinríkin, ó wa íwipe o kan ile Ọrunmla "ni lilọ wàyí o! A gbọ a wa íwi fun Ọrunmla; Ọrunmla kọ́ "ìporún rè o dá a, a ri Ofú-meji, a ni ki ó yara fi ewurẹ kan "rubọ, ki ó yara palẹ̀mọ ki o jade nile fun alejo nla kan ti "mbọwa yi. *Ọrunmla gbọ, o rú; o palẹ̀mọ o yara jade kuro "nile." – Ofú-meji.

---

*Li alẹ́ ọjọ naa, Ọrọ inu Ooro jade nke kiri igbo pe "Iboosi Gbẹ́gbẹẹrẹ o!" Iku gbọ o jade wa ibeere ẹjọ; Ọrọ rojọ pe igi on ni Gbẹnagbẹẹrẹ ọmọ Ọlọfin di iba mọ lalẹ yi ti o si lẹri pe on nji kutu bọwa bẹ lọla. Iku dahun pe Gbẹnagbẹẹrẹ naa ko ha mu ti on kuro bi o? Ọrọ ni "O mu tirẹ kuro." Arun jade o beere bakannaa; Ọrọ ni "O mu tirẹ kuro." Iku on Arun dahun pe "Tiwa kuro ninu rè naa ni un." Nigbanaa ni Ẹburubu Ọran jade wa ibeere; Ọrọ ni on ko gbọ ki Gbẹnagbẹẹrẹ mu tirẹ kuro o: Ẹburubu Ọran ni "nje ko ni iroju bẹ igi na lọla o." Tootọntọ lati ọjọ naa titi iwọn osu mẹta Ẹburubu Ọran nkọlu Gbẹnagbẹẹrẹ titi o fi lọ ida a wo ti awọn babalawo bi i leere pe "ki isaa ise iwọ li o di iba mọ igi Ooro? odindi igiripa obukọ kan pẹlu ẹgbaasan ni ki o yara lọ ifi yẹ iba naa kuro ki Ẹburubu Ọran le tan lọrun rẹ o."

*Bi Ọrunmla ti mbọ sode, o pade Ọrọ fiifii; o yara ya a kọja o nlọ bi ẹnipe ko mọ ọ ri. Ṣugbọn o ke-si Ọrunmla o ni "Nibo ni o nlọ? Iwọ ni mo ntọ-bọ." Ọrunmla dahun wipe on yara nlọ si idalẹ kekere kan lọhunyi ni. Ọrọ dahun oni "Maa lọ, ọdunkọdun ti o ba ti idalẹ dé,

iwọ yio ba mi nile rẹ o." Ọrọ wi bayi tan o ju firi kọja sinu yaara Ọrunmla, o lọ le gongo si ẹhin igba Ifa rẹ̀. Nigbanaa ni Ọrunmla rora yipada wa isọ fun obirin rẹ kansoso ti nsọle de e pe, "Jòwó mo bẹ̀ ọ, mase wọ inu yaaraifa mi lọ titi ngo fi de, nitoriti alejo kan wa nibẹ o: ṣugbọn lojoojumọ titi ngo fi de ni ki o jọwọ maa se onjẹ ẹrinmẹta, ki o maa gbe e ka ẹnuọna yaara naa, ṣugbọn maṣe wọle o." Obirin Ọrunmla pa ilọ naa mọ fun ọjọ mẹta, o si nya a lẹnu lati maa ba igba ofifo nigbati o ba pada wa si ẹnu-ọna yi. Nijọ kẹrin, obirin yi ronu titi o ni "Ẹmọ nla ma ni eyi! iru alejo wo li ọkọ mi mu pamọ sinu yaara, ti njẹun igba mẹta-mẹta ojumọ, ṣugbọn ti emi ko gbọdọ fojukan a yi? Kutukutu ọla ni mo iwọle tọọ lọ." Nijọ keji tooto, bi obirin yi ti silẹkun wọ yaara naa, bẹẹni Ọrọ fiifii kọ mọna kọja lẹgbẹ rẹ̀, o pa a sibẹ, o ba tirẹ lọ. Lojukannaa ara fu Ọrunmla nibi ti o lo lọhun, o yara nsare bọ wale. Bi o ti de wa iba oku obirin rẹ nile, inu rẹ bajẹ jọjọ, o tun nsare pada nlọ ipe Ọrọ naa dehin; ṣugbọn gbogbo awọn ara ile rẹ gba a mu, nwọn mbẹ e ki o mase lọ, ṣugbọn ko fẹ igbọ ipẹ. Nigbanaa ni ẹranla ile Ọrunmla tọ ọ wa o ni "bi nwọn ba bẹ ọ ki o gbọ ipẹ, mo nlọ ipe Ọrọ naa pada wa ifun ọ. Ẹranla Ọrunmla sare titi lọ iba Ọrọ bi o ti nfẹ ikọja odo, o si nkọrin pe Ọrọ bayi:–

"Ọrọ fiifii ẹẹn-un; Ọrọ fiifii en-un:
Sehin wa wo'le o fi silẹ o to maa lọ."

Ọrọ fiifii bojuwo ẹhin o ni "Ha! ẹranla kẹ!" Ẹranla ni "ko si haa kan, bi o ba ni ipada ki o pada kalọ, ọrọ tirẹ ko to temi." Ọrọ fiifii dahun o ni "kini iwọ ẹranla ti nṣe ọrọ tirẹ?" Ẹranla ni "bi mo ba bimọ loni, a maa dide duro loni." Ọrọ fiifii ni "Siọ, iyẹn ha li a mpe li ọrọ i?" Bẹẹni Ọrọ fiifii ko si ba ẹranla pada wa. Ọrunmla tun binu bi ti isaaju titi ẹṣin ile Ọrunmla sare lọ fun u. Ṣugbọn ẹṣin ko to imu Ọrọ fiifii pada; nitori nigbati o bi ẹṣin leere pe kini o ti nṣe ọrọ tirẹ, o dahun pe bi on ba bimọ loni, ọmọ naa a si maa sare tẹle on kiri ode loni na. Eyi ko kun Ọrọ fiifii loju, bẹni ẹṣin sare pada lasan. Ọrunmla tun binu titi agbebọ adiẹ ti o waba ẹyin mẹwa nile Ọrunmla fi wipe on yio sare lọ mu Ọrọ fiifii wa fun u. Nigbati adiẹ kọrin si Ọrọ, Ọrọ bojuwẹhin o ni "Haa! adiẹ kẹ!" Adiẹ ni "ko si haa! kan, bi o ba ni ipada ki o pada kalọ, Ọrọ tirẹ ko to temi." Ọrọ fiifii dahun o ni "kini iwọ adiẹ ti nṣe ọrọ tirẹ?" Adiẹ dahun pe on ko le duro maa to bẹẹrẹrẹ, oju nkan on nitori oyun on wa nile, oyi yio fẹ si i bi on ba pé ju. Eyi li o wa ika Ọrọ fiifii lara, o ni on yio pada wayi ki on lọ wo oyun ti mbẹ nile yi: o si pada mba adiẹ bọ. Nwọn rin diẹ, nwọn ba ẹja kan loju ọna; Ọrọ bi adiẹ leere pe "kili eyi ti ijẹ?" Adiẹ ni on ko mọ: Ọrọ mu ẹja naa fun adiẹ bọni. Nwọn tun lọ die si i nwọn tun ba ẹja kan loju ọna ; Ọrọ tun beere bi ti iṣaju, adiẹ dahun pe on ko mọ ọ: Ọrọ si dahun pe "Sebi iwọ wipe o gbọn? iwọ ko mọ pe ẹja Ọrọ (arọ) li eyi ijẹ? iwọ ko mọ pe ẹja yi li Ọrọ itẹ? nitorina yara mu ẹja mejeeji sare tọ Ọrunmla lọ, ki o fifun u ki o fi i bọ iporun rẹ ki ng to ide o. Adiẹ se bẹẹ, Ọrunmla nfi ẹja-ọrọ (arọ) wọnyi bọ iporun rẹ lọwọ nigbati Ọrọ fiifii wọle de, o wo Ọrunmla titi pe ko sọrọ buburu kan bi ẹniti o ti barajẹ; nitorinaa o bi i lere pe eetiṣe ti o fi pe on pada? Ọrunmla dahun wipe "Obirin mi ti o ku yi ni mo bẹ ọ ki o jare wa ji i dide." Ọrọ si ba a ji obirin naa dide tan o ni ki Ọrunmla jade wa iwo iṣẹ ti on iṣe wayi o–. O mu ọpa ọrẹrẹ ọwọ rẹ o fi gun ilẹ nibi ekini o ni ki Ọrunmla lọ fa a tu, Ọrunmla fa a tu igba ọkẹ owo jade nibẹ: Ọrọ tun se bẹẹ nibi ekeji, Ọrunmla fa a tu, igba wundia tọọwọ jade nibẹ: Ọrọ tun ṣe bee nibi ẹkẹta,

Ninu ìtan ti mbẹ labẹ ẹsẹ 45, a ri pe (1) Ọrọ fiifii jẹ ẹni ti o li ẹru jọjọ, ṣugbọn sibẹ (2) Olukuluku awọn ẹranko li o ni ọrọ tirẹ, ṣugbọn sibẹ Ọrọ fiifii gbọna ju gbogbo wọn lọ tobẹẹ ti (3) Ọrunmla tikalarẹ bẹru Ọrọ fiifii o si mparamọ búrubúru niwaju rẹ. Njẹ kini Ọrọ fiifii yi jẹ?

*i.* Ọrọ fiifii yi jẹ Ọwun.

Gẹgẹ bi a ti ri ninu ìtan Gbẹnàgbẹẹre ni tí o di ìba mọ igi Ọrọ ti o si mpete ati-bẹ ẹ, ṣugbọn ti ọran èburubú gbogbo ndide sí i lati dí i lọna titi o fi wadi rẹ mọ pe o kù diẹ ki on lọ ítẹ ìkere iku ti ibá pa on: (ka ẹsẹ 44). A rí apẹẹrẹ iru Ọwun bayi ninu itan Fárao ti ó ṣeeṣi mú Sara iṣ'aya. Genes. xii. 17; ati Abimeleki ti o ṣe bẹẹ pẹlu. Genes. xx. 3, 18. Li èdè ilẹ wa a le wipe Ọrọ lu Farao naa on Abimeleki naa tán diẹ l'o kù; nitori nwọn nlọ ijẹ Ọwun. Ka ẹsẹ-ifá yi.–

**46.** "Ẹsẹ kan omi, ẹsẹ kan òkiti;– a da a fun Laaṣọní "ọmọ Orè l'Otùn nigbati o wá loko igbàmù-aayè, nwọn ni 'ẹtì "kan ọrùn rẹ yi, ọduun-ní ni o yio dá a: rubọ ìgiripá obukọ kan "pẹlu àdá ọwọ rẹ.' Laaṣọní gbọ, o rú. A ní ki o lọ dá "ẹtì kuro lọrùn ọpẹ kan ti mbẹ l'odo oko rẹ.* Laaṣọní "tọwọ bọ àdá o lọ dá ẹti nù lọrùn ọpẹ naa patapata."–Irẹtẹ-'Túra.

---

Ọrunmla fa a tu, igba ẹrukunrin ati ẹrubirin tọwọ jade nibẹ. Ọrọ ni ki Ọrunmla maa ko wọn sile, – on fi gbogbo wọn fun u nitori on kiyesi pe ko baraje: o ni "nitori eyi li a ṣe wipe ki enia rọju ọran kan ki o ba le ni igba aya; njẹ igba aya ti o ni yi ko ha san ju ọkansoṣo i?" Ọrunmla dupẹ tan, o nsin ọrọ bọ sode ni agbebọ adiẹ naa han ganranran lori ẹyin rẹ lenu iloro. Ọrunmla dahun o ni "ọpẹlọpẹ adiẹ mi yi l'o mu ọ pada wa fun mi!" Nigbanaa ni Ọrọ dahun oni "bi o ko ba yara gbe adiẹ naa tont' ẹyin rẹ mẹweewa lọ ibọ iporun rẹ, amọbi ile rẹ ngbona ṣọọṣọọ." Ọrunmla si yara ṣe bẹẹ.

*Li ọdun naa ni ọpẹ ti a da-nu yi la'di o si so; Laaṣoni gbe igba si i o gun u d'ori lati kọ ẹyin : ṣugbọn bi o ti d'oke tan ti o nwo yika, o ri ọkan ninu awọn olori ti iṣe anaasin ọba kọja wa iwọnu igbo tont'igba kekere kan lọwọ. Laaṣoni ṣọ obirin yi titi o fi lọ ifi igba yi pamọ sinu okiti ọgan kan ninu igbo naa; o si ṣọ ọ titi o fi pada lọ sile rẹ. Laaṣoni ko le kọ ẹyin mọ, o yara sọkalẹ lọ wo kini obirin naa gbe sinu okiti ọgan, ẹnu si ya a lati ri aaye ọmọ titun kan ninu rẹ. Laaṣoni gbe ọmọ naa lọ ififun ọba lalẹ ọjọ naa pe on ri i he ninu okiti ọgan kan n'igbo. Ọba gba ọmọ yi, o si fi i si

ii. Ọrọ fiifii yi jẹ Ọpá-àrèku tabi Ìkere ti a ítẹ̀ ré ọpá. Iru ọpá-àrèku bẹẹ ni Erì ati Onáni tẹ̀ tí Oluwa fi pa wọn.– Genes. 38, 7–10.

Irú ọkannaa ni ọkọnrin nì tẹ̀ ti kìniún fi pa a nitoriti o kọ lati lù wolii nì.– i Ọba. xx. 35–36.

Irú ọkannaa ni Bẹlṣassari ọba awọn ara Kaldea tẹ̀ ti a si pa a loru ọjọ kannaa – Dan. v. 18–30.

Irú ọkannaa ni Anania pẹlu Safira aya rẹ̀ tẹ̀ ti o mu iku ajọkú bá wọn loojọ kanṣoṣo – Iṣe v. 1–10.

Irú ọkannaa ni Herodu Agrippa Ekíni tẹ̀ ti angẹli Oluwa fi lu u lojukannaa tobẹẹ ti o fi di jijẹ idin. – Iṣe. xii. 21–23.

---

itọju ẹnikan ni ilu keji laijẹ ki ẹnikẹni mọ idi rẹ.

Ṣugbọn, tani ọmọ titun yi?—–Oba yi li o mu arẹwa ọmọbirin kekere kan fun aayo olori rẹ tọju lati iwọn ọdun mẹjọ: (aayo olori tabi olori ninu awọn aya ọba li a maa npe ni Anaaṣin ọba). Anaṣin ọba tọju ọmọde naa titi o fi to ẹni-ọkọ, ṣugbọn ko mu u fun ọba.

Loru ọjọ kan, ijalọ bo ile Anaṣin ọba, Anaṣin ran ọmọbirin yi jade sode pe bi ko ba pa wọn tan ki o mase wọle sun: omidan naa pa pa pa titi ko le pa wọn tan o sun si ẹnu ọna iloro. Oba ntọ Anaṣin rẹ bọ lọganjọ, o ba omidan yi ti o sun si iloro, ko beni-beji o mu u dipo tan, o ba tirẹ pada lọ s'aafin. Losu kẹta nigbati oyun farahan ninu omidan yi, Anaṣin ọba binu nitoripe on paapaa yagan, ko si fẹ ijihin oyun naa fun ọba: kaka bẹẹ o nlo ọmọbirin naa ni ilokulo, o si ngbiro ohun ti on yio ṣe nigbati o ba bimọ naa.

Kẹrẹkẹrẹ, oṣu kẹsan pe, omidan naa bimọkọnrin: Anaṣin tilẹkun mọ ọ, o f'aṣọ bo o loju, o yara gbe ọmọ titun naa sinu igba ademu, o si fi ọlọ -osun dipo sabẹ omidan naa. Ọmọ titun naa ni Anaṣin ọba gbe lọ ipamọ sinu okiti ọgan. Ọba beere titi lọwọ Anaṣin rẹ, ṣugbọn o nwi fun u pe ọlọ-osun ni omidan naa bi. Anaṣin ọba yi ti nhu oniruuru iwa ika bayi pé ti ọba si nsọ eyi ti yio wọ lati fi mu u: nitori eyi ni ọba ṣe gbe ọmọtitun yi lọ ipamọ silu keji laisọ fun ẹnikẹni.

Ṣugbọn li ọdun mẹrin lẹhin eyi, ọba ransẹ ki olutọju ọmọ naa gbe e wa iri on, o si se ase nlanla ti o pe gbogbo awọn ijoye rẹ si. Nigbati ilu pejọ, ọba paṣẹ ki a ro omidan naa li aṣọ akisa, ṣugbọn a ko idẹ si ọmọ rẹ lọwọ ati lẹsẹ ki a si ṣe e lọọsọ gidigidi, ki a wa igbe e si aarin agbo ki a si jẹ ki ọmọ naa maa rin agbo bọ. A ṣe bẹẹ, ẹnu si ya gbogbo ilu lati ri ọmọ naa nla agbo lọ lai-ya sọtun tabi soosin bikoṣe sọdọ ọba. Bakannaa ni ọmọ naa lọ taara sọdọ omidan alakisa yi nigbati a gbe e lọ idanwo laarin agbo awọn olori ọba.

Lọjọ na gaan li a sọ itumọ ọmọ naa fun awọn ijoye ilu, a si paṣẹ ki a fa Anaṣin buburu yi lọ ipa, ki a si fi omidan yi dipo rẹ ni ile ọba. Ọmọkọnrin kanṣoṣo yi li o si jẹ pe a bi fun ọba, on li o si wa ijọba nigbati ọba ku.

Compare 46 with Queen Esther's story

Nigbati a ba ro itan awon apeere ti a mu wonyi jinle, a oo kiyesi i pe kò si enikan ninu awon maraarun ti a ka wonni ti o fura pe eti bèbè iku gangan li on wà; bi beeko, nwon kì bá tí şíşe ikehin naa ti o mu iku ojiji ba won.

Aìní-ìmotele, tabi ifarasin, ti opá-àréku yi fun enia li awon baba - nla wa ndárò rè ninu owe lailai yi pe.–

"Abère kò mo aso a-rán -gbèhin,
Agbere kò mo eni à-fé-pekun!"

|| Note

Ero yi li o si je ki awon babalawo so ese-ifa ti a ka ninu awon ese 46 ati 47 "ni Esè kan." Oruko naa si wo jojo; nigbati a ba ro o jinlè otito naa ko le şaihan sí-ni pe esè kan ni mbe laarin elese ati iku. Ka ese-ifa yi ki o si fi-we awon iwe mimo ti o tèlé e.—

**47.** " 'Esè kan;' – Ikere aya èku, Irawé dùduudù aya "ofin, Ikoko aya omi: enit' o bá m'owo kan ikeke èkú nwaaja "èkú, enit' o ba m'ese lé ìrawé ofin nwaaja ofin, enit' o ba m'ese "lé ìkoko omi nwaaja omi:— Orunmla ní enit' o ba gb'ese "lé aya on kò mo pe on nm'ese lé ona orun i?" – Irete–'Túra.

Fi eyi si ègbé Psalmu vii, 11-13.– "Olorun li Onidajo, Olorun si mbinu si enia buburu lojoojumo; Bi on kò ba yipada yio si pon ida rè mú: o ti fa orun rè le ná, o ti mura rè sile. O si ti pèse elo iku sile fun u; o ti se awon ofà rè ni oninà.

iii. Oro fiifii yi jè Aşe ti o jade lo fun iparun ti a ko si le yí i pada mo.

Irú Ase bee ti ki íyipada li o jade ti Hofni ati Fínehasi fi kú.— i Sam. 3, 14.

Irú bee naa li o jade ti Goliati fi subu loju ogun.—i Sam. xvii, 45–47.

Irú bee li o jade fun Saulu ti o fi gbé si ogun oke Gilboa.– i Sam. xxviii. 18–19.

Irú bẹẹ li o jade fun Ahabu ti ko fi bọ ogun Ramoti Gileadi. i Ọba xxii, 19–22.

Nigbati a ba ro ìtan awọn apẹẹrẹ ti a mú wọnyi jinlẹ, a oo kiyesi i pe iṣàn ìwa buburu a maa gbá ẹlẹṣẹ lọ titi de ibiti kò sí iyipada mọ ninu aṣẹ iku ti o jade fun ẹsan sori ẹlẹṣẹ. Nigbati iru aṣẹ bẹẹ ba si ti jade, o ya-ni-lẹnu pe kì ígbọ etutu. Ka ẹsẹ-ifa yi ki o si fi i we awọn iwe mimọ ti o tẹle e.

**48.** " 'Eesí 'ún-tù-kàn,'—Ikú pa Eríkiijá; 'Eesí 'ún-tù-"kàn,'– ikú pa Imóloogbè: *kò ku emi ọmọ kekere inu wọn, "ẹbọ mi kò kọ 'rú kò kọ'we ná, ko di ki ng maa lọ kú i?" Iretè–Egútan.

---

*Nigba atijọ, Eṣu, Ọrunmla ati Ajẹ jumọ nṣọrẹ, nwọn si nrin pọ̀. Bi nwọn ti nlọ sọna oko nijọ kan, nwọn gbọ igbe buruku kan bi ti awọn ti nru oku bọ̀, nwọn si yara sa sinu igbo nitoripe eewọ ni fun wọn lati foju-kan oku. Adi awọn ọmọ-iya mẹta kan–Erikija, Imoloogbe ati aburo wọn ti o lọ sọdẹ li o pa odidi agbọnrin kan, ti nwọn tẹ ẹ sori patako kan, nwọn fi aṣọ funfun bo o, ẹnikan ninu wọn gbe e ru nkè bọ bi-ẹnipe fun oku. Bi nwọn ti kọja ibiti Eṣu, Ọrunmla ati Ajẹ sapamọ si, Ajẹ dahun o ni "ẹran ni nwọn ma nru lọ ti nwọn pe li oku yi!" Ṣugbọn awọn ọrẹ rẹ meji iyokun njiyan pe ki ise ẹran. Ajẹ ni bi nwọn ba ba on jiyan, ki nwọn jumọ pada tẹle wọn lọ sile ibiti nwọn ngb'ẹran naa lọ. Nwọn se bẹẹ, nwọn si ran Eṣu wọle lọ iwo o wa. Nje, Eṣu parada di arugbo kẹgẹkẹgẹ, o dè o m'ọwọ le ilẹkun pe on yio wọle fọnna, awọn ọmọ mẹta naa dahun pe aye ko si nitori awọn nṣe nkan lọwọ o. Arugbo pada. Eṣu tun parada di omidan pẹkẹpẹkẹ, o kan 'lẹkun pe on yio wọle fọnna, nwọn tun kọ̀ nwọn ni awọn koi ti raye sè o. Omidan pada. Eṣu tun parada di ọmọ kekere ti o sẹṣẹ nra, o si f'ori silẹkun wọle: nwọn jọwọ rẹ o ri gbogbo ẹran ti nwọn kun silẹ, o si pada lọ isọ fun Ajẹ on Ọrunmla pe ẹran ni nitootọ. O si wa jẹ pe bẹẹ ni awọn ọmọ-iya mẹta nwọnyi ti ima ṣe nigbagbogbo si awọn ara-ile wọn nibẹ.

Nigbanaa ni Ajẹ dahun o ni "ṣe mo ti wi bẹẹ? Nje pipin l'ao pin awọn mẹtẹẹta naa pajẹ: iwọ Ọrunmla, mu ọkan tirẹ, iwọ Eṣu mu tirẹ, eniti ko ba pa tirẹ yio ma kan nkan kẹ! Iwọ Ọrunmla saa ni oninu dindinrin ti ngba gbogbo aiye silẹ."

Ki alẹ to ilẹ lọjọ na otutu aburadi kọlu Erikija, Imọloogbe sare wa ida a wo lọdọ Ọrunmla: Ọrunmla ṣan ọpẹlẹ waa o ni "Haa! Eesiun-tu-kan." e.n. pe "ko si nkan;" sugbọn ki Imologbe to ipada de'le, Erikija ti ku! Nijọ keji ti nwọn kita-kije oku yi tan ni otutu aburadi kọlu Imoloogbe, aburo ẹhin rẹ si sare tọ Ọrunmla, on si dahun bi ti isaaju. Lẹhin ọjọ meje ti oku Imoloogbe, nigbati otutu kọlu aburo wọn yi ni on tikararẹ sare lọ beere lọdọ Ọrunmla; Ọrunmla dahun pe ko si nkan? Nigbanaa ni aburo yi nsọkun bọwa ile nwipe: "Esi un-tu-kan, – iku pa Erikija, Esi un-tu-kan, - iku pa Imoloogbe: ko ku emi ọmọ kekere inu wọn, ẹbọ mi ko kọ'ru ko kọ'we na, ko di ki ng maa lọ ku i?"

vi. Ọrọ fiifii yi jẹ Angẹli Ikú tí Olodumare kì íran jade fun ohun miran bikoṣe fun ati-ré ìkeke ikú lori awọn ti ó j'ọwun.

Angẹli Iku naa yi li a rán jade la Egipti já, ti o si pa gbogbo àkọbi ọmọ ni ilẹ wọn loru kanṣoṣo. Eksod. x, 4; xii, 29.

Angẹli Iku naa yi li a rán jade la Israeli já, ti o si pa ẹgbaa marundilogoji enia ni ọjọ mẹta.– i Kron. xxi; 14–15.

Angẹli Iku naa yi li a rán jade la ibudo-ogun Sennakeribu já, ti o si pa ọkẹ mẹsan enia o lé ẹgbẹẹdọgbọn ninu ogun rẹ loru kanṣoṣo.— ii Ọba xix. 28 ati 35.

**49.** "Opo ile Ọrunmla l'o difa fun Ogún nlọ s'ogun Igbo "Akára, a ní ki ó rú aja kan ki ogun ti o nlọ yi le sàn a. O "gbọ o rú, o d'ọhun o mu obirin kanṣoṣo-le-ligba, o bọ délé o

---

Ninu ohunrérè ẹkun yi li o ko Pẹ̀tẹbi kan lọna ti o bi i leere idi ẹkun, o ko o ro fun u tan ni eleyini beere pe "ẹran kan ti ẹ nyan ni ojumina nyin ni, ẹ ti jẹ ẹ tan bi? yara lọ ko gbogbo rè wa pẹlu ẹru iṣu kan ati iṣa epo kan wa ifi-bẹ Ọrunmla."

Aburo kekere yi yara lọ ko gbogbo rè wa bi Pẹ̀tẹbi ti sọ fun u. Ṣugbọn nigbati Ọrunmla ri nkan wọnyi ti 'Kekere inu wọn' ko wa, o binu; o ni "tani ha yan ẹbọ fun ọ bayi ki o to lọ ko nkan wọnyi wa? Bi o ko ba jẹwọ ng ko jẹ gba wọn." Ọmọ naa si fi ibẹru nlanla jẹwọ gbogbo òran naa. Njẹ inu bi Ọrunmla si Pẹ̀tẹbi naa, o yi wọle fi ọwọ ọtun mu owo aba, o fi ọwọ osi mu t'aṣẹ, o si jade lọ pade Pẹ̀tẹbi na lọna odo, o gegun fun u pe "Lai, ibiti o wa ni ni ki o duro si, ki ladugbo ori rẹ maṣe tun pada de ilẹ mọ' Pẹ̀tẹbi yi ati ladugbo ori rè li o si wa di Tèterẹgun pẹlu eso ori rè.

Ọrunmla pada wale wa ifi kekere-inu wọn pamọ sinu yaara; o se ẹran agbọnrin naa lobè, o fi iṣu guyan, o pe Esu ati Ajé o ni ki nwọn wa ba on jẹ ẹran ti on o: o ni ṣugbọn ajẹpọ ma ni on njẹ ti on o. Nwọn ba a jẹ ẹ tan patapata: sugbọn nijọ keji ni Ọrunmla wẹ Kekere-inu-wọn sode, o si mu u sẹhin lọ ki Esu on Ajẹ Nwọn binu lati ri ọmọ naa, nwon si wipe Ọrunmla dalè wọn: sugbọn Ọrunmla dahun wipe "Se mo ti wi fun nyin tẹlẹ pe ajẹpọ ni mo njẹ temi?"

Fi eyi si ẹgbẹ *i* Sam. *iii*, 12–14 "Li ọjọ naa li emi o mu gbogbo ohun ti mo ti sọ si ile Eli ṣẹ: nigbati mo ba bèrẹ emi yio si se e de opin. Nitoriti emi ti wi fun u pe, emi yio san ẹsan fun ile Eli titi lai, nitori iwa buburu ti on mọ, nitori awọn ọmọ rè ti sọ ara wọn di eni ẹgan, on ko si da wọn lẹkun. Nitorinaa emi ti bura si ile Eli, pe iwa buburu ile Eli li a ki yio fi ẹbọ tabi ọrẹ wẹ-nu lailai."

Ki akiyesi pe a sọ ọrọ wọnyi l'ọdun mẹtadilọgbọn siwaju mimusẹ rè

"mú igba obirin fifun Ọlọfin, o fi ọkan ti o kù ti ó siàn ju ṣe "aya; o tun pada lọ sogun. Ki ogún tó íbọ ni Ọlọfin ranṣe lọ "ímu obirin kanṣoṣo naa ti Ogún fi silẹ tont'oyun ninu, o si fi i "s'aya. A ròhin yi fun Ogún bi o ti mbọ lẹekeji t'on ti ọkanle-"nirinwo ẹrú ti o mú l'ogun, inu bi i o ní on yio pa gbogbo ile "Ọlọfin run, o si nrun ilu yíka nitootọ titi o fi yipada wa íkọlu "Ifẹ Ọọyẹ'lúàgbo paapaa kò mọ pe ìlú Ọlọfin nibiti on naa paa-"paa ti jade lọ ni, o run ilu ku ọgbọn mẹfa ki arugbo obirin kan "ti kò le salọ tó iń ohùn rara kigbe-dàrò si Ogún bayi pe "Gbàjúre-e-e-e-e! Ọkọnrin gogorogo ti ngbojuto íjade!' "Nigbati Ogún gbọ igbe arò yi, o wá ímọ pe on de igboro ibiti "a njubà on, o si tẹ idà rẹ bọ'lẹ, kò tún pa wọn mọ. Idà na "mbẹ titi di oni nibiti Ogún tẹ ẹ bọ n'ile Ifẹ."—Ogùda-'Sẹ.

**50.** "A jẹ, a kò wún ẹlẹrú jẹ; a mu, a kò wún ẹlẹrú mu; "ẹ kò rí i , igbe a se ọsọsọ ẹpa ti a ko wun ẹlẹru jẹ, ti a ko wún "ẹlẹrú mu, * ti ẹlẹrú gún ẹse sọna de-ni i ?—O gbè- 'Wọnrin.

Iru ero bayi ni awọn baba nla wa ní li ọkàn wọn nigba-kugba ti ajakálẹ arun tabi iku ajọkú bá njà ni ilú, nwọn a maa ṣe

---

*Nigba atijọ ni Ile Ifẹ, nigbati ọdun ba jọ, ti gbogbo ilu ba se ase ti nwọn ba si nse ajọyọ odun titun, kiki ọmọ-ibilẹ ni imaa se e, eru ko gbọdọ jade ba wọn ṣe e: eru ki iba wọn je, eru ki iba won mu; awọn ọmọ a se ẹru wọn mole kije nwọn ki si ifun wọn li onje, opọlọpọ ẹru a si maa ku sinu isemọ naa lọdọọdun: awọn ọmọ ro pe nwọn nfi ọna bayi jaiye. Ṣugbọn lehin ọdun pupọ awọn eru nwọnyi peropọ, nwọn gun oro silẹ igbo-malẹ de awọn ọmọ tobee ti opọlọpọ ọmọ ti o farakan oro naa ku lodun naa. Awọn eru si nse bẹẹ lọdọọdun, iku si nja larin awọn ọmọ-ibilẹ Ife gidigidi. Nigbati ilu fẹre run tan ni awọn iyokun ronu, nwọn se ajo lọ beere lọwọ Orunmla ohun ti awọn iba se ti ọdun naa ti nwọn nfẹ ise le san wọn. A ri Ogbewọnri. Orunmla bi wọn leere pe "ọna wo li ẹ ti ngba se ọdun ti ko san nyin?" Nwọn dahun pe awọn a maa se ẹru mọle kije laijẹ laimu, ṣugbọn gbogbo ọmọ-ibilẹ a maa jẹ nwọn a maa mu, nwọn a maa jaiye ọmọ kiri ilu. Nigbanaa ni Orunmla yan obukọ kan ati ẹgbaata aridin li ẹbọ fun wọn, a ni ki nwọn kede yi gbogbo ilu ati igberiko ka pe "T'ẹru-t'ọmọ ni Malẹ pe ki o bọ on l'oduunni o" Ifẹ gbọ, Ife ru: enu si ya awọn eru pe a kede bayi: nwọn si yara mu ẹro lọ buwọn igbo-malẹ naa, tobẹẹ nigbati t'ẹru-t'ọmọ papọ se ọdun naa, nwọn jumọ je, nwọn jumọ mu, iku aburadi ko si ja lodun naa bi ti atẹhinwa. Ayaani o ko ri i, -"A se ọsọsọ ẹpa, a ko wun ẹlẹru je, a ko wun ẹlẹru mu, ẹlẹru ng'ẹsẹ sọna de-ni!"

aniyan lati wadi isise won ti o mu ohun abami bee ba won: nwon ní ìmo yi li okàn pe arun ati iku bee kì ijade lasan bikose fun esan ìsíse kan ti o farasin. Ka awon ese-ifa wonyi.—

**51.** "Nkan wúyewúye labe ìrawé, adifa fun "ojúle "abeesán, **a ní ki ojule abeesán rú agutan kan ati ogbokanlá "ki nwon ma baa yo-kú, ojúle abeesán kò rúbo. Ayaaní- "okookan, èjeejì, e kò rí ojúle abeesán mà yo-kú po!" — Oyekúbì-wòri.

**52.** "O se koko siwaju sasa, ó se ikù sehin : adifa fun "won l'Ife Ooye-ílú-Agbo, a ni ki nwon rú agutan kan, ogbo- "kanlá, nitori ikú de. Nwon s'eti gbonran si ebo nwon se "àrán-ìgbo s'Esù, nwon kò rú, iku de o mpa won n'igba-n'igba: "nwon wa íke to babalawo won wipe 'eyiti e wi mà se o!' "Babalawo ní 'bí e ba fé ki ikú dáworo, èru goke;—ohun "gbogbo di mejimeji!'" — Oyekúbìwori.

**53.** "Oyekúbìwori ni on kì ise Ifá olobirin kan:* o ní on "a-so-ile gbogborogbo-di-ahoro. Nwon ní 'kini a íse ti o kò "tún so ile gbogborogbo dahoro?' O ní 'ewusa meji ati "egbejilelogun ni ebo." — Oyekúbìwori.

Ero yi li o mú awon baba-nla wa maa se aniyàn lati pètutu si agbo-ile kan bi nwon ba kiyesi pe iku njá pipoju ninu re.

**54.** "Agbo-fi–jojo-wolè, adifa fun Oba Adó Ajaniwa "nijo ti ati Lísà ati Jomu **njoko tí i nfowo ko o lorun; a ni "k'Oba Adó rú àgbo kan, egbaata pelu idà kan ti mbe lowo "re ki a se nkan si i fun u, ki o ba le gb'aiya lowo gbogbo ara "ilè rè. Oba Ado gbo, o rú."—Irosu-'Sá.

---

**'Ojule abeesan' - jasi Agbo ile kan ti o ni idile mesan ni kikun.

*Eyini ni pe on ki ise Ifa ti olobirin kansoso ida ti ifi jafara ati-rubo nigbati o ri bi olobirin pupo ti o ko ode aafin gbogborogbo da on, ti ko tete rubo, ti on so ode aafin rè dahoro fun u.

**Nigba atijo, Oba Ado ko niyi loju ara ilè rẹ rara tobee ti awon ijoye rẹ ki iwolẹ fun u, nwon ki iko eruku fun u, awon enia rè ki imu isin odoodun wa ifun u, isé a si ma sé oba loju won. Nigbati iwa yi tubo nwo

**55.** "Enu p'elenu, enu mi mà mà gbà mi là ò:– a dá a "fun Leemíkàn—iwọ mí kàn mi ki ng mí kàn ọ;—a ní ki o rú "obukọ kan ati ọbẹ owọ rè ki o to ilọ soko. O kọ ko rù, o lọ; "ogun ba a nwọn pa a soko, nwọn gbé ori rẹ lọ ípaalè le ikàn "l'oko Ipetu.

"Paaràkọdà, adifa fun Ọlọọbẹdé Ipetu, **a ni ki o rú "obukọ kan ati ọbẹ owọ rẹ ki o tó ilọ soko. O kọ kò rú, o lọ "soko naa dandan."—Otúra-'Bàra.

---

Ado lara, Lisa ati Jomu n'o ba ọba joko lori itẹ rè, nwọn a si maa fọwọkọ ọba lorun laibẹru. Sugbọn nigbati ọba rubọ Irosu-sa tan ti a si se ifa si ida rẹ fun u, o sun loru o ri baba rè nkó o bayi pe "Nijọ miran bi ajọ ba kun tan, fa ida rẹ yọ lojiji ki o bẹ Lisa lori ki o si sọ ọ lu Jọmu li aiya." Oba se bee tootọ gbogbo ilu funka si igbo, o di ibẹru fun wọn lati wa fojukan ọba, nitori nwọn ko mọ eyiti o ku ti yio se. Ninu ibanuje yi gbogbo wọn gbarajọ, nwọn ni awọn yio kuku tọ Olodumare lọ ki O kuku tikalare run wọn lẹekan. Beeni gbogbo wọn forile ọna ọrun. O pẹ die ni nwọn ko ọkọnrin kan nti ọrun bọ: o bi wọn pe kini gbogbo wọn nwọ lọ se lorun bayi? Nwọn ro fun u pe awọn mbinu tọ Olodumare lọ ki O le tikarè pa wọn l'eekan. Okọnrin na beere pe "ẹni melo ni gbogbo nyin?" nwọn dahun pe awọn to ọkẹ mefa enia: Okọnrin naa ni "O mase o! o si ku ọkẹ mẹta enia ki ẹ le to eyiti onibode ọrun nfi rubọ owurọ Olodumare." Bi nwọn ti gbọ eyi, aiya wọn ja, nwọn pẹhinda, nwọn tun funka sinu igbo, nwọn si mpa erin, ẹfọn ati oniruuru ẹran kaakiri nwọn ndi i li ẹru titi olukuluku fi ni ẹru tirè: nwọn si ru gbogbo rè lọ sọdọ Oba Ado.

Nigbati ọba wa wo wọn, o bi wọn pe "kini ẹ tun nfẹ nihin?" ẹru ba wọn, nwọn nwariri, nwọn si dahun pe "nigbati a ronu wa wo a ri pe a koi ti sin ọ lati ọjọ ti o ti jọba; nitorinaa ni a se mu eru-eran wọnyi wa ifun ọ." Oba Ado wipe ki nwọn joko ki on ri wọn, nwọn dahun pe awọn ko ro pe o tọ ki nwọn maa ba ọba joko, nitorina iduro ti awọn wa yi dara to. Atijọnaa ni awọn ara Ado ko ti nfidi balẹ nile ọba wọn titi di oni oloni.

**Ọlọọbẹde Ipetu sisẹ tan o mbọwa ile li alẹ o ya sidi ikan yi lati ji die ka ninu rè. Bi o ti nawọ lati ka ikan naa, beeni o gbọ ori gbigbẹ ti a fi paale lè e nkè wipe "ma fọwọkan a, ma fọwọkan a, tabi o ko ri mi nihin ni?" Eru ba Ọlọọbẹde Ipetu o sare wa ile, o lọ rohin li aafin ọba pe on ri ori gbigbẹ ti nfọhun l'oko loni, ki ọba yan 'nia kalọ wo o. Oba jiyan sugbọn Ọlọọbẹdè tenumọ ọ pe bi ko ba ri bẹẹ ki ọba pa on: ọba sileri ati-fi idaji ijọba rẹ jin Ọlọọbẹde bi ohun naa ba ri bẹe nitootọ. Bayi ni nwọn leri titi gbogbo ilu yan ijoye meji tele Ọlọọbẹdè pe bi ori gbigbẹ ko ba fọhun ki nwọn pa Ọlọọbẹdè sibẹ. Nigbati nwon de idi ikan naa Ọlọọbẹde se titi ori gbigbẹ kọ ko fọhun a si pa Ọlọọbẹde sibẹ. Bi nwọn ti nmura ati-kuro nibẹ, ori gbigbẹ dahun o ni "E ṣeun o, o rọ mi sii-sii-sii." Eru ba wọn nwọn si sare wa iwi nile, nwọn si fi ileri ti i gẹgẹ bi Ọlọọbẹdè ti se nigba tirè: a tun yan enia bi mẹjọ le awọn naa ki o lọ igbọ wa ki o si pa wọn sibẹ bi ohun naa ko ba ri bẹẹ. Nwọn de ọhun nwọn se titi ori gbigbẹ kọ ko fọhun, a si pa awọn meji naa sibẹ; sugbọn bi nwọn ti yipada nlọ,

"Oluwa mi atoobájaiye."

A pe Ọrunmla ni atoobajaiye, nitoripe awọn baba-nla wa gbagbọ pe bi Ọrunmla ba wà lọdọ wọn, tabi bi awọn ba wa lọdọ rẹ nigbagbogbo, kò si ohun buburu kan ti o le bá wọn. Ero yi li o mu wọn maa dì í mọra lọ si ọna àjo, lọ si oju ogun, tabi si ibi ewu miran. Ninu ero wọn yi, ọrun ati ibugbe ọrun jìnna rére si ọkán wọn, nitoripe:

(*i*) Ọrunmla paapaa kò fẹ ní ibugbe tabi ile ọrun: ati pe
(*ii*) Ọrunmla paapaa kò fẹ lati kuro li aiye.

Ka awọn ẹsẹ-ifa wọnyi:—

56. "Ewe ẹmọ ni ilu-'ra wọn pẹlẹmbẹ-pẹlẹmbẹ, ewe "agbagbà ni ilu-'ra-wọn gbàmkọ-gbàmkọ, a-gbọn 'mi ni "íwo'le ẹja, a-p'àjuba ni íwo'le aparò:--a dá a fun Ọrunmla a "nkọle meji silẹ dè e,— ọkan rẹ li aiye, ọkan rẹ li ọrun. "A ni ki o rú obukọ t'o bẹ́ju, pẹlu iyán aisan ati ọbẹ aisan ki a "le wó ile ọrun nù fun u.* Ọrunmla gbọ, o rú; a wó'le ọrun nù fun u."— Ireẹtẹ-meji.

Bawo ni eyi ti yàtọ si ìwa Jesu Kristi tó—ẹniti o sọ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ pe "E maṣe jẹ ki ọkan nyin bajẹ; ẹnyin gba

---

ori gbigbẹ ke si wọn o ni "ẹ ṣeun-seun o, o ṣe mi sii-sii-sii!" Awọn mẹjọ sare wale wa iwi nile. Bayi ni ọran yi ntobi si i titi a nka bi ẹgbẹrun enia ti a ti nlọ ipa sidi ori gbigbẹ ti a fi paale le ikan l'oko Ipetu. Nigbanaa ni awọn agba ilu wa ironu, nwọn sa-tọ Ọrunmla lọ ibeere ohun ti nwọn iba ṣe ki akufa yi le dawọro: Ọrunmla yan ẹbọ fun wọn o si wipe ki nwọn lọ imu ori gbigbẹ naa kuro lori ikan naa, ki nwọn gbe e si posi ki nwọn si sin i tẹyẹ-tẹyẹ, ki nwọn kiita-kiije rẹ. Nwọn si se bẹẹ gẹgẹ, ọran akufa naa si dawọduro.

56* Obukọ ti o bẹ́ju (e.n. pe oju obukọ naa kun fun ipin), ni Ọrunmla fi se ọbẹ ainiru-ainepo olomi sooro, ti o si gun iyan ti o kun fun koko lọpọlọpọ, o si wa awọn adẹtẹ ati ologodo o fi nkan wọnyi ran si awọn ti nkọle dè e li ọrun. Nigbati awọn ti nsiṣẹ ile na ri ohun iwọsi nlanla ti Ọrunmla se si wọn yi, nwọn binu, nwọn gbe onjẹ naa danu, nwọn si wo ile ti nwọn ti nkọ dè e danu tuutuu: Nigbati a pada wa rohin fun Ọrunmla, o nkọrin o si njo bayi pe–

"Mo wo'le ọrun nu mee ku,
Atupuru yẹ, yẹyẹ atupuru."

Olorun gbọ, ẹ si gba mi gbọ pẹlu. Ninu ile Baba mi ọpọlọpọ ibugbe li o wa : ibamaṣepe beẹni, emi iba ti sọ fun nyin. Emi nlọ ípèse aye silẹ fun nyin. Bi emi ba si lọ ípèse aye silẹ fun nyin, emi o si tun pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbe wà, nibẹ li ẹnyin o maa gbé pẹlu." John. xiv. 1–3.

Iru igbagbọ bayi ti o kún fun ìtunu nìnu Kristi li o le mu awọn ọmọ Jesu maa kọrin ti o yàtọ si ti ọmọ Ọrunmla nipa ti ile ọrun wọn bayí pe:

"Daradara ni ile ọrun, Irora on iku kì íde 'bẹ̀;
Orun kò dan tó ile-ìṣọ rẹ̀, Mo nlọ sile ki ng ma kú mọ:
Mo nlọ sile, mo nlọ sile, Mo nlọ sile ki ng má kú mọ
Ki ng ma kú mọ, ki ng ma ku mọ, Mo nlọ sile ki ng má ku mọ"

tabi eyi—

"Mo m'ajo mi pọn soke Sioni, Gbogbo ọna si jẹ Jesu;
Ọnu si mọ siwaju sibẹ si i, Gbogbo ọna si jẹ Jesu;
Jesu! Jesu! Haa gbogbo ọna si jẹ Jesu.
Bi ipin ti èro ti rọrun tó, Gbogbo ọna si jẹ Jesu;
On ni irọrun ti aiye ko ni; Gbogbo ọna si jẹ Jesu.
Jesu! Jesu! Haa, gbogbo ọna si jẹ Jesu.
Jẹk' ìjì gbá-jọ ki wahala nde, Gbogbo ọna si jẹ Jesu;
On ni ilu kan ti oju rẹ̀ mọ; Gbogbo ọna si jẹ Jesu:
Jesu! Jesu! Haa, gbogbo ọna si jẹ Jesu.

**57.** "Baba Orógbo, Baba Oṣùgbó, Ajana Màgbótiyẹtiye, "awọn li o dífa fun Ọrunmla nijọ ti Olodumare ranṣẹ pe "gbogbo irúnmalẹ lode ọrun, O ní ki gbogbo wọn yara gẹṣin "wa fojukan On. Ọrunmla dá, ohun tí on le ṣe ki on má bá "wọn dé ọrun? A rí Ogbèwọnrin.* A ni àgbo kan pẹlu "ẹgbaata l'ẹbọ: a ni ki o má mà gẹṣin, àgbo yi ni ki ó mà "gùn ò! Ọrunmla gbọ, o rú." — Ogbewọnrin.

57 *Ọrunmla gun agbo rẹ̀ yi nitotọ, o kẹhin gbogbo irunmalẹ: ṣugbọn

Awọn apeẹrẹ nwọnyi fihanni pe ni pipe Ọrunmla ni Atoobajaiye, ọrun ati ibugbe ọrun jinna rère si èro awọn baba-nla wa; aiye yi nikan si ni opin aniyan ọkàn wọn. Nję, awọn baba wa ngba Ọrunmla sile wọn, tabi nwọn ngbe e lọ si àjo wọn nitori aabo ti nwọn nreti lọwọ rẹ li aiye yi. Ka awọn ẹsẹ wọnyi:–

**58.** "Ọdọ ji kùtu o ni on nwa ọkọ ọmọran lọ íní, o dé "le odidẹ o bá íkó mbẹ ṣẹkẹṣẹkẹ, o ni on yio ṣ'aya rẹ; odidẹ ní "ki o bọ sile. O d'ijọ keji, o ri odidẹ nf'ẹsẹ mú ẹyìn nílẹ̀ si "ẹnu, oju ti Ọdọ o binu o kó jade. Ọdọ rin síwaju o de 'lé "akukọ, o ní "Akukọ o siansiàn o yẹniyẹni, o mọ ídaja, o mú "ìrerẹ ṣọyin, ngo ṣ'aya rẹ." O ko'gbá sile. Ni kutu ọjọ keji, "akukọ dája. Ọdọ jí o pa ile pa ọna ó gbe iṣa, o re ẹri; bíbọ "ti o ti odo bọ li o bá ti Akukọ ṣu pẹtẹpẹtẹ si gbogbo ile. "Oju ti Ọdọ, Ọdọ binu ko jade.

"Ọdọ mú ogoji mọ aṣọ ró, ó mu ago aasárà mọ aṣọ ró, " o ní on sa nwa ọkọ ọmọran lọ íni. O rìn siwaju o yà "lọna o ṣùba le ori ọká, ago aaṣara pẹlu ogoji ọwọ rẹ bọ sibẹ "pẹlu, ewe ti o lò ṣùba bọ sori ẹran edú: Ọdọ ko fura titi "o fi de ile Ọrunmla ti o ní ki o jare yẹ on wo. Ọrunmla gbe "ìporún rẹ lé'lẹ̀, o dá a, a rí Ogbè-ṣẹtẹ o ni. "Haa! Ọdọ, "o ní o nwá ọmọran lọ íni li ọkọ, o de'le Odidẹ ó nf'ẹsẹ m'ẹyin "sẹnu; o de'le Akukọ ó nṣu sile; àṣẹhinwa-àṣẹhinbọ o fori lé

---

agbo ti ko ri iru òran bẹẹ ri, o bẹrẹsi ise iyọnu, o nkandi o si ngbe Ọrunml a wọ inu igbo kiri. Awọn irunmalẹ̀ nke si Ọrunmla pe "Maa kalọ o-o-o-o!" On si nda wọn lohun pe:—

"O-o-o-o-o!
Ẹ ma wi fun wọn o-o-o-o!
Àgbo Ẹdu ma re kọrin o-o-o-o!"

Ninu siṣe bayi gbogbo irunmalẹ fi i silẹ de ọrun, onibode si ti tilẹ̀ kun ki Ọrunmla to ide. Nigbati Ọrunmla nkankun ibode ọrun ni onibode dahun pe "Maa pada sọhun o; eewọ ni, a ki isilẹkun ọrun nigba meji. Kini Ọrunmla gbọ̀ eyi ṣe? O yipada biri, o sọkalẹ lori agbo o nfa a sare bọwa 'le aiye nkọrin bayi pe:—

"Olọrun tikun mee wa,
Ṣigidimọ̀gba, sigidimọ̀gba-ṣi!"

"ile emi Ọrunmla, o yà lọna ṣubaa o ṣe e le ọkà lori, ewe ti o "lò bọ sori edú, ago aaṣárà pẹlu ogoji *bọ saarinmeji ibẹ̀, "bi mo ba purọ ki ng yan-ni-lé ọ!" — Ogbèṣẹete.

59. "Ojúmọ mọ, Ọrunmla nmura ati-lọ s'ẹ́gbẹ̀, o kó "ìporún rẹ̀ lelẹ o dá a, a rí Ogúdabèdé, a ni ki o rú àdá ọwọ "rẹ̀, apẹ̀rẹ ìrawé pẹlu akukọ adiẹ kan, ki ibiti o nlọ lè sàn a. "Ọrunmla gbọ, o rú. Pẹ̀tẹbí ti mba a lọ binu pe kini yio ha fi "ṣe ọkọnrin lọna nigbati o lọ ífi àdá rẹ̀ rubọ bayi? Ọrunmla "dahun pe ìrọfa on tó ífiṣe ọkọnrin.

"Nwọn dé ọna nwọn bá ọká, Pẹ̀tẹbi lọgun; ṣugbọn Ọrunmla "fi ìrọfa ọwọ rẹ̀ ṣí ọká o si gbe e sinu ọkẹ Pẹ̀tẹbí.

"Nwọn rin siwaju, nwọn de oju ìdá awọn onísùmọmí nibiti "Igára ile Ará, Iforifo awo Ijerò ati Akónijẹ-múnitá awo "Ọl'Ọgọtún nkó gbogbo èro nigbẹsin, nwọn jade lojiji si Pẹ̀tẹbí "Ọrunmla, nwọn mú u nwọn si nwọ ọ lọ si ibudo wọn. Pẹtẹbi "nke wipe 'Ọrunmla gbà mi o, ogun mu mi lọ o:' Ṣugbọn "Ọrunmla ndahùn bọ lẹhin pe 'maa ba wọn nṣó o! Nibo ni "nwọn yio mú ọ de?' Nwọn mu Pẹ̀tẹbi dé iwaju tan ni "nwọn ntú ọkẹ́ rẹ̀ nwọn njijadu tọwọbọ ọ lati mú ohun inu rẹ̀, "ọká si nyán wọn lọkọọkan titi gbogbo wọn fi kú.

"Ọrunmla ti nrosẹ̀ wọn bọ lẹhin wá íde ibudo wọn ó bá "Pẹ̀tẹbí rẹ̀ nikanṣọṣọ laarin gbogbo òkú ogun. Ọrunmla si wọ "inu ibudo lọ o kó gbogbo ẹrú aimoye ti nwọn ti nkó sibẹ o si "kúku ngbé ibẹ. Ayaaní oo rí i a nwipe 'Ọrunmla dó sinu ajé "tont'aṣọ ṣàsú,' "—Ogúdabèdé.

---

*Nihin ni Ọdọ fọwọ lu ara wo bi yio ri ago aaṣara ati ogoji, ṣugbọn ko ri wọn, Ọrunmla si wa iyan awọn Amoosu ati Amọọrẹ tẹlẹ e ki nwọn ba a lọ si ibiti o ti ya ṣubaa: nwọn ba gbogbo nkan wọnyi nibẹ gẹgẹ bi Ọrunmla ti wi. Enu si ya Ọdọ̀ o wa imọ̀ pe on de ọdọ ẹniti o to ìba jaiye wàyi o, o si joko ti Ọrunmla lati ọjọ naa o nṣe aya rẹ̀.

**60.** "Aìsí Ogbè mi ẹ̀hin, ogun ja ile Elériwò.*"—"Ogbè – Wòri.

"Ọrọ a-b'iku-jigbo."

Awọn baba wa mpe Ọrunmla ni "a-b'iku-jìgbo, nitori nwọn gbagbọ pe

*i.*—Ọrunmla nikanṣoṣo li o tó Ikú ibá-ṣire laìfarapa, ati pe

*ii.*—Ọrunmla nikanṣoṣo li o tó Ikú ibá-ja laigbé si i.

Ka ẹsẹ - ifa wọnyi—

**61.** "Ọrunmla jí o m' ori sile Ikú, o m'ẹsẹ sile Arun, o "m'ẹẹgbẹ́ mejeeji si Ojiji Bàriṣa ikọ Ikú. Awọn babalawo "dahun nwọn ni 'Ọrunmla nigbati o mú ori sile Ikú, Ikú kò ni pa ọ

---

*Iyanhun ni ise ọmọ Ẹlẹ̀ẹwi, o pé ti Ẹwi ti ngbogun lọ si ilu Eleriwo ti Ogbè nkifa fun Elériwo ṣẹetẹ Ewi. Iyanhun jẹẹje fun baba rè pe on nwa Ogbè lọ, o mu egbinrin obi kan bọni, o dé ẹhin odi ilu naa o ko Ogbè, o beere ẹniti nje beẹ lọwọ rè, eleyiini wipe on ni nję bẹẹ, o si tele e lọ sile. Nwọn de ile tan o ki i o mu obi fun u, o ni on ti ngburo rè pé on si wa ise aya rẹ nisisiyi. Ogbè fi ibugbé fun u. O to itadogun Iyanhun ni on nyara lọ iwo baba on ki on bọ̀: o padawa iyọ̀ fun Ewi pe on ti ri Ogbè na o. O pẹ diẹ o tun pada wa igbe bi itadogun lọdọ Ogbè. Li ẹẹkẹta ti Iyanhun ti mpaara bayi ni o ji ada Ogbè pẹlu ọpẹlẹ rẹ ati ọwọifa kan ninu Ifa rẹ sinu ọkẹ laijẹki Ogbè mọ, o mura o ni on nlọ bẹ baba on wo wa o. Ogbè mura o nsin i sọna, nwọn nsọrọ lọ o ndun-mọ Ogbè ko mọ igbati on rin jinna. Nigbati o fura o ni "Haa! bi mo mọ pe ngo jinna to eyi, se ng ba mu ada mi bọni!" Iyanhun yara tu ọkẹ o mu ada Ogbè fun u: nwọn si tun jumọ nsọrọ rin lọ. O tun pẹ ni Ogbè tun duro pe on iba mọ on a mu ọpẹlẹ on bọni: nibẹ Iyanhun mu ọpẹlẹ rẹ fun u. Titi bẹẹ Ogbè ko mọ igbati on ba Iyanhun wọle Ẹwi; Iyanhun mu Ogbè lọ iwọ si yaara iya rẹ o si wa lọ sọ fun baba rè li odi ẹkẹẹsan lọhun pe on ti mu Ogbè dé o!

Ẹwi ni ki a mu u wa iki on, o si ta a lọrẹ gidigidi. Loru ọjọ naa gan ni Ẹwi ran ogun lọ ko ilu Elériwo, nwọn si ṣẹgun, nwọn si ko gbogbo enia ibẹ wa fun Ẹwi. Ni kutu ọjọ keji Ẹwi tẹ Ifa rè o ranṣẹ pe Ogbè ki o wa iwo o fun on. A ri Ogbe - 'Wori. Ogbè dahun o ni "Haa! Aisi Ogbe mi ẹhin, ogun ja ile Elériwo o!" Ẹnu ya Ẹwi o si beere pe "Kini ẹbọ?" A ni agbebọ adiẹ meji ni; Ogbè pa ọkan si ọpẹlẹ rẹ o tu iwu rẹ kiri ile nkọrin wipe—

"Otété ọmọ oliwu
Ọran iwu l'o dun aladiẹ, ọran iwu."

Eṣu ko iwu adiẹ wọnyi lọ ilẹ̀-mọ̀ iwaju awọn ara ile Ogbè ki a le mọ̀ wọn sọtọ bi a ti nko wọn wọle Ẹwi wa. Ẹwi si ko wọn pada patapata fun Ogbè, o ni ki o maa pada lọ ijoko si Eleriwo ile rè o.

ni pa ọ bayi? Nigbati o m'ẹsẹ sile Arun, Arun kò ni íṣọ "ọ lojọ bayi? Nigbati o si m'ẹegbẹ mejeeji si Ojiji Bàrisa, "kò ha ni íṣe ọ lohun bayi? Ọrunmla ni ki nwọn jọwọ "yan ẹbọ fun on. Nwọn yan akukọ adię meji, epo ọpọlọpọ "fun u. Ọrunmla rubọ, ó mbá Ikú yàju Iku ko le pa a, ó "nkẹsẹ le Arun Arun kò le sọ ọ lojọ, ó nk'ẹgbẹ mejeeji si "Ojiji Bàrisa, kò si le ṣe e li ohunkohun."— Ọyẹkú-meji.

Latinu Ifa yi ni awọn babalawo ti gbagbọ pe awọn wa labẹ aabo Ọrunmla, bi nwọn tilẹ nfarapọn ikú-oníku ati àrun-àlarun kiri li orukọ Ọrunmla. Fi eyi wé Marku xvi. 16-18; ati Matteu viii. 17.

**62.** "Ẹké s'owọ gbàgidi mú'le, àbọn ṣe rìgìdì d'ẹyìn; "àteṣímẹṣí ìgbin ti nlọ, ẹnu èwu l'ó mọ:—awọn l'o dífa fun "Ọrunmla nlọ dó s'ikorita Ikú ."—*Ogbè-meji.

**63.** "Oke ṣe geerè wọ'dò, adifa fun Ọrunmla Ikú ntọ ọ "bọwá ípa a. A ni ki Ọrunmla rú olugbóro mẹfa, ewusà mẹfa "ati ẹgbẹ̀fa. Ọrunmla gbọ, o rú; o ṣẹtẹ. **"—Ogbèṣẹtẹ.

---

*Nigbati Iku gbọ pe Ọrunmla ma wa ido si ikorita on, o ran awọn balogun rẹ mẹtẹta—Ẹjọ̀, Ofo ati Arun lati lọ yọ ọ lẹnu fun on. Ṣugbọn Ọrunmla ti rubọ adię merin, igbodo iyan merin, agba ọti mẹrin ati ẹgbẹrin. Ẹjọ ti o kọ de o ku si Ọrunmla o beresi igbo logun; ṣugbọn Ọrunmla fa a mọra o gbe igbodo iyan kan ati isaasun ọbẹ kan fun u ti a fi odidi adię kan se: o si gbe agba ọti kan fun u ki o mu u le onjẹ lori. Ẹjọ jẹ o mu tan o ku silẹ rangbandan, tobẹẹ ti nigbati o jaja ra pala dide, o foribalẹ fun Orunmla, o sure fun u pe "Nlẹ o, Oluwa mi, o ki yio ri ejọ titi o," o si pada lọ wi fun Iku pe "Okọnrin naa ki ise enia buruku rara o, ki o jeki o do sibẹ o." Iku binu o ran Ofo ati Arun wa, Ọrunmla tun ṣe bakannaa fun wọn. Nikẹhin ni Iku tikarẹ dé, o ke-si Ọrunmla pe on dé: Ọrunmla dahun pe "Bi o ba dé ki o duro nibẹ ki o gbé iyan tirẹ, ki o gbe adię tirẹ, ki o si gbé agba-ọti tirẹ. Iku se bẹẹ o jẹ o mu, on paapaa si ku silẹ fun ọjọ meta. Nigbati o jaja ji, o foribalẹ fun Orunmla gẹgẹ bi olukuluku ninu awọn balogun rẹ ti se, o si wipe "Nlẹ o, Oluwa mi, o ki yio ku titi o."

**Awọn babalawo ṣe Ifa sara olugboro mẹfa naa fun Ọrunmla, nwọn si wi fun u pe ki o ko o bọni ki o tikarẹ tọ Iku lọ li alẹ ọjọ naa. Ẹnu ya Iku lati ri Orunmla. Ọrunmla ki i o ni on wa ba Iku ṣire ni. Iku yọ o ni ẹniti on ti nwa kiri li o tilẹ mu ara-rẹ wa ifun on lọọfẹ-loofu yi nitorinaa o fi Ọrunmla wọ̀ si yaara kan ni ireti pe on mbọwa lu u pa mọ ibẹ̀ loru. Ṣugbọn Ọrunmla dide jẹẹ kuro nibẹ o lọ sun sibomiran: Iku

mu olugboro dè loru, o fi lu ọkan ninu aya rè mẹfa pa. Enu ya Iku lowuro lati ri pe ki ise Ọrunmla ni on pa; o rọju dakẹ o si tun fi Ọrunmla wò sibomiran lalẹ naa: ṣugbọn loru, ọkan ninu aya rẹ marun iyoku li o lọ lu - pa dipo Ọrunmla. Bẹẹ bẹẹ li nkan naa rin titi Iku fi pa gbogbo aya rè tan ni ireti ati -pa Ọrunmla. Nigbati ile ọjọ kẹjọ mọ Ọrunmla ki Iku, o ni on nlọ sile wayi o. Iku ni on yio sin Ọrunmla lọ. Ọrunmla ni ki o maṣe sin on, ki o maa sọfọ awọn obirin rè, on nlọ. Ọrunmla wa iji gbogbo olugboro ti Iku nfi pania o ko o le ejika o lọ. Lati ọjọ naa ni a ti nki Ọrunmla ni "A-ba-Iku-jigbo."

---

Ninu awọn itan wọnyi a ri bi iwa Ọrunmla ti yatọ si ti Olugbala ti a fihan-ni ninu Iwe Mimọ Ọlọrun to. Lati ibẹrẹ Bibeli Mimọ li a ti sọtele pe ẹniti yio se Olugbala araiye ko le ṣai-gbọgbẹ. Gen iii. 15 wipe "On yio fọ Iku li ori, Iku yio si pa a ni gigiisẹ." Heb. ii. 14 wipe "Nje niwọnbi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara on ẹjẹ, on tikararẹ pẹlu si mu ipa ninu rè naa; pe nipa iku ki o le pa ẹniti o ni agbara iku run, eyini ni Eṣu." Iwe Mimọ Ọlọrun sọ daju pe ebọ ẹiyẹ ati ẹran ko le tan gbese iku ti ọmọ araiye ti jẹ sọrun afi bi Olugbala naa ba le fi ẹmi ara rẹ ati ori tirẹ tan gbese naa. Ninu Psalmu xi 6–8 asọtẹ́lẹ̀ naa daju, a si tumọ rẹ ninu Heb. x. 4–10 bayi pe "Nitori o soro ti ẹjẹ akọ maalu ati ti ewure, yio fi mu ẹsẹ kuro. Nitori-naa nigbati o wa si aiye, o wipe, ẹbọ ati ẹbọ ọrẹ iwọ ko fẹ́, ṣugbọn ara ni iwọ ti pese silẹ fun mi: ninu ẹbọ ọrẹ sisun ati ẹbọ nitori ẹsẹ iwọ ko ni inudidun si. Nigbanaa ni mo wipe, Kiyesi i, mo de lati se ifẹ tirẹ Ọlọrun· (ninu apo iwe ni li a gbe kọ ọ nipa ti emi). Nitisaaju nigbati o wipe, Ẹbọ ati ẹbọ ọrẹ, ati ẹbọ ọrẹ sisun, ati ẹbọ nitori ẹsẹ ni iwọ ko fẹ, bẹẹni iwọ ko ni inudidun si i ti a nru nipa ti ofin; nigbanaa li o wipe, Kiyesi i, mo de lati se ifẹ tirẹ, Ọlọrun. O mu ti isaaju kuro, ki o le fi idi ekeji mulẹ. Nipa ifẹ yi naa li o nsọ wa di mimọ nipa ifi ara Jesu Kristi tọrọ lẹẹkanṣoṣo." Jesu Kristi tikalarẹ si tumọ ifi ara-rẹ tọrọ yi ninu Marku x. 45 bayi pe "Gẹgẹ bi ọmọ-enia ko ti wa ki a se iranṣẹ fun u, bikoṣe lati maa ṣe iranṣẹ funni, ati lati fi ẹmi rè se irapada fun ọpọlọpọ enia" Olugbala bi iru eyi ti o fi ẹmi rẹ lele fun awọn ọmọ araiye ko si loju Ọpọn Ifa, ki isi ise Ọrunmla ti awọn babalawo ilẹ wa nki.

# ORI VI

"Oluwa mi Ajíki,
Ọgégé a-gb' aiye-gún,
Odùdù ti ídu ori emere
O tún ori ẹni kò siàn ṣe."

Orunmla ni gbogbo babalawo imaa kọtète kí nigbati nwọn ba ji li owurọ, on kannaa ni nwọn ímaa kí kẹhin li alẹ. Nitorinaa ni nwọn ṣe mpe e ní Ajikí. Ninu adura wọn si Ọrunmla li owurọ ati li alẹ, ó jẹ apakan ìlana-ìsin fun wọn lati duro niwajú ìtẹ Orùnmla ki nwon batewo nigba meta fun u, ki nwon si maa wipe,—

**64.** "Ilà jí, Ọrunmla! Ilà jí, Ọruunmlà! Ilà jí, Ọrunmlà! "Mo jí, mo kí Atọla, mo kí Asùlá, mo ki Aṣùrunẹnẹnẹ. Iná "ku-ku-ku l'ahére, enia ku-ku-ku l'ábà,—adifa fun Ọgbọjọ "l'ímọ, o ní 'Ti awo yọ, ọgbọjọ; ti awo yọ, ọgbọjọ.' Njẹ, Oluwa mi, mà jẹki tirẹ yọ o!"

Lẹhin eyi ni babalawo íkunlẹ, a si maa rawọ si Ọrunmla wipe:—

**65.** "Awo Ajíkí l'awo Ajíkí, Awo Ajíkí l'awo Ajíkì' "Awo Ajíkì l'à ípe awo Aja-alẹ-gbun;-a dá a fun awọn mẹtẹeta "nlọ bọ Ori -Ẹlú, Ori - Ẹlú kò gb'ẹbọ lọwọ wọn."

"Awo Ajíkì l'awo Ajíkì, Awo Ajíkì l'awo Ajíkì, Awo "Ajíkì l'à ípe awo Aja-alẹ-gbun; a dá a fun Okéte f'ọwọ "winnníwinní t'ó ní on yio bọ Orí-Ẹlú. Okéte kì Orí-Ẹlú titi "Orí-Ẹlú kò gbà'bọ lọwọ rẹ. Njẹ lèsi kàn maa bọ Ori-Ẹlú ti "Ori-Ẹlú yio gbà lọwọ rẹ?"

NÐ32 = NÐ35



"Awo Ajíkí l'awo Ajíkí, Awo Ajìkì l'awo Ajìkì, Awo "Ajíkì l'à ípe awo Aja-alẹ̀-gbun:—a dá a fun Ikì t'ó ní on yio "bọ Orí-Ẹlú, yio gba ìbọ lọwọ on. Ikì jí ó wẹwọ finí ó wẹsẹ̀ "finí, ó wa ímu obi o nà a si Orí-Ẹlú, Orí-Ẹlu gba lọwọ rẹ̀, ó ní "'Iwọ Ikì ẹlẹyinjú ẹgẹ́ l'o tó mi íbọ.' Igbanaa ni Ikì m'ẹkún "ṣ'ẹkun igbe, ó m'óhùn ṣ'ohun yẹ̀rẹ̀ nkọrin wipe, — 'Gb'obì pa o, Awo Ayẹ̀! Gb'obì pa o, Awo Ayẹ̀!"—Irẹtẹ 'Sá.

"Ọgẹ́gẹ́ a-gb'aiye-gún."

Awọn babanla wa gbagbọ pe Ọrunmla ni Olodumare fi iṣẹ atunṣe aiye le lọwọ nitori on li ó gbọn julọ ninu gbogbo oriṣa ati imalẹ̀ tí aiye mbọ.—

**66.** "Ọlọgbọn-kò-ta'mi-sẹ́ti-aṣọ, Ọmọran-kò-mọ'ye-"erùku ilẹ; awọn l'ó dífa fun Ọrunmla nijọ ti nlọ m'ówo silẹ̀ mú "ọgbọn. Eku meji, ẹja meji, àgbébọ adiẹ meji ati ọrinlenirin-"wo li ẹbọ. Ọrunmla rubọ ọgbọn tán ó nṣe 'Ọgbọn ró si mi "ninu tòkí, kòrogbíngbín ọkọ l'omi àkurọ.' Ayaaní ẹ kò ri i, "Ọrunmla tí o gbọn ju gbogbo irúnmalẹ̀ lọ li a nkì ní 'Agìrí Ile "Ilọgbọn.'"

Awọn babanla wa gbagbọ pe ọgbọn tí Ọrunmla kọ gbogbo ọrọ silẹ lati ni yi li Olodumare fifun u ju gbogbo irúnmalẹ̀ lọ, on naa li ó si fi ntún aiye ṣe ju gbogbo wọn lọ pẹlu.—

**67.** "Ẹnit' ó mọ'ṣẹ́ jijẹ́ ni íjẹ 'Onísẹ,' àimọjíjẹ́ ni íjẹ "'Onìṣẹ̀;'–a dá a fun Ogun ọmọ eleegbẹ̀ oole-nijọ ti Olodumare "nrán a re Ifẹ̀ Oyẹ̀ Ilú Agbo lọ gba igba orí wá. Ogún dé Ifẹ̀ "ó duro l'ọja o ké wipe 'Ẹ kú o ẹnyin ará Ifẹ̀. Olodumare ni "ki ng dá igba orí wá o!' Gbogbo Ifẹ̀ gbọ nwọn hó lọ kùhù, "nwọn ní 'Haa kínla! orí 'yẹ̀ rẹ tabi ti 'bà rẹ i? O di kítikìtikíti, "nwọn lé Ogún gbọnre."

"Ẹnit' ó mọ' ṣẹ́ jíjẹ́ ni íjẹ 'Oníṣẹ,' àimọjíjẹ́ ni íjẹ 'Onìṣẹ̀;'

"a da a fun Ọbalufọn Eyindẹ nijọ ti Olodumare nran a re Ifẹ
"Ooyẹ Ilu Agbo lọ gba igba ori wa. Ọbalufọn de Ifẹ o duro l'
"ọja o ke wipe 'Ẹ ku o ẹnyin ara Ifẹ, Olodumare ni ki ng da
"igba ori wá o!' Gbogbo Ifẹ gbọ nwọn hó lọ kùhù, nwọn ni
" 'Haa, kinla! ori 'yè rẹ tabi ti 'bà rẹ i? O di kitikitikiti,
"nwọn lé Ọbàlufọn gbọnre."

"Enit' o mọ'sé jijẹ ni ijẹ 'Onisẹ,' àimọjijẹ ni ijẹ 'Onìṣẹ;'-
"a dá a fun Sàngó Onikòso Ilaju nijọ ti Olodumare nrán a re
"Ifẹ Ooyẹ Ilú Agbo lọ gba igba ori wá. Sàngó dé Ifẹ o duro
"l'ọja o ké wipe 'Ẹ kú o ẹnyin ara Ifẹ, Olodumare ni ki ng dá
"igba ori wá o!" Gbogbo Ifẹ gbọ nwọn hó lọ kùhù,
"nwọn ni 'Haa, kinla! ori 'yè rẹ tabi ti 'bà rẹ i?' O di kiti-
kitikiti nwọn lé Sàngó gbọnre."

"Enit' ó mọ'sé jijẹ ni ijẹ 'Onisẹ, 'aimọjijẹ ni ijẹ 'Onìsé';–
"a da a fun ọkanlénirinwo Imalẹ nijọ ti Olodumare nrán
"wọn re Ifẹ Ooyẹ Ilu Agbo lọ gba igba ori wá. Ọkanlénirinwo
Imalẹ dé Ifẹ nwọn duro l'ọja nwọn ké wipe 'Ẹ kú o ẹnyin ara
"Ifẹ, Olodumare ni k'á dá igba ori wá o!' Gbogbo Ifẹ
"gbọ nwọn hó lọ kùhù, nwọn ni 'Haa kinla! ori iya nyin tabi
"ti baba nyin ni?' O di kitikitikiti, awọn ara Ifẹ le Ọkanlé-
"nirinwo Imalẹ gbọnre."

"Enit' ó mọ'sé jijé ni ijẹ 'Onisẹ', àimọjijẹ ni ijẹ 'Onìṣẹ,'–
"a dá a fun Ọrunmla Ọsingbo nijọ ti Olodumare nrán a re Ifẹ
"Ooyẹ Ilú Agbo lọ gba igba ori wá. Ọrunmla dé Ifẹ ó duro
"l'ọja ó ké wipe 'Ẹ kú o ẹnyin ara Ifẹ, Olodumare ni ki ng
"gbà igba eku tont'igba ẹja wá o!' Gbogbo Ifẹ gbọ nwọn hó
"lọ kùhù, nwọn ni 'Ọrunmla, o wii re o-o-o!' O di wiriwiri
"gbogbo Ifẹ yara dá ọrún eku tont'ọrún ẹja wa fun Ọrunmla
"ki ó jọwọ lọ bá wọn fi bẹ Olodumare wipe awọn nwá iyokun
"bọ laipẹ o. Ọrunmla gba eku on ẹja naa o gbe e de ọdọ Olodu-
"mare o ni 'Eyiti awọn ara Ifẹ ṣì rí mú wa ni'yi o, nwọn nwá

"iyokun lọwọ o'? Olodumare tẹwọgba ọrún eku on ọrún ẹja "naa ó yọ ó ni 'Lotitọ ni iwọ Ọrunmla yio mọ aiye itunṣe, "njẹ wá tún pada lọ ijokó sinu aiye titi gbogbo wọn yio fi "dá àdápe ẹja ati àdápe eku naa yika; Bayi ni Ọrunmla ṣe "padà ti ọrun wá ijoko sinu aiye, ọrún eku ati ọrún ẹja ti Ifẹ́ "san-kù nijọnaa ni Ọrunmla si ti ngbà lọdọ araiye titi di òni:"–Ọṣẹ́' –Wòri.

(a) Fun iṣẹ titún-aiye-ṣe yi, awọn baba-nla wa fun Ọrunmla ni orukọ pàtaki kan: eyini ni 'Ọmọlihorogbo."

Orukọ naa 'Ọmọlihorogbo' ntọka si bi ọran aiye ati ọran ọrun ti dun Ọrunmla bakannaa; ni bi on paapaa ti fi apakan ara-rẹ bá aiye tan, ti o si fi apakeji ara-rẹ bá ọrun tan.—

**68.** "Ọdẹ ṣ'ápó yọ oró, Arọni-màja ṣ'apò yọ oogún; a dá "a f'Ọmọlihorogbo ti nṣọmọ Ajalaiye, Olodumare nranṣẹ pè e "ki ó wá wo On lọọrun—òjojo nṣe On. Okéte mẹfa li ẹbọ. "Ọmọlihorogbo gbọ o rú, o ni on kò mà ni lè lọ si ọrun o! "Tani ki on fi ile aiye silẹ fun?"

"Ọdẹ ṣ'ápó yọ oró, Arọni-màja ṣ'apò yọ oogun; a dá a "fun Oniṣọṣo ti nṣọmọ Ajalọrun nijọ ti on nikanṣọṣo gbèhin "si ọrun lọọhun, ti òjojo nṣe Olodumare*—kò rihun ṣẹbọ: "òkéte mẹfa l'ẹbọ."

---

*Nigbati Olodumare reti Ọmọlihorogbo ti ko tete de, o daro rẹ leti Oniṣọṣo. Nijọ 'keji Oniṣọṣo rin wa si aiye o ba Ọmọlihorogbo o si tọrọ okéte kan lọwọ rẹ. Ọmọlihorogbo dahun wipe okéte kanṣoṣo naa li o kù lọwọ on, on ko si le fifun ẹnikẹni bikoṣe ẹniti yio ṣe aya on, ti yio si bi ọmọ kan fun on fi ṣikeji ara. Oniṣọṣo gba, o si mu okete kan naa lọ fun Olodumare fi ṣẹbọ, ojojo rè si san diẹ. Oṣu mẹta li a iyun ti a ibi nigba iwa ṣè: njẹ Oniṣọṣo pada wa ibimọ fun Ọmọlihorogbo l'oṣu 'kẹta. O tọ ọmọ naa dagba tan loṣu mẹta o tun pada sọrun o ba Olodumare nsan diẹdiẹ, a wi fun Onişoso pe Olodumare iba ti san tan biosepe a ri okéte 'keji: eyi li o mu Oniṣọṣo tun ṣaajo lọ iba Ọmọlihorogbo lẹẹkeji. Ọmọlihorogbo ati Oniṣọṣo tun ṣe adehun fun ati ri okéte 'keji: Onisoso gba, o si mu okéte 'keji naa lọ fun Olodumare, ojojo tubọ san diẹ si i; Oniṣọṣo si pada wa ibimọ 'keji fun Ọmọlihorogbo loṣu 'kẹta. Bayi ni Oniṣọṣo paara lọ

"Ọdẹ ṣ'ápó yo oró, Arọni-maja ṣ'apa yọ oogun: a dá a "fun ọmọ araiye nijọ nwọn nranṣẹ lọ ibeere lọrun eeṣe ti Oni-"ṣoṣo* kò wa ibimọ fun wọn mọ?"

"Ọdẹ ṣ'ápó yọ oró, Arọni-màja ṣ'apo yọ oogun: a dá a fun "ọmọ araiye nijọ nwọn nbinu lọ sọrun lọ iba Olodumare wijọ "pé eni-tere-éji-tere ti awọn mbimọ yi kò rọrùn, ki Olodumare "saa yan-ni wá ikún wọn lode aiye li awọn mọ. Igba àworan** "ati igba ẹranko li ẹbọ."

Ọdẹ ṣ'ápo yọ oró, Arọni-màja ṣ'apo yọ oogun; —a dá "a fun Ọmọlihorogbo nijọ ti awọn ọmọ araiye pọ tán ti nwọn "nyáju s'Ọlọrun pe 'kini yio ṣe? 'Kò saa ni enia pọju ti araiye lọ.' "

---

paara bọ laarin aiye on ọrun titi o fi ri okete mẹfẹẹfa gba lọ fun Olodumare ti ojojo si fi san fun u tan patapata. Awọn ọmọ ti Ọmọlihorogbo fi bẹẹ ni si jẹ mẹfa,—mẹta ọkọnrin, mẹta obirin.

*Nigbati Olodumare san tan patapata li O wa ibeere pe nigbawo ni Ọmọlihorogbo ti On ransẹ lọ ipè wa iwo On ninu aisan? A dahun pe Ọmọlihorogbo ko ma wa titi. O tun beere pe nibo ni nwọn ha ti ri okéte mẹfẹẹfa fi se ẹbọ On. Oniṣọṣo wa isọ gbogbo rẹ fun u bi on ti paara lọ sinu aiye nigba mẹfa, ti on bimọ mẹfa fun Ọmọlihorogbo ki ọwọ on to le tẹ okéte mẹfa wọnni. Olodumare wa ibinu pe njẹ On ko mọ pe Ọmọlihoro-gbo tilẹ jere tobẹẹ lara On; njẹ ki Onisọso mase tun ṣisẹ lọ sinu aiye mọ. Nitorinaa nigbati araiye ransẹ si ọrun lati beere Oniṣọṣo, Olodumare ransẹ pada pe ki awọn ọmọ araiye mẹta ọkọnrin rọra mu mẹta obirin ni lọkọọ-kan, ki nwọn si maa ba ra-wọn bimọ: nitoripe Onisọso Ọmọ Ajalọrun ko waiye mọ o.

**Nigbati ọmọ araiye rojọ wọn bayi fun Olodumare, Olodumare tun tẹnumọ ọ fun wọn pe ṣebi On ti ransẹ si wọn pe suuru ni ki nwọn mu lati maa fi ba ara-wọn bimọ ki nwọn le maa pọ si i? Ṣugbọn awọn ọmọ araiye si tun nké wipe ọna eyiini pẹ-ju o si nira ju fun wọn, nitorinaa ki Olodu-mare saa kuku maa ti ọdọ rẹ yan -ni wa ikun wọn lode aiye. Olodumare ni "O dara, njẹ ẹ ko ẹbọ ọwọ nyin silẹ ki ẹ maa pada lọ sile aiye, ngo yan-ni wa ikun nyin titi ọrun." Nijọ 'karun Olodumare mu igba aworan wọnni O se 'Sii'! si wọn lori nwọn di enia, O ni ki nwọn maa lọ ba ọmọ araiye gbé: O si tun mu igba ẹranko wọnni o ṣe 'Sii'! si wọn lori nwọn di enia, O ni ki nwọn maa lọ iba ọmọ araiye gbé. Inu ọmọ araiye dun nigbati nwọn ri irinwo enia ya ti ọrun wa iba wọn joko: sugbọn ko n'ọjọ ko n'oṣu ki iyatọ wọn to ifarahan. Ayaani o ri i a nwipe "Ọṣeun, ọmọ enia." Njẹ iru-ọmọ ti enia li a mba sọrọ ti o si ngbọran si-ni-lẹnu; a ba iru-ọmọ ẹranko wi titi, a naa titi ko ni igbọ: a ba iru-ọmọ aworan fọ titi ko gbọ pẹlu.

"Nję Olodumare ranşę si Ọmọlihorogbo ki ó pe gbogbo "araiye wá ifojukan on l'ọrun. Nwọn dé ọrun tan Olodumare "dá wọn joko O ni nwọn kò gbọdọ lọ mọ. Nigbanaa ni "Ọmọlihorogbo bẹrẹsi ibèbẹ fun wọn pe ki Olodumare jọwọ "wo ti on—ti a rán lọ ipè wọn–bi a o ti maa lọgun on, pe on "li ó wá ipé araiye lọ fifun Olodumare pa. Olodumare gbọ "ipè, O si da gbogbo wọn silẹ fun Ọmọlihorogbo. Ayaani "a nwipe Ọmọlihorogbo ni kò jẹ k'aiye baję, on l'ó tun iwa "aiye şe."—Ọyẹkúlogbè.

(b) Fun işe titún-aiye-şe yi, awọn baba-nla wa gbagbọ pe Olodumare fun Ọrunmla ni aşẹ-iwosan lati ipilẹşẹ, O si fi aşẹ sinu ọpá kan fun u lati maa mú u bọni nigbagbogbo.

**69.** "Aşẹşẹ-pa ajuba ni if'ẹsẹ le ori ẹràn geregèregere, a "dá a fun Ọrunmla nlọ gba ọpá ọtọtọọtọ w'aiye. O mbọ o bá "arọ lọna ó ni 'kil'ó şe iwọ ti o ri wọngu-wọngu bayi? "O fi ọpá ọtọtọọtọ kàn a, lẹsẹkannaa arọ nà."

"Aşẹşẹ-pa ajuba ni if'ẹsẹ le ori ẹràn geregèregere, a dá a "fun Ọrunmla nlọ gba ọpá ọtọtọọtọ w'aiye. O mbọ o ba abu- "ké lọná ó ni 'kil' ó şe iwọ ti èhin rẹ şe gànnaku bayi? O fi ọpá "ọtọtọọtọ kàn a, lẹsẹkannaa abuké nà."

"Aşẹşẹ-pa àjuba ni if'ẹsẹ le ori ẹràn geregéregere, a dà a "fun Ọrunmla nlọ gba ọpá ọtọtọọtọ w'aiye. O mbọ ó bá afin "lọna ó ni 'kil' ó şe iwọ ti ara rẹ funfun gboo bayi?' O fi ọpá "ọtọtọọtọ kàn a, lẹsẹkannaa àfin di dúdú."

"Aşẹşẹ-pa àjuba ni if'ẹsẹ le ori ẹràn geregèregere, a dá a "fun Ọrunmla nlọ gba ọpá ọtọtọọtọ w'aiye. O mbọ ó bá "aboyún Ifẹ ndaawọ ati-bi sọna, o ni 'kil' ó şe iwọ aboyun Ifẹ " ti ó nràpala bayi?' O fi ọpá ọtọtọọtọ kàn a, lẹsẹkannaa "aboyun Ifẹ bi tibi-tire." — Ejiogbè.

Latihin ni awọn baba-nla wa ti nka ọpọlọpọ işẹ iyanu iwosan ati omiran ti Ọrunmla şe laarin araiye.

Akiyesi:— A şe akiyesi ninu Bibeli Mimọ awọn ọna ti imọ yi gbà dé ọkàn awọn baba-nla wa. Nibi pipọ li a ri ti Bibeli Mimọ nfi ọpá şe apeere ọla, aşẹ ati agbara.

(a) Ọpa yi lọwọ Olọrun jẹ ọpá agbara, ọpá irin. Psalmu 110, 1–2;—"Oluwa wi fun Oluwa mi pe, Iwọ joko li ọwọ ọtun mi, titi emi o fi sọ awọn ọta rẹ di apoti-itisẹ rẹ. Oluwa yio na ọpa agbara rẹ lati Sioni wá: iwọ jọba laarin awọn ọta rẹ." Psalmu 2, 7–9. "Emi o si rohin ipinnu Oluwa: O ti wi fun mi pe, Iwọ li ọmọ mi, loni ni mo bi ọ. Beere lọwọ mi, emi o si fi awọn orilẹ-ede fun ọ ni ini rẹ, ati iha opin ilẹ li ọrọ-ilẹ rẹ. Ọpa irin ni iwọ o fi fọ wọn; iwọ o si run wọn wómú-wómú bi ohun-èlo amọ."

(b) Ọpá yi lọwọ Jesu Kristi jẹ ọpá Olusọ–agutan fun aabo ati itunú awọn agutan rẹ.—Psa. 23, 1-4.

"Oluwa li Olusọ–agutan mi; emi ki yio ṣe alaini. O mu mi dubulẹ ninu papa-oko tutù; o mu mi lọ si iha omi didakẹ rọrọ, O tu ọkan mi lara; o mu mi lọ nipa ọna ododo nitori orukọ rẹ. Nitootọ, bi mo tilẹ nrin laarin afonifoji ojiji ikú, emi ki yio bẹru ibi kan; nitori ti Iwọ wa pẹlu mi; ọgọ rẹ ati ọpa rẹ nwọn ntù mi ninu."

(d) Ọpá naa lọwọ Jakọbu jẹ ọpá aṣẹ ẹnu àgba - idile—Heb. 11: 21.

"Nipa igbagbọ ni Jakọbu, nigbati o wà ni ibulẹ ikú, o sure fun awọn ọmọ Josefu mejeeji; o foribalẹ, o fi ara ti ori ọpá tirẹ."

(e) Ọpá naa lọwọ ẹya Judah jẹ ọpa-alade fun ipo ọlá ninu Ijọba — Gen. 49: 10.

"Ọpá–alade ki yio ti ọwọ Judah kuro, bẹeni olofin ki yio kuro laarin ẹsẹ rẹ, titi Ṣiloh yio fi de; on li awọn enia yio gbọ tirẹ."

(ẹ) Ọpá naa lọwọ Mose ati Aaroni, lọwọ Eliṣa ati lọwọ angeli ti o farahan Gideoni, jẹ ọpá iṣẹ iyanu.—Eksod. 8. 16–17. "Oluwa si wi fun Mose pe, Sọ fun Aaroni pe, Na ọpá rẹ, ki o si lu eekuru ilẹ, ki o le di ina já gbogbo ilẹ Egipti. Nwọn si ṣe bẹẹ; Aaroni si na ọwọ rẹ pẹlu ọpá rẹ, o si lu erupẹ ilẹ, iná si wà lara enia, ati lara ẹran; gbogbo eekuru ilẹ li o di ina já gbogbo ilẹ Egipti."

Num. 20 7–8. "Oluwa si sọ fun Mose pe, Mú ọpa ni, ki o si pe ijọ awọn enia jọ, iwọ, ati Aaroni arakọnrin rẹ, ki ẹ sọrọ si apata ni li oju wọn, yio si tú omi rẹ jade; iwọ o si mú omi

lati inu apata naa jade fun wọn wá: iwọ o si fi fun ijọ ati fun ẹran wọn mu. 9 Mose si mu ọpá naa lati iwaju Oluwa lọ, bi o ti fun u li aṣẹ"

ii. Ọba 4. 29 "Elisa si wi fun Gehasi pe, Di àmure rẹ, ki o si mú ọpá mi li ọwọ rẹ, ki o si lọ, bi iwọ ba ri ẹnikẹni li ọna, maṣe ki i; bi ẹnikẹni ba si ki ọ, maṣe dá a lohún: ki o si fi ọpá "mi le iwaju ọmọ naa.

Onid. 6, 21. "Angeli Ọlọrun si wi fun Gideoni pe, Mú ẹran naá, ati akara alaiwú naa, ki o si fi wọn le ori okuta yi, ki o si da omi ẹran naa silẹ. On si ṣe bẹẹ. Nigbanaa ni angẹli Oluwa na ọpá ti o wa li ọwọ rẹ̀, o si fi ori rẹ̀ kan ẹran naa ati akara alaiwú naa; iná si là lati inu okuta naa jade, ó si jó ẹran naa ati akara alaiwú; angeli Oluwa naa si lọ kuro niwaju rẹ̀."

Oniruuru ọna wọnyi ni awọn baba-nla wa nfẹ ki a mọ-mọ Ọpá Ọtọtọọtọ lọwọ Ọrunmla fun iṣẹ atunṣe-aiye ti nwọn gbagbọ pe Olodumare ti fi lé e lọwọ.

(d) Awọn ohun miran ti Olodumare fun Ọrunmla lati maa mú bọni fun iṣẹ titún-aiye-ṣe ni Irọfá ati Irukẹrẹ.

**70.** "Ọrunmla ni 'Asápè,' mo ni 'Asápè,' ó ni bi a ba "sá-pè ọdẹ a gb'ápo rè.'"

"Ọrunmla ni 'Asápe,' mo ni 'Asápè,' ó ni 'bi a bá sá-pè "ajagun a gb'ásà rẹ.'"

"Ọrunmla ni 'Asápè' mo ni 'Asápè,' ó ni 'bi a ba sá-pè "ọṣowo a gbe owó ànàkù rẹ.'"

"Ọrunmla ni 'Asápè,' mo ni 'Asápè,' ó ni 'bi a ba sà-pè "'emi Ọrunmla, emi a mú Irọfa idẹ, emi a mú Irukẹrẹ, okùn, "'kò si ẹniti o le gba adiẹ temi sin.'"—Ọsá-meji.

Latihin ni gbogbo Oluwo (eyini ni Olú awo tabi Olori ninu ẹgbẹ awọn babalawo nibikibi) a maa jẹ 'Asápè' li ooki oyè rẹ.

(e) Ohun pataki miran ti awọn baba-nla wa gbagbọ pe Olodumare tún fifun Ọrunmla ni 'Oṣumàre Ẹgọ ti imaa bi ohun rere gbogbo jade fun ilo Ọrunmla ni oniruuru ati ni iwọnkiwọn ti Ọrunmla ba ti fẹ fun àtúnṣe aiye.

**71.** "Irọfa mi ki iṣe ẹ̀ṣi, Irukẹ̀rẹ mi ki iṣe idà, Iboju mi "ki iṣe apata; a dá a fun Ọrunmla nlọ fẹ́ Oṣumare Ẹgọ ṣe aya:- "Oṣumare Ẹgọ ti iṣ'ọmọ Ọlọọjà Ororo.– Oṣumare Ẹgọ ni iṣu "owó, Oṣumare Ẹgọ ni iṣu okùn, Oṣumare Ẹgọ ni iṣu idẹ: "Oṣumare Ẹgọ! iwọ kò jẹ́ padà ki o wá ṣu temi fun mi, "Oṣumare Ẹgọ!"

Latihinyi pẹlu ni awọn ògbó awo ati olọsányin ati adáhunṣe ni ile wa iti imaa s'aferi ohun àwamaari kan ti nwọn a maa pe ni 'Imi Oṣumare,' ti nwọn ngbagbọ pe ó ni agbara lati maa bi ohun àlumọni gbogbo fun ẹnikeni ti ó ba ni i silẹ; nitori nigbati Ọrunmla ni Oṣumare, ó di ọlọrọ ninu ohun gbogbo nipa agbara ibisi ti Oṣumare ni, ti ó si imaa lò fun, ati nipa aṣẹ Ọrunmla.

Akiyesi:—Iro yi kò dé ọkàn awọn baba-nla wa lasan; Ọlọrun ti iṣe Ẹlẹda wọn li ó gbin i sibẹ. Lati ni ohun gbogbo jẹ apakan ọlá Ọlọrun, njẹ enia ti a dá li àwòrán Ọlọrun kò le ṣaifẹ́ lati ni ohun gbogbo pẹlu. Bi enia tilẹ jẹ́ alaimọna naa ti à igba ini ohun gbogbo, sibẹ eyiini kò wipe ki aarẹ̀ ki ó mú u, tabi ki suuru tán a ninu ṣiṣe àferi ipá naa. Ṣugbọn, iwọ ti nka iwe yi, mo fẹ́ itè ẹ mọ ọ lọkan nihinyi pe bi iwọ ba nfẹ ni ohun gbogbo, kọtètè sàferi Ọlọrun ati Kristi Rẹ̀.—Matt. 6: 31–33. "Nitorinaa ẹ má gbèro wipe, Kili a o jẹ? tabi, kili a o mu? tabi, nibo li a o ti fi aṣọ wọ wa? Nitori gbogbo nkan wọnyi li awọn keferi nwá kiri. Baba nyin ti mbẹ li ọrun mọ pé, ẹnyin kò le ṣe alaini gbogbo nkan wọnyi. Ṣugbọn ẹ tètè maa wá ijọba Ọlọrun ati ododo rẹ̀: gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin.

"Oṣumàre Ẹgọ Ọlọọjà Ororo."

Itumọ oruko yi 'Oṣumàre' jasi 'Oṣù ti o tobi julọ'. A kiyesi i pe ati Oṣumare ati oṣùyóṣù, kò si eyiti o le lé sọju ọrun ninu ẹwà ati ogo rẹ laisi agbara oorùn. Latinu ogo oorun ni òṣumare ti ijade soju sánmà:—Latinu agbara oorùn kannaa ni ohun ọrọ gbogbo lori ilẹ ati ninu omi nisalẹ ilẹ̀ ti njade wá pẹlu. Lati wadi ọran yi siwaju kiyesi ifiwe ti àlá Josefu ni lẹgbẹ́ awọn ibukún rẹ̀. Gen. 37. 9–11 "O si tun lá àlá miran, o si rọ ọ fun awọn arakọnrin rẹ̀, o wipe, Sa wò o, mo tun lá àlá kan si i; si wò o, oorùn ati oṣupa, ati irawọ mọkanla nforibalẹ fun mi. O si rọ ọ fun baba rẹ̀, ati fun awọn arakọnrin rẹ̀: baba rẹ̀ si bá a wi, o si wi fun u pe, Alá kili eyi ti iwọ lá yi? Emi ati iya rẹ, ati awọn arakọnrin rẹ yio ha wá nitootọ, lati foribalẹ fun ọ bi? Awọn arakọnrin rẹ̀ si ṣe ilara rẹ̀; ṣugbọn baba rẹ̀ pa ọrọ naa mọ."

Gen. 49. 24–26. "Ṣugbọn ọrun rẹ joko li agbara, a si mu apa ọwọ rẹ larale, lati ọwọ Alagbara Jakọbu wá, (lati ibẹ li oluṣọ-agutan, okuta Israeli). Ani lati ọwọ Ọlọrun baba rẹ wá, ẹniti yio ràn ọ lọwọ; ati lati ọwọ Olodumare wá ẹniti yio fi ibukun lati oke ọrun busi i fun ọ, ibukún ọgbun ti o wà nisalẹ, ibukun ọmú, ati ti inu. Ibukun awọn baba rẹ ti ju ibukun awọn baba nla mi lọ, titi de opin oke aiyeraiye wọnni: nwọn o si maa gbe ori Josefu, ati li atari ẹniti a yàsọtọ laarin awọn arakọnrin rẹ."

Deut 33. 13–16. "Ati niti Josefu o wipe, Abukún Oluwa ni ilẹ rẹ, fun ohun iyebiye ọrun, fun iri, ati fun ibú ti o ba nisalẹ, ati fun eso iyebiye ti oorùn múwa, ati fun ohun iyebiye ti ndàgba li oṣooṣù, ati fun ohun pàtaki okenla igbaani, ati fun ohun iyebiye oke aiyeraiye, ati fun ohun iyebiye aiye ati ẹkún rẹ, ati fun ifẹ inurere ẹniti o gbe inu igbẹ: jẹ ki ibukún ki o wá sori Josefu, ati si àtari ẹniti a yàsọtọ laarin awọn arakọnrin rẹ."

Yio si tubọ ya-ni lẹnu gidigidi pe Ori 'kẹrin Iwe Ifihan ti o sọ kinikini nipa ti itẹ Jesu Kristi ati Oṣumàre ẹlẹwà ti o yi i ká, fi Orin Iyin ti gbogbo ẹdá ọrun nkọ yi itẹ naa ká han -ni pẹlu bayi.–

Ifihan 4, 1-3 "Lẹhin eyi li emi wò, si kiyesi i, ilẹkun kan ṣi silẹ li ọrun: ohun ti mo si tetekọ gbọ dabi ti ipè ti mbá mi sọrọ; ti o wipe, Goke wá ihin emi o si fi ohun ti yio hù lẹhin ọla hàn ọ. Lojukannaa mo si wà ninu Ẹmi; si kiyesi i, a tẹ itẹ kan li ọrun, ẹnikan si joko lori itẹ naa. Ẹniti o si joko jẹ ẹniti a ba maa wò bi okuta jasperi, ati sardi: òṣumare si ta yi itẹ naa ka kiri, ni wiwò rẹ bi okuta smaragdu. 5. Ati lati ibi itẹ naa ni mànamána ati aará ati ohùn ti jade wa: fitila iná meje si ntàn nibẹ niwaju itẹ naa, ti iṣe Ẹmi meje ti Ọlọrun.

9–11. Nigbati awọn ẹda alaaye wọnni si fi ogo ati ọla, ati ọpẹ fun ẹniti o joko lori itẹ, ti o mbẹ lai ati lailai, awọn alagba mẹrinlelogun naa wólẹ niwaju ẹniti o joko lori itẹ, nwọn si tẹriba fun ẹniti mbẹ laaye lai ati lailai, nwọn si fi ade wọn lelẹ niwaju itẹ naa wipe, Oluwa, iwọ li o yẹ lati gba ogo ati ọlá ati agbara: nitoripe iwọ li o dá ohun gbogbo, ati nitori wiwù rẹ ni nwọn fi wà ti a si ṣe dá wọn.

Iwọ olufẹ mi ti nkà iwe yi, jọwọ tẹnumọ ọrọ orin yi rere; nitori o kún fun imọ ijinlẹ gidigidi fun ẹnikẹni ti nwá Agamrara ati Imí Oṣumare kiri:—"nitoripe Iwọ Ọdọ-agutan Ọlọrun

ti nkó ẹṣẹ aiye lọ, Iwọ Ọdọ–agutan ti a pa, ti o ṣi tún mbẹ laaye lai ati lailai, àni Iwọ JESU KRISTI li o dá ohùn gbogbo, ati nitori wiwù rẹ ni nwọn fi wà ti a si ṣe dá wọn.”

Njẹ lẹhin gbigbọ ati mimọ ọrọ-orin yi dáju, iwọ onigbagbọ ati olufẹ Kristi yio pa ara–rẹ mọ kuro lọdọ awọn ti nṣáferi Agamrara ati Imi Oṣumare (ati lọdọ awọn ti ndẹdà) fun ati-ni ọrọ pipọ: iwọ yio kúkú maa tẹlé imọran iyebiye ti Paulu fifun gbogbo enia Ọlọrun bi a ti kọ ọ sinu i Tim. 6, 16.—“Ṣugbọn iwabi–Ọlọrun pẹlu itẹlọrun ère nla ni. Nitori awa kò mu ohun kan wá si aiye yi, o si daniloju pe awa ki yio si le mú ohun kan jade lọ. Bi a ba si li onjẹ ti on ti aṣọ, ki eyiini ki o tẹ wa lọrùn ṣugbọn awọn ti nfẹ di ọlọrọ a maa bọ sinu idanwo ati idẹkùn, ati sinu wère ifẹkufẹ pipọ ti ipanilara, ti si nri enia sinu iparun ati ègbé. Nitoripe ifẹ owo ni gbòmgbo iwa buburu gbogbo: eyiti nigbati ẹlomiran nfi ojukokoro wá kiri, a ti tàn wọn jẹ kuro ninu igbagbọ, nwọn si fi ibinujẹ pipọ gún ara–wọn li ọkọ. Ṣugbọn iwọ, enia Ọlọrun, sá fun nkan wọnyi; ki o si maa tọ ododo, iwabi–Ọlọrun, igbágbọ, ifẹ, suuru, iwa tutu lẹhin. Maa ja ija rere ti igbagbọ, fi ọwọ le iye ainipẹkun, nibiti a gbe pè ọ si pẹlu ti iwọ si ṣe ijẹwọ rere niwaju ẹlẹri pupọ. Mo fi aṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ti nsọ ohun gbogbo di aaye, ati niwaju Jesu Kristi, ẹni, niwaju Pọntiu Pilatu, ti o o jẹri ijẹwọ rere; Ki iwọ ki o pa aṣẹ yi mọ li ailabawọn, li ainibawi, titi ifarahàn Jesu Kristi wa: Ni igba tirẹ, ẹniti yio fihan, Olubukún, ati Alagbara naa kanṣoṣo, Ọba awọn ọba, ati Oluwa awọn oluwa; Ẹniti on nikanṣoṣo ni aiku, o tẹdo sinu imọlẹ ti ẹnikan kò le sunmọ; ẹniti ẹnikan kò ri, bẹli a kò le ri i: ti ọlá ati agbara mbẹ fun lailai. Amin.”

“Odudu ti idù ori emère,
O tún ori ẹniti kò siàn ṣe.”

Awọn baba-nla wa gbagbọ pe ọwọ awọn èmi buburu kan wà ti imaa le ọmọ tootọ kuro ninu aboyún lati gba ipò nibẹ. Nigbati a ba bi iru ọmọ bẹẹ, nwọn ki ipẹ iku mọ iyá wọn lọwọ: tabi, nwọn a dàgba dè akoko ti iwọ gbogbo enia lara tán, nigbanaa nwọn a ṣẹ–kú mọ gbogbo enia loju. Irú awọn ẹni bẹẹ li awọn enia ilẹ wa mpe ni ‘emère.” Nitorinaa, lati du ori rere fun awọn emère tabi eleere bẹ, awọn ọkọ a maa fa aya wọn fun babalawo tọju bi nwọn ba ti loyun: nwọn ni igbẹkẹle pe nipa riru ẹbọ igbagbogbo fun aboyún bẹẹ, awọn ẹmi emère ki yio le pa orirere ti ọmọ–titun naa mba bọwa aiye di buburu mọ ọ ninu. Eyi ni ijẹ didù–ori emère.

NDS '72-'76 Awrre & Isegun



Ewè, ninu igbagbọ ilẹ wa, awọn enia ti ifùwa buburu titi kan ikú gbigbona jẹ ol'ori aisiàn; bẹẹ gẹgẹ ni gbogbo ẹni rere ti işubu sọwọ ẹni buburu jẹ ol'óri aisiàn: bẹẹ gẹgẹ ni gbogbo enia ti wahala, ipọnju tabi idaamu mba ni abale-àbale ni ol'ori aisiàn. Awọn baba-nla wa gbagbọ pe Ọrunmla a maa tun ori aisian bawọnni şe nipa yiyan ẹbọ igbagbogbo lati tù wọn.—Ka ẹsẹ – ifa wọnyi:—

**72.** "Ọrunmla ni 'A-ró-dè' mo ni 'A-ró-dè,' O ni 'Ẹnyin "ọmọ wẹẹrẹ ti nlọ sinu aiye, nigbawo li ẹ o pada bọ?' Nwọn "dahùn wipe nigbati ọjà ba ti tó gaan li awọn mpadà bọ. "Ọrunmla ni 'Mo wọ! emi ki ibá awọn eleyi şe ajọrin.' "

"Ọrunmla ni 'A-ró-dè' mo ni 'A-ró-dè', O ni 'Ẹnyin "igiripá ti nlọ sinu aiye, nigbawo li ẹ o pada bọ?' Nwọn "dahun wipe nigbati ọjọ ba ti kàn 'tàri gaan li awọn mpadà bọ. "Ọrunmla ni 'Mo wọ! emi ki ibá awọn eleyi şe ajọrin.' "

"Ọrunmla ni 'A-ró-dè' mo ni 'A-ró-dè', O ni 'Ẹnyin "àgbaagba ti nlọ sinu aiye, nigbawo li ẹ o pada bọ?' Nwọn "dahun pe 'O di ọjọ ti a ti ilẹ di àgubè, ti ọrọ godogbo t'o wà "n'ikùlé Olodumare fu imù lẹsè şaraşàra.' Ọrunmla ni "Ẹẹn-ẹẹn! mo ri awọn ti ngo bá şe àjọrin wàyi o'. O wá m'ẹkún "ş'ẹkún igbe, ó m'ohùn ş'ohùn iyèrẹ, ó nşe

" 'Akọ ẹranla f'ori tàrapó,
" 'Iwarẹ ọrun ' m' aa bá-rin
" 'Mee b'émère rin!' "

**73.** "Ọrunmla ni 'Aródè' mo ni 'Aródè,'—a dá a fun "awọn ọmọ wẹẹrẹ-wẹẹrẹ nlọ sinu aiye ti Onibodè ndá wọn "dèhin lọna—nwọn nkú li ọmọ kékèké. A ni 'Eetiri?' A "ni nwọn kò duro de Ọrunmla ni. Meji tọkọnrin-"tobirin ninu wọn ti Ọrunmla beere lọwọ wọn pe "Tani ẹ ha "duro dè?' Nwọn ni 'Iwọ Ọrunmla ni,' O ni 'Njẹ, o dara, ẹ "ẹ maa kalọ.' Nwọn bá Ọrunmla de ibodè, Onibode nfẹ dá "wọn dèhin; Ọrunmla bẹbẹ fun wọn, o si san ojoojúlùgba "lori wọn. Ayaani o ri òjoojúlùgba naa li a nsan fi gbọ ori "ọmọ-titun titi di oni."—Oşoofú.

**74.** "Ọrunmla ni 'Ọkanrandi' mo ni 'Ọkanrandi' O ni "'Ori ọmọ eku ti Ọkanrandi ha gbó bi?' Mo ni 'Ori ọmọ eku "kò mà gbó ò!'"

"Ọrunmla ni 'Ọkanrandi' mo ni 'Ọkanrandi' O ni 'Ori "ọmọ ẹja ti Ọkanrandi ha gbó bi?' Mo ni 'Ori ọmọ ẹja "kò mà gbó ò!'"

"Ọrunmla ni 'Ọkanrandi' mo ni 'Ọkanrandi,' O ni 'Ori "ọmọ araiye ti Ọkanrin di ha gbó bi?' Mo ni 'Ori ọmọ araiye "ti Ọkanran di kò mà gbó ò! A ni 'Kili a o ha ṣe ki ori ọmọ "araiye le gbó?' Ọrunmla ni 'igiripà obukọ kan ati ọtalegbẹta "li ẹbọ.' A gbọ a rú, ori ọmọ araiye wá igbó." Ọkanran-'Di.

**75.** "Ori rere ni iṣẹgun ọtá, ori aisiàn ni ọtá idi li àdipa. "Njẹ tani bi mi ò? Ogúda tà 'túra pa! Ẹ jẹ ki nwọn o maa "ṣubu lé 'ra wọn, ki nwọn k' ó maa p'ara wọn. Gbogbo ọtá ti "mo ba ni kò ni iyè, pipa ni ki nwọn o maa p'ara wọn lọ "bẹẹrẹbẹ. Ṣugbọn emi kò mà m'ọtá emi kò mà m'odi ò!"

"Tani ijẹ 'ori aisiàn'? —Ẹni a bá ndi t'ó ni kò si ẹni t'ó "le di on;—adipa, on ni ijẹ ori aisiàn," — àdipa.

"Njẹ àṣubulébu mà–mà ni t'egbee o;—aṣubulébu ni ki "ọtá maa ṣubu lé 'ra wọn: ọtá mi kò ni ib 'ara wọn ré, akọ "alaamgbá ki ib'ara wọn rẹ bọrọbọrọ."—Ogudatà–'Túra.

**76.** "Agbọ-irú l'awo àgbọ-irú, Agbọ–itu l'awo àgbọ-itu, "Oloojòmsúrú l'awo Ikiyinwún:—a dá a f'Ọrunmla nlọ wẹri "àwẹgbó."

"Ọrunmla ni 'Osuru-sùru' mo ni 'Osuru-sùru,' o ni 'Tani 'mbẹ lẹhin ti nwẹri? A ni 'Ṣé iwọ Ọrunmla ni!' O wa "im'ẹkun ṣ'ẹkún igbe, o mu ohùn ṣ'ohun iyẹrẹ, o nṣe—

"Ori awo wẹ̀, àwẹgbó mà ni;
"Ori awo wẹ̀, awẹgbó mà ni;
"Ori awo wẹ̀, àwẹtọ mà ni;
"Ori awo wẹ̀, àwẹtọ mà ni!
"Ori awo wẹ̀, àwẹmọ mà ni,
"Ori awo wẹ̀, àwẹmọ mà ni!"—Otúra–'Ká.

Akiyesi:— Awọn ẹsẹ-ifa ti a kà lati 72 de 76 fihan-ni daju pe ori awa enia ti buru latinu iya wa wá, ati pe laisi iwẹnumọ kan ti o daju, ọran araiye ko le yé idiju, ọna wọn ko si le yé iburu. Ajò ati-ri ẹniti yio wẹ̀ wọn yi ni awọn oobi wa ṣe de ọdọ awọn irunmalẹ̀ ati igbamalẹ̀ titi nwọn fi bi wa sinu ibọriṣa ti nwọn si nsọ orukọ wa ni 'Ṣangowẹ̀mimọ,' 'Osówẹ̀mimọ,' 'Oṣunwẹ̀mimọ,' 'Ifáwẹ̀mimọ,' ati. ọpọ iru orukọ bawọnni ti njẹwọ aimọ ati eeri ti a bi-ni-bi.

Bi onigbagbọ ati ọmọ imọlẹ, awa mọ daju pe Ọrunmla kò le wẹ ori aisàn ti ẹbi-ẹsẹ kó-bá ọmọ araiye, Ọrunmla ko le yi ibinu Ọlọrun pada kuro lori ẹlẹsẹ; bẹẹni iwẹ Ọrunmla kò tó lati sọ-ni-di mimọ, lati fun-ni ni iyipada ọkàn si iwabi-ọlọrun, ati lati mú alafia ati iyọnu Ọlọrun ti a ti sọnu pada bọ sori ọmọ enia.

Njẹ bi Ọrunmla beere lọwọ onigbagbọ pe 'Tani mbẹ lẹhin ti nwẹri?' awa dahun pe "JESU KRISTI Oluwa mi ati Ọlọrun mi ni Ẹnikansoṣo naa ti mbẹ lẹhin ti nwẹri àwẹmọ ati àwẹgbó fun gbogbo ẹniti o sádi I."

Ọpẹ ni fun Ọlọrun Olodumare Ẹniti o fun wa ni ọrọ mimọ Rẹ, ti O si kọ wa pe ki a sá tọ JESU lọ fun iwẹnumọ ti o pé, ti o dáju, ti ó si le gba-ni-là de opin.

John 13, 1–10 "Njẹ ki ajọ irekọja ki o to de, nigbati Jesu mọ pe wakati rè de tán, nigbati on o ti aiye yi kuro lọ sọdọ Baba, fifẹ ti o fẹ awọn tirè ti o wa li aiye, o fẹ wọn titi de opin. Nigbati onjẹ alẹ si pari tán, nigbana li Eṣu fi i si aiya Judasi Iskariotu ọmọ Simoni lati fi i han; Jesu si ti mọ pe Baba ti fi ohun gbogbo le on lọwọ, ati pe lọdọ Ọlọrun li on ti wa, on si nlọ sọdọ Ọlọrun: O dide ni idi onjẹ alẹ, o si fi agbada rẹ lelè li apakan; o si mu gèle o di ara-rẹ li amure. Lẹhin eyini o bu omi sinu awokoto kan, o si bẹẹrẹ si imaa wẹ ẹsẹ awọn ọmọ ẹhin rè, o si nfi gèle ti o fi di àmure nù wọn. Nigbanaa li o de ọdọ Simoni Peteru: Peteru si wi fun u pe, Oluwa, iwọ nwẹ mi li ẹsẹ? Jesu dahun o si wi fun u pe, Ohun ti emi nṣe iwọ kò mọ nisisiyi; ṣugbọn iwọ o mọ ọ nikẹhin. Peteru wi fun u pe, Iwọ ki yio wẹ mi li ẹsẹ lai. Jesu da a lohun pe, Bi emi kò ba wẹ ọ, iwọ kò ni ipa lọdọ mi. Simoni Peteru si wi fun u pe, Oluwa, ki iṣe kiki ẹsẹ mi nikan, ṣugbọn ọwọ ati ori mi pẹlu. Jesu si wi fun u pe, Ẹniti a ti wẹ kò tun fẹ ju ki a wẹ ẹsẹ rè, ṣugbọn o mọ nibi gbogbo: ẹnyin si mọ, ṣugbọn ki iṣe gbogbo nyin.

Ọpẹ ni fun Jesu Kristi Olugbala wa Ẹniti o fẹ wa tobẹ ti o si fi ẹjẹ ara-rè ṣe iwẹ wa— ani etutu fun ẹsẹ araiye.

i John 1, 7–10 "Ṣugbọn bi awa ba nrin ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ni idapọ pẹlu ara–wa, ati ẹjẹ Jesu Kristi Ọmọ rè ni nwẹ wa nù kuro ninu ẹṣẹ wa gbogbo. Bi awa ba wipe awa ko li ẹṣẹ, awa tan ara-wa jẹ, otitọ ko sì sí ninu wa.

Bi awa ba jẹwọ ẹṣẹ wa olootọ ati olododo li on, lati dari ẹṣẹ wa ji wa, ati lati wẹ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo. Bi awa ba wipe awa kò ṣẹ, awa mu u li eke, ọrọ rẹ kò si si ninu wa."

i John 2, 1–2.—"Ẹnyin ọmọde mi, iwe nkan wọnyi ni mo kọ si nyin, ki ẹ maṣe ṣẹ. Bi ẹnikẹni ba ṣẹ, awa ni alagbawi kan lọdọ Baba, Jesu Kristi olododo: On si ni etutu fun ẹṣẹ wa: ki isi iṣe kiki tiwa, ṣugbọn fun ẹṣẹ gbogbo araiye pẹlu.

Ọpẹ ni fun Ẹmi Mimọ Ọlọrun wa ti kò dẹkun ifoye ye araiye nipa ti ẹṣẹ, ati nipa ti ododo, ati nipa ti idájọ: ati ti O si nfi bẹẹ mú wọn maa ṣe àferi Olugbala.

i Kor. 6. 9–11. "Ẹnyin kò mọ pe awọn alaiṣootọ ki yio jogún ijọba Ọlọrun? Ki a má tàn nyin jẹ: ki iṣe awọn àgbere, tabi awọn aboriṣa, tabi awọn panṣaga, tabi awọn alailera ọkàn, tabi awọn ti nfi ọkọnrin ba ara wọn jẹ, tabi awọn olè, tabi awọn olojukokoro, tabi awọn ọmutipara, tabi awọn ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọwọgbà ni yio jogun ijọba Ọlọrun. Gẹgẹ bẹẹ si li awọn ẹlomiran ninu nyin ri: ṣugbọn a ti wẹ nyin nù, ṣugbọn a ti sọ nyin di mimọ, repititia, ṣugbọn a ti da nyin lare li orukọ Jesu Oluwa, ati nipa Ẹmi Ọlọrun wa."

Orin.— "A baa f'okun wẹri o,<br>A baa f'ọsa wesẹ,<br>Ẹni Jesu wẹ l'ó mọ t'okan–t'ara."

---

IPARI IWE NAA.

# ASỌJỌ AWỌN ORI — IWE NAA

ORI I — Ooki ati Itumọ Ọrunmla, ewe 1–2. Ija laarin aiye ati ọrun,— Ajọ ati Abemọ, ewe. 3–8. Araiye kò ro ati-túmba fun ara ọrun:—laisi ẹbọ on ètutu kò si ojurere Ọlọrun:— lati ọrun ni oniilàja ti wá. ewe 9–11.

ORI II — Ọrunmla jẹ́ Ẹlẹeri-ipin —nitori on jẹ́ Igbimọ Olodumare, atı ori fun gbogbo irunmalẹ: ewe 12–16. Ọrunmla jẹ́ Ibikeji Olodumare nitori tonti Rẹ̀ l'ó bẹ̀rẹ iwa: ewe 17.— on li ó kápá Ẹsu: ewe 18 ati 21. Itumọ ẹbọ: ewe 20. Titori kini awọn keferi ṣe mbọ ẹsu? ewe 21.

ORI III — Itumọ 'Oluwa' ninu isin: ewe 23.— Bi Ọrunmla ti ṣe jẹ 'Amọimotàn': ewe. 24–32. Eeṣe ti Ifa fi ṣoro ikọ li àkọjari? ewe 33.— Ọnamgbà ni afọṣẹ–Ifa lẹnu: ewe.—33–38.

ORI IV — Itumọ 'Ọwa ati 'Ọlọwá' ati Ọlọwá aiyèrẹ́? ewe 39.—Eeṣe ti a kò gbọdọ yẹ Ọrunmla nipò? ewe 40–43.– Eeṣe ti a mpe Ọrunmla ni 'Opòki, Amù-idẹ-ṣ'oju? ewe 44.— Ọrunmla jẹ́ Ẹkùn, nitori kini? ewe. 45.

ORI V — Itumọ 'Igbo' bi oriiki Ọrunmla: ewe 47.–'Ọrọ': ewe 48–50. Ọwun—Ọpa–àrèkú—Aṣẹ—Angẹli Ikú: ewe. 51–58. A pe Ọrunmla ni 'Atoobàjaiye,'—nitori kini? ewe 59–62. A pe e ni 'A-b'iku-jigbò,'—nitori kini? ewe 63–65.

ORI VI —Tori kini a ṣe mpe Ọrunmla ni Ajiki, Ọgẹ́gẹ́ agb'aiye-gún? ewe 66–68. Ọmọlihorogbo: ewe 69–70. Awọn àmi Ọrunmla bi ikọ Olodumare,—Ọpá Ọtọtọọtọ, Irọfa ati Irukẹ̀rẹ, Ibojú: ewe 71–73. Oṣumare mbi ohun rere gbogbo fun ilo Ọrunmla: bawo? ewe 73–75. Bawo ni Ọrunmla ti ṣe ndù ori fun enia, —bawo li ó ti ṣe ntún ori aisian ṣe? Kili a mpe ni 'Ori aisiàn '? ewe 76–80.

**EZADEL ENTERPRISES (NIG.)**
**REGD 136832**

(*MANUFACTURER OF YORUBA NATIVE DRUGS & CHEMICALS*)

**SANCTUARY PRODUCTS**

1. SANCTUARY SOAP:– £5 : 5s
   For treating and preventing attack of hypertension and low blood pressure, stroke and paralysis.

2. CONCENTRATED SANCTUARY SOAP:– £6 : 10s
   For reducing heavy weights. For treating and preventing noise making or bell ringing in the head. Stiff neck, sleeplessness, general debility, high and low blood pressure.

3. SANCTUARY POWDER:– £2
   For checking rapid heart beatings, unnecessary fear, undue tiredness after little work or when ascending or descending hills or staircases and rejuvenating weak nerves. It cures RHEUMATISM.

4. SANCTUARY OINTMENT:– £2 10s
   External only. For treating stroke, paralysis, low blood presure and rheumatism.

5. SANCTUARY OIL:– 17/–6
   For eliminating diarrhoea, dysentery, constipation and other hypcohondriac diseases.

You can seek our help on other matters.

*Yours sincerely.*

REVD. E. A. LIJADU,
Ajihinrerelofe House,
64, Lokun Street,
P.O. Box 76,
Tel. 85, Ondo.

*Branch Office*:
5, Campbell Street,
Lagos.

*Printed by:-*

OMOLAYO STANDARD PRESS

IKERE ROAD, P. O. BOX 3,

TELEPHONE 102, ADO-EKITI.